
# MARYLAND
# Atọnà Awakọ

MARYLAND DEPARTMENT OF TRANSPORTATION
MOTOR VEHICLE ADMINISTRATION



Fún àlàyé síwájú si, kàn sí:

# mva.maryland.gov

6601 Ritchie Highway N.E.
Glen Burnie, MD 21062

410-768-7000
TTY fún àwọn tí ó ní ìṣòro etí 1-800-492-4575

MarylandMVA

MD_MVA

**October 2025 Edition**

Aṣẹ-adakọ

© Iṣakoso Ọkọ Ayọ̀kẹ́lẹ̀ Maryland, 2023

Gbogbo àwọn ẹ̀tọ́ wà ní ìpamọ́.

Ẹ̀ka Ètò Ìrìnnà ti Maryland, Ìṣàkóso Ọkọ̀ Ayọ́kẹ́lẹ́ (MDOT/MVA) ni ó ní ẹ̀tọ́ lórí àṣẹ àdàkọ iṣẹ́ yìí. Kò sí apákan inú ìwé yìí tí a lè ṣe àtúntẹ̀ rẹ̀ tàbí ṣe pínpín rẹ̀ ní ipòkípò tàbí ní ọ̀nàkọ́nà, yálà nípa ẹ̀rọ-oníná tabi ẹ̀rọ ọlọ́wọ́, ti ó fi mọ́ ṣíṣe ẹ̀dà, ìgbàsílẹ̀, tàbí nípa ọ̀nà ìpamọ́ àti ìgbàpadà àlàyé láìsí àkọsílẹ̀ ìgbanilááyè oní kíákíá láti ọdọ̀ MDOT/MVA.

Gbogbo àkóónú ni a lè lò ní òfẹ́ àtipé ó wà fún ìkẹ́kọ̀ọ́ Òfin Ọkọ̀ Ayọ́kẹ́lẹ́ Maryland. Èyíkéyìí àtúntẹ̀, lílò, pínpín, tàbí títà ohun èlò yìí tí a kò fi àṣẹ sí ni ó di èèwọ̀.

Jọ̀wọ́ darí gbogbo ìbéèrèkíbéèrè nípa pípèsè àwọn ẹ̀dà tàbí pínpín ohun èlò yìí sí: Alákóso MVA, 6601 Ritchie Highway N.E., Glen Burnie, MD 21062.

DL-002 (10-25)

# Àtẹ̀ránṣẹ́ Olùdarí

**Ẹ̀yin Awakọ̀ Ọjọ́ Ọ̀la:**

O fẹ́ gbé àwọn ìgbésẹ̀ láti gba ìwé ìrìnnà awakọ̀. Àsìkò ìduùnnú nìyí funún èyíkéyìí awakọ̀ tuntun! Ó ṣe pàtàkì láti rántí pé ànfàní ni wíwakọ̀, àtipé ò ń kópa láti ri pé àwọn ènìyàn wà ní àlàáfíà lójú ọ̀nà. Àwọn ohun tí ó ṣe pàtàkì láti mọ̀ pọ̀ – ìwé atọ́nà yìí ni olùdárí rẹ.

**Jẹ́ Awakọ̀ tí ó gba Ẹ̀mí là**

Bí o ti ń rin ìrìn-àjò lójú ọ̀nà Maryland, ìwọ máa ṣe àbápàdé àwọn awakọ̀ pẹ̀lú oníruúrú ọjọ́ orí àti àwọn tí wọ́n ni oríṣiríṣi ìpele òye. Àmọ́ gbogbo wa ni a ní àbùdá kam náà: ojúṣe láti kọ́ àwọn ẹlòmìíràn láti Jẹ́ Awakọ̀ tí ó ń gba ẹ̀mí là. Èyí túmọ̀sí pípa ẹ̀mí ara rẹ àti ti ẹlòmìíràn mọ́ ní ojú ọ̀nà. Gẹ́gẹ́ bí awakọ̀ tuntun, ó ṣe pàtàkì láti:

- Gba àkókò rẹ
- Jẹ́ kí àwọn òfin ìrìnnà yé ẹ
- Tẹ́tí sílẹ̀ kí o sì kọ́ ẹ̀kọ́ láti ọdọ̀ olùkọ́ àti olùkọ́ni rẹ
- Bọ̀wọ̀ fún àwọn èrò ọkọ̀ àti àwọn awakọ̀ mìíràn

Gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹ̀kọ́ tuntun mìíràn tí ò ń kọ́, òye rẹ nínú ọkọ̀ máa tẹ̀síwájú látàrí ìrírí rẹ lórí oríṣiríṣi ọ̀nà, lábẹ́ oríṣiríṣi àkókò àti ní ibi ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Bí àpẹẹrẹ, wíwakọ̀ ní àkókò tí ojú ọjọ́ kò dára, nínú sún-kẹrẹ-fàkẹrẹ, àti ní àkókò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nínú ọjọ́. Ẹnìkankan wa ni ó ní ojúṣe ní gbogbo ìgbà tí a bá di ọrùn ọkọ̀ mú láti:

- Wakọ̀ pẹ̀lú ìrònú.
- Fi ara balẹ̀.
- Lo ìgbàdí ọkọ̀.
- Tẹ̀lé gbìndéke eré sísá.
- Wò lẹ́ẹ̀méjì fún ọ̀kadà.
- Ṣe àjọpin ọ̀nà pẹ̀lú àwọn ẹlẹ́sẹ̀ (àwọn tí ó ń fi ẹsẹ̀ rìn) àti oní kẹ̀kẹ́

Ó kù sọ́wọ́ rẹ láti ṣe ìpinnu alálàáfíà ní ọrùn ọkọ̀. Ó ṣeni láànú pé ní ojoojúmọ́, ẹgbẹgbẹ̀rún awọn awakọ̀ máa ń pinnu láti wakọ̀ pẹ̀lú ìdíwọ́ tàbí àlébù, sísáré tàbí da ìbínú wọn lé ẹlọ̀míràn lórí ní ojú ònà. Èyí fi àwọn àti àwọn mìíràn sínú ewu. Gbogbo wa ni a gbọ́dọ̀ ṣe àfẹ́ri ara wa.

Àlàáfíà ni ó jẹ Ẹ̀ka Maryland tí ó ń ṣe àbójútó ètò ìrìnnà ọkọ̀ (MVA) lógún. Àfojúsùn wa ni láti dé ìpele àìsí ìpalára (kò sí iku Kankan) lójú ọ̀nà Maryland nítorí ẹ̀mi kan tí ó sọnù ṣe iyebíye lọ́pọ̀lọ́pọ̀.

Lẹ́yìn tí o bá ti ka ìwé atọ́nà yìí tán, ṣe àyẹ̀wò òye rẹ  nípa òfin ìrìnnà nípa ṣíṣe ìdánwò ẹ̀kọ́ wa lórí ayélujára.  Ó wà lórí ìtàkùn ayélujára MVA, mva.maryland.gov/drivers.

À ń retí láti ràn ẹ́ lọ́wọ́.

Wà láìléwu,



Administrator, MDOT MVA

# Àwọn Àtẹ àkòónú


**ÌPÍN 1: Àwọn Àmúyẹ Àyẹ̀wò Wíwakọ̀ . . . . . . 7**

A. Àyẹ̀wò Ìríran ........7
B. Ìdánwò lórí òye ........7
C. Ìdánwò lórí òye Wíwakọ̀ ........7
D. Àwọn Ipò Àìlera tí a lè ṣe àfisùn rẹ̀........8

**ÌPÍN 2: Àwọn Àmúyẹ Ìwe-Àṣẹ àti Ìlànà . . . . 9**

A. Awakọ̀ Onírúkì/Erọ Elétò Ìwé Onípele Ńlá .9
B. Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o ........9
C. Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ Onígbà díẹ̀........10
D. Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀........11
E. Àjọbọwọ́lù Màjẹ̀ṣín fún Ìforúkọsílẹ̀ Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ ........11
F. Alájùmọ̀ bọwọ́lú ìfagiléìwé ìrìnnà àwọn màjèṣín ........11
G. Ìwé ìrìnnà awakọ̀ ti Òkè- Òkun ........11
H. Ìpín Dọ́gbadọ́gba fún gbogbo Olùbárà ........12

**ÌPÍN 3: Ìpìnlẹ̀ṣẹ Wíwakọ̀. . . . . . . . . . . . . . . . . . 13**

A. Wa Ọkọ̀ pẹ̀lú Ìdáàbòbò ........13
B. Apá Ọ̀tún........13
C. Níní Òye Sísáré Ọkọ̀........14
D. Títẹ̀lé Títakété sí Ara-ẹni........14
E. Dídúró Títakété sí Ara-ẹni ........15
F. Wíwakọ̀ Lórí Ìlà........15
G. Yíyípadà........15
H. Àyípadà-U ........15
I. Kíkọjá ........15
J. Àwọn Òfin Ìgúnlẹ̀ Gbogboògbò........16

**ÌPÍN 4: Àwọn Amì, Atọ́ka àti Àlà Pèpé . . . . . 17**

A. Atọ́ka ètò ìrìnnà........17
Atọ́nà ọkọ̀ ........17
Atọ́ka Rírìnsọdá ........19
B. Àwọn Amì Ètò Ìrìnnà........20
Àwọn Àwọ̀ ........20
Àwọn Àmì Ìdarí........21
Àwọn Àmì Ìkìlọ̀ ........22
Orísị Àmì Ètò Ìrìnnà Mìíràn........23
C. Àwọn Àlà pèpé ........24
Àwọn Orísị Sísàmì sí Ìlà ........24
Àwọn Àlà pèpé miiran ........25
Àlà Pèpé Ẹlẹ́sẹ̀ àti Kẹ̀kẹ́........25

**ÌPÍN 5: Àwọn Àkókò Ìwakọ̀ àti Ìgbà. . . . . . . 27**

A. Wíwakọ̀ nínú Ìríran tí ó dínkù........27
B. Wíwakọ̀ ní Alẹ́ ........28
C. Wíwakọ̀ nínú Ìkúùkù........28
D. Wíwakọ̀ nínú Ojú-Ọjọ́ tí ó kù díẹ̀ káàtó ........28
E. Sikidi ........29
F. Agbára Inú Omi........29
G. Ọ̀nà-Ojú irin Òpópónà tí ó ń sọdá........30
H. Àbò Ibùdó Iṣẹ́ ........30
I. Àsúnjọ Súnkẹrẹ-Fàkẹrẹ Ọkọ̀ (Oríta )........31
J. Wíwakọ̀ ìpínlẹ̀-dé-ìpínlẹ̀ àti àwọn ọ̀nà aláàyè díẹ̀ ........31
K. Ètò Ìsìnkú ........31
L. Ọkọ̀ tí ó n rìn jẹ́jẹ́........32

**ÌPÍN 6: Ìwà Ọkọ̀ Wíwà Búburú ............ 33**

A. Ògógóró, Oògùn Olóró àti Ọkọ̀ Wíwà............33

B. Wíwakọ̀ Pẹ̀lú ara Kíkan àti Ìbínú ni Ojú-Ọ̀nà............34

C. Ìdíwọ́ nínú Ìwakọ̀............34

D. Títòògbé Lori Ọkọ̀ Wíwà............35

**ÌPÍN 7: Ṣíṣe Àjọpín Ànà .................. 37**

A. Ojú-Ọ̀nà títọ́ fún Ẹlẹ́sẹ̀............37

B. Àwọn Ọkọ̀ Pàjáwìrì............37

C. Àwọn Ọkọ̀ Ńlá àti Àwọn Ọkọ̀ Akérò............37

D. Àwọn Ọkọ̀ Ilé-Ìwé............38

E. Ọ̀kadà............38

F. Kẹ̀kẹ́............39

G. Mopeds ati Scooters............41

H. Níní Òye Ìmọ̀ Ẹ̀rọ Ọkọ̀............41

**ÌPÍN 8: Ìkọlura àti Dídúró Ọkọ̀ ............ 43**

A. Ìkọlura............43

B. Pàjáwìrí Ẹ̀gbẹ́ Ojú Ọ̀nà............44

C. Ìdúró Ètò Ìrìnnà............44

D. Òfin Ìfarahàn............45

**ÌPÍN 9: Àwọn Ìfòfindè Mìíràn, Òfin Rírú àti Ìjìyà rẹ̀ .................................. 47**

A. Ìfòfindè............47

B. Àyẹ̀wò Oògùn Olóró tàbí Ọ́ti -- Àfọwọ́sí Ẹlẹ́lọ̀ọ́............47

C. Gbígba ìwé ìdánimọ̀, ìwé ìrìnnà awakọ̀ ayédèrú tàbí èyí tí a parọ́ sí tàbí Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o............48

D. Àwọn ìgbésẹ̀ Adarí............48

E. Àwọn Ìjìyà............49

F. Lílo ibi Ìwàgúnlẹ̀ Aláàbọ̀-Ara, Ike Ìwé Ìrìnnà, àti Àpèlé............49

**ÌPÍN 10: Àwọn Àlàyé tí ó ṣe pàtàkì mìíràn .......................... 51**

A. Àwọn ìpele Ìlera láti fi ṣọwọ́ sí MVA............51

B. Adarí Awakọ̀ – Ohun tí wọ́n nílò àti Ojúṣe wọn............51

C. Olùfiẹ̀ya ara sílẹ̀............51

D. Fi Orúkọ sílẹ̀ láti dìbò............52

E. Ohun Ìnílò fún Adójútòfò............52

F. Òfin Ìgbàdí Ọkọ̀............52

G. Ìjòkó Àbò Ọmọdé............52

H. Àpò Afẹ́fẹ́............52

I. Ìtúsílẹ̀ pẹ̀lú Anti-lock Braking System (ABS)..52

J. Wíwọ Ìbòrí orin, Yẹtí orin àti àkìbọ etí ṣe èèwọ̀............53

K. Ìgúnlẹ̀ Fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́............53

L. Ìwa Ọkọ̀ gúnlẹ̀ inú ilé, Ìwa ọkọ̀ gúnlẹ̀ Ẹlẹ́yìn, Ìyípadà ọkọ̀ ẹlẹ́sẹ̀ méta............53

M. Àwọn Òfin àti Àṣírí fún Kẹ̀kẹ́ wíwà............53

N. Àwọn Ọkọ̀ Eléré Kékeré Oníná (Àwọn oríkì)............54

# Ṣe àbápàdé àwọn awakọ tí wọn gba ẹmí là ní Maryland.



Jẹ awakọ ti o gba ẹmi là

Jákèjádò ìwé atọka yìí, àwọn ẹka “Jẹ awakọ náà” wa máa sọ nípa ìpolongo wiwa ọkọ ní àwàyè kí o sì gba ẹmí là fún ẹ, àtipé wọn á tún pèsè àwọn àṣírí àwàyè fún ẹ! Fún àlàyé síwájú si lórí ìpolongo ”Jẹ Awakọ náà”, kàn sí:
ZeroDeathsMD.gov.

# ÌPÍN 1: Àwọn Àmúyẹ Àyẹ̀wò Wíwakọ̀

O gbọ́dọ̀ ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ kí o tó bẹ̀rẹ̀ sí ń wa ọkọ̀. Àwọn ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́, ọkọ̀ ẹlẹ́rù, àti àwọn àjàgbé eléjò jẹ́ àpẹrẹ àwọn ọkọ̀. Láti ní ìwé ìrìnnà awakọ̀, o ní láti ṣe àwọn ìdánwò kan kí o sì yege nínú rẹ̀. Àwọn àyẹ̀wò yĩí ni à ń pè ní àwọn àmúyẹ ìrìnnà. Lára àwọn àmúyẹ ìrìnnà ni:

- Àyẹ̀wò Ìríran.
- Ìdánwò lórí òye.
- Ìdánwò lórí òye wíwakọ̀.

Àwọn mĩíràn lè ní láti ní àmúyẹ mĩíràn láti fihàn pé wọ́n lè wakọ̀ láìléwu. Ẹ̀ka Maryland tí ó ń bojútó ètò ìrìnnà (MVA) máa jẹ́ kí o mọ̀ tí ó bá nílò láti ní àwọn àmúyẹ mĩíràn.

## A. Àyẹ̀wò Ìríran.

Àyẹ̀wò Ìríran máa ń ṣe àyẹ̀wò bí o ṣe lè ríran kedere sí. Àjọ MVA tàbí Dókítà rẹ lè ṣe àyẹ̀wò yĩí.

Láti kún ojú òṣùwọ̀n fún ìwé ìrìnnà awakọ̀, o gbọ́dọ̀ ní:

- Ìríran láti inú ìgò.
- Agbára ìríran ojú ó kéré tán 20/40 ní ojú kànkan.
- Ìtẹ̀síwájú ìríran ó kéré tán 140 dìgírìì.

Àjọ MVA tàbí Dókítà rẹ lè ṣàlàyé ohun tí èyí túmọ̀sí fún ẹ. Wọ́n á lè sọ fún ẹ bí o bá peregedé nínú àmúyẹ yĩí.

Bí o bá nílò ìgò ojú láti peregedé nínú àmúyẹ yĩí, o gbọ́dọ̀ máa lò wọ́n nígbà tí o bá ń wakọ̀. Ìwé ìfàyègbà rẹ máa sọ èyí.

Àfikún àlàyé wà lórí ìtàkùn MVA fún àwọn tí kò bá yege nínú àmúyẹ ìríran yĩí.

## B. Ìdánwò lórí òye

Ìdánwò lórí òye máa ń wò bóyá o mọ̀ nípa:

- Àwọn òfin ọkọ̀.
- Ìwà wíwakọ̀ láìléwu.
- Àwọn àmì ètò ìrìnnà.

Ìwé ìtọ́ni yĩí dá lórí àwọn àlàyé tí a máa dán ẹ wò lé lórí. O máa ṣe ìdánwò òye náà ní ojúkò MVA kan. Ìbéèrè 25 ni ó wà nínú ìdánwò náà. O má ní ìṣẹ́jú 20 láti ṣe ìdáwò náà. Wo ìpín 2.A bí o bá nílò àyè ọ̀tọ̀.

Ẹ̀kọ́ ìdánwò awakọ̀ lórí ayélujára wà lórí ìtàgùn MVA. Ẹ̀kọ́ náà ní àwọn ìbéèrè tí ó lè ràn ẹ́ lọ́wọ́ láti gbáradì fún ìdánwò lórí òye náà. **O tún gbọ́dọ̀ ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àlàyé tí ó wà nínú ìwé ìtọ́ni yĩí láti yege nínú ìdánwò lórí òye náà.**

## C. Ìdánwò lórí òye Wíwakọ̀.

Ìdánwòn ìrìnnà ni ọ̀nà tí MVA máa ń gbà láti mọ̀ bọ́yá o ní òye láti wa ọkọ̀ láìléwu  àti bí ọmọlúwàbí. Lára ìdáwò yĩí ni wíwa ọkọ̀ ní ààrín ìgboro àti ẹ̀kọ́ ọ̀tọ̀ ní ojúkò ìdánwò náà.

O gbọ́dọ̀ gba àyè sílẹ̀ láti ṣe ìdánwò òye awakọ̀ náà. Láti gba àyè sílẹ̀, o lè:

- Kàn sí mva.maryland.gov ki o si tẹ “Gba àyè sílẹ̀” tàbí
- Pe 410-768- 7000 tàbí 1-800-492-4575 (TTY fún àwọn odi àti àwọn tí ó nira fún láti gbọ́).

O maa ṣe ìdánwò òye ìrìnnà náà pẹ̀lú ọkọ̀ tí o gbé wá sí ojúkò ìdáwò náà. Ó gbọ́dọ̀ ní àwọn àmúyẹ yìí kí o tó lè lò ó fún ìdánwò náà:

- Ìwé ọkọ̀ náà àti ti àtẹ́wọ́gbà nọ́ńbà ọkọ̀ gbọ́dọ̀ pé.
- O gbọ́dọ̀ ní ìdáni ló pé ọkọ̀ náà ní ètò adójútòfò.

Ọkọ̀ náà gbọ́dọ̀ ní:

- Dúró re láti wà.
- Kò gbọ́dọ̀ ní ìla sisàn tàbí ohun mìíràn níwájú rẹ̀ tí ó lè dí ẹ lọ́wọ́ láti ríran kedere.
- Ní ó kéré tán ìlàjì àgbá epo-gaasi kan.

Aláàbójútó awakọ̀ kan gbọ́dọ̀ tẹ̀lé ẹ wá láti wa ṣe àyẹ̀wò ojúkò náà. Ìpín 10 Ìwé ìtọ́ni yìí ṣe àlàyé àwọn ẹni tí Aláàbójútó awakọ̀ jẹ́. Ìwọ àti ẹni tí ó ń fún ẹ ní ìdánwò nìkan ni a fi àyè gbà nínú ọkọ̀ náà ní àkókò ìdánwò náà. Ògbufò tí MVA fi ọwọ́ sí tún lè wà nínú ọkọ̀ náà bí o bá nílò ìkan.

Láti lè mú kí ìwọ àti àwọn òṣìṣẹ́ MVA wà ní àlàáfíà àti ara pípé:

- A gbà ẹ́ níyànjú láti jẹ́ kí afẹ́fẹ́ máa fẹ́ nínú ọkọ̀ náà ni àkókò ìdánwò náà. Bí àpẹrẹ, nípa ṣíṣí àwọn fèrèsé rẹ̀ sílẹ̀. Ẹni tí ó ń fún ẹ ní ìdánwò náà lè dá àbá ohun mìíràn.
- O lè wọ ìbòjú ní àkókò ìdánwò náà bí ó bá wù ẹ́.
- Bí ara rẹ kò bá yá dáradára, o lè tún àyè mìíràn gbà.

## D. Àwọn Ipò Àìlera tí a lè ṣe àfisùn rẹ̀

O gbọ́dọ̀ jẹ́ kí MVA mọ̀ bí o bá ní  àìlera kan tí ó lè ní ipa lórí wíwakọ̀ rẹ. Àwọn òfin ìpínlẹ̀ nílò eléyìí. Wo Ìpín 10 fún Àwọn akojọ àìlera tí o gbọ́dọ̀ ṣe àfisùn rẹ̀ àti àkókò láti ṣe àfisùn won.



**Nję o mọ pe awọn oṣiṣẹ ojú opopona yọ ju miliọnu meji pọun idọti kuro ni awọn opopona ipinlẹ ni ọdun kọọkan? Awọn itanran fun idalẹnu-àìtọ le jẹ to $1500 tabi ọjọ 30 ninu túbú.**

# ÌPÍN 2: Àwọn Àmúyẹ Ìwe-Àṣẹ àti Ìlànà

Ìpín yìí ń ṣe àlàyé àwọn ohun tí o gbọ́dọ̀ ṣe láti gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ ti Maryland. Àwọn àlàyé yìí wà fún àwọn tí wọ́n fẹ́ gba "ìwé ìrìnnà awakọ̀ tí kìí ṣe ti ọlọ́kọ̀ èrò". ìwé ìrìnnà awakọ̀ tí kìí ṣe ti ọlọ́kọ̀ èrò fi àyè gbà ẹ́ láti wa àwọn ọkọ̀ gbogboògbò bíi ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́, ọkọ̀ alajá-ẹ̀yìn, àti ọkọ̀ aláàyè ẹ̀yìn. A sì tún ń pè é ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ onípele C.

Lati bẹrẹ ilana naa, o gbọdọ ṣe ipinnu lati pade lati ṣabẹwo si eyikeyi ẹka MVA. Ní ìgbà tí o ba fi orúkọ sílẹ̀, o gbọ́dọ̀ mú àwọn nǹkan wònyí wá:

- Ìwé (àkọsílẹ̀) tí ó tọ́ka ọjọ́ orí rẹ. Orúkọ rẹ ní kíkún gbọ́dọ̀ wà nínú èyí. Àwọn àpẹrẹ ni ìwé ọjọ́ ìbí rẹ tàbí ìwé ìrìnnà passport rẹ.
- Ìwé tí ó tọ́ka orírun rẹ ní pàtó (fún àwọn tí a kò bí ní United States). Bí o bá wà ní àjọ ọmọ ológun tí kò sì bí ẹ ní U.S, ìwọ kò nílò láti wá pẹ̀lú ìwé aṣàfiàn orírun.
- Nọ́ńbà Social Security rẹ (SSN), tàbí ẹ̀rí pé ìwọ kò yẹ fún SSN.
- Ìwé méjì tí ó tọ́ka pè ò ń gbé ni Maryland.

O gbọ́dọ̀ mú ojúlówó àwọn ìwé náà wá tàbí ẹ̀dà tí àjọ tí ó pèsè rẹ̀ fún ẹ bu ọwọ́ lù. Àjọ MVA kò ní tẹ́wọ́ gba ẹ̀dà ìwé, àbọwọ́lù amòfin, tàbí ìwé tí a ti pààrọ̀ tàbí pa ohun inú rẹ̀ rẹ́.

Jọ̀wọ́ kàn sí ìtàkùn wa fún àkọsílẹ̀ àwọn ìwé tí ó jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà níwájú MVA.

## A. Awakọ̀ Onírúkì/Erọ Elétò Ìwé Onípele Ńlá

Ìlànà tí o má atẹ̀lé láti gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ ọlọ́kọ̀ èrò ni à ń pè ní Awakọ̀ Onírúkì/Erọ Elétò Ìwé Awakọ̀ Onípele ńlá (GLS). Ìwọ máa tọ ìpele GLS yìí bí ìwọ kò bá tíì gba iwé ìrìnnà awakọ̀ rí. Ó dà lórí oníruúrú ènìyàn pẹ̀lú ọjọ́-orí ìyówù tí ó peregedé láti fi orúkọ sílẹ̀ fún ìwá ìrìnnà awakọ̀. Ìwọ máa bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú gbigba Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ léyìn náà ni Ìwé ìrìnnà Awakọ̀ Onígbà díẹ̀. Ìgbésẹ̀ yìí máa fún ẹ ní ìrírí wíwakọ̀ kí o tó "sọda" sí Ìwé Ìrìnnà Awakò. Tẹ̀síwajú láti máa kàwé kí ó lè kọ́ ẹ̀kọ́ si.

## B. Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o

Bí ìwọ kò bá tíì ní Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ ti gbogboògbò ri, gba ìpele 1 Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o. Ìwé ààyè náà lè lò tó ọdún 2̀. O gbọ́dọ̀ yege nínú àyẹ̀wò ìríran àti ìdánwò òye láti lè gba àyè ìwé yìí.

Bí o bá ti ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ tẹ́lẹ̀ rí àtipé o nílò ìpele mìíràn ìwé ìrìnnà awakọ̀, ó gbọ́dọ̀ fi orúkọ sílẹ̀ fún Ìpele 2 Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o. O gbọ́dọ̀ jẹ́ ọmọ ọdún ó kéré tán 16 àti oṣù 6. Ìpele 2 Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o lè lò tó ọjọ́ 180. O lè ṣe ìdánwò wíwakọ̀ náà fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ kíkún nígbà tí o bá ti ní ìwé àyè yìí fún ọjọ́ 14.

Iye àkókò tí o lè ní láti ní Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o kí o tó lè ní àǹfàní fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀ da lori ọjọ ori rẹ. Àwọn tí ó fi orúkọ sílẹ̀ fún ìwé àyè ni a ń pè ní "Olùforúkọsílẹ̀".

### Àwọn Olùforúkọsílẹ̀ tí wọ́n kéré ju ọdún 25 lọ:

- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ọmọ ọdún 15 àti oṣù 9 ó kéré tán.
- Bí o bá kéré ju ọdún 18, òbí rẹ tàbí alágbàtọ́ gbọ́dọ̀ fi ọwọ́ sí ìwé na pẹ̀lú rẹ.
- Bí o bá kéré ju ọdún 16, o gbọ́dọ̀ pèsè Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ fọ́ọ̀mù àfọwọ́sí ilé-ìwé.

Nígbà tí o ní Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́, o gbọ́dọ̀:

- Parí ìwé ètò ẹ̀kọ́ awakọ̀ ti Maryland. Ó máa ń ran àwọn awakọ̀ tuntun lọ́wọ́ láti kọ́ nípa àlàyé tàbí ìmọ̀ọ́ṣe láti lè wa ọkọ̀. Orí ìtàkùn MVA ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ilé-ìwé awakọ̀ tí wọ́n fi ọwọ́ sí láti ṣe ètò yìí. **ÀTI**
- Kọ́ bí wọ́n ti ń wa ọkọ̀ ó kéré tán wákàtí 60 pẹ̀lú Olùtọ́ni awakọ̀. Èyí ni wọ́n ń pè ní wákàtí ẹ̀kọ́. Ó kéré tán, a gbọ́dọ̀ rí wákàtí ẹ̀kọ́ 10 láàárín ìṣẹ́jú 30 kí òòrùn tó wọ̀ àti ìṣẹ́jú 30 kí òòrùn tó yọ. **ÀTI**
- Tẹ̀síwáwájú láti máa ṣe ìmọ̀ọ́ṣe ẹ̀kọ́ láti ṣe àkọsílẹ̀ wákàtí ẹ̀kọ́ rẹ. O lè rí ìmọ̀ọ́ṣe ẹ̀ko náà lóri ìtàkùn MVA.

## Àwọn Olùforúkọsílẹ̀ tí wọ́n to ọdún 25 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ:

Nígbà tí o ní Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́, o gbọ́dọ̀:

- Parí ìwé ètò ẹ̀kọ́ awakọ̀ ti Maryland. **ÀTI**
- Ṣe pari ó kéré tán wákàtí ẹ̀ko 14 pẹ̀lú Olùtọ́ni awako kaǹ. Ó kéré tán, a gbọ́dọ̀ lo wákàtí ẹ̀kọ́ 3 láàárín ìṣẹ́jú 30 kí òòrùn tó wọ̀ àti ìṣẹ́jú 30 kí òòrùn tó yọ. **ÀTI**
- Tẹ̀síwáwájú láti máa ṣe ìmọ̀ọ́ṣe ẹ̀kọ́ láti ṣe àkọsílẹ̀ wákàtí ẹ̀kọ́ rẹ. ìmọ̀ọ́ṣe ẹ̀ko náà wa lóri ìtàkùn MVA.

O gbọ́dọ̀ ní ìwé àyè rẹ fún ó kéré tán ọjọ́ 45 kí o tó lè kójú ọ̀ṣùwọ̀n láti gba Ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀.

## Rírú Òfin

Nígbà mĩràn, ó gbọ́dọ̀ ní ìwé àyè rẹ fún àkókò tí ó pọ̀ díẹ̀ si kí o tó lè kójú òṣùwọ̀n fun Ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀:

- Ní ọjọ́ orí ìyówù, bí a bá ti dá ẹ lẹ́jọ́ rí tàbí a ti fún ẹ ní ìkìlọ̀ ní iwájú adájọ́ (PBJ) rí látarí rírú òfin, o gbọ́dọ̀ mú ìwé àyè rẹ fún ó kéré tán oṣù 9 láti ọjọ́ tí ó kẹ́yìn tí a dá ẹ lẹ́jọ́ tàbí tí a fi ẹ̀sùn PBJ kàn ẹ́ pé o rú òfin. Èyí tún dúró bí a bá ti dá ẹ dúró fún ìdí kankan ri. Ó gbọ́dọ̀ peregede lórí gbogbo ìyókù àmúyẹ GLS tí a ṣàlàyé lókè kí o tó lè kún ojú òṣùwọ̀n láti lè ṣe ìdánwò ìrìnnà.
- Bí o bá kéré ju ọdún 18, o gbọ́dọ̀ ní ìwé àyè náà fún ó kéré tán oṣù 9 láìrú òfin Kankan kí o tó lè kún ojú òṣùwọ̀n fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀.
- Bí o bá jé omo ọdún 18 pẹ̀lú ìwé ẹ̀rí ilé-ẹ̀kó girama tàbí GED, tàbí ọjọ́ orí 19-24, o gbọ́dọ̀ ní ìwé àyè náà fún ó kéré tán fún oṣù 3 láìrú òfin Kankan kí o tó lè kún ojú òṣùwọ̀n fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀

## C. Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ Onígbà díẹ̀

Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ Onígbà díẹ̀ ni a máa ń fún àwọn awakọ̀ tuntun tí wọn kò tĩì ní Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ rí. Èyí gbà ẹ́ láyè láti wa ọkọ̀ láìsí Olùtọ́ni ṣùgbọ́n pẹ̀lú gbèǹdéke. Lára àwọn gbèǹdéke náà ni kò gbọ́dọ̀ sí èrò ọkọ̀ àtipé kò sí wíwakọ̀ alẹ́. O ní Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ Onígbà díẹ̀ fún ó kéré tán oṣù 18 kí o tó lè kún ojú òṣùwọ̀n fún Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ gbogboògbò.

Bí o bá fẹ́ fẹ́ gòkè láti orí Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ lọ sí orí Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ Onígbà díẹ̀, o gbọ́dọ̀:

- Ti parí láìsí ìyọnu ètò ẹ̀kọ́ awakọ̀ tí Maryland fi ọwọ́ sí.
- Ní Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ tí ó ṣì ń ṣiṣẹ́ tàbí èyí tí kòì ti pari iṣẹ́ .

- Ní Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀ọ́ láìsí rírú òfin tí ó jẹ mọ́ irúfẹ́ àkókò ti a ṣàlàyé lókè.
- Láìsí rírú òfin kan tí ó wà nílẹ̀ tàbí ìfòfindè ní iwájú adájọ kan lórí ẹjọ́ Kankan tí ó wà nílẹ̀ ní àkókò tí a ṣàpèjúwe lókè.
- Ṣe ìfilélẹ̀ ìwé tí ó tọ́ka ẹ̀kọ́ wíwakọ̀ àti ìmọ̀ọ̀ṣe tí a ti parí tí a sì bu ọwọ́ lù. Èyí gbọ́dọ̀ fi hàn pé o ti parí ó kéré tán wákàtí 60 ní wíwakọ̀ pẹ̀lú olùtọ́ni awakọ̀ (14 bí o bá jẹ́ 25 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ)
- Yíyege nínú ìdánwò oye ìrìnnà.

## D. Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀

Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ ni ìpele tí ó kẹ́yìn nínú ìdàgbàsókè ètò Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀.

Láti kún ojú òṣùwọ̀n fún ìwé ìrìnnà awakọ̀, o gbọ́dọ̀:

- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ó kéré tán omo ọdún 18.
- Ti ní Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ onígbà díẹ̀ fún ó kéré tán oṣù 18.
- Láìsí rírú òfin kan tí ó wà nílẹ̀ tàbí ìfòfindè ní iwájú adájọ kan lórí ẹjọ́ Kankan tí ó wà nílẹ̀ láàárín oṣù 18 sẹ́yìn.

Nígbà tí o bá ti peregede nínú gbogbo àbùdá yìí, ní ẹsẹ̀kẹsẹ̀ ni MVA máa yí Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ onígbà díẹ̀ rẹ padà sí Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀. Ìwé pélébé tí ó ń tọ́ka ìyípadà yìí ni a máa fi ránṣẹ́ sí ẹ. O gbọ́dọ̀ mú ìwé pélébé yìí dání pẹ̀lú Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ onígbà díẹ̀.

## E. Àjọbọwọ́lù Màjẹ̀ṣín fún Ìforúkọsílẹ̀ Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀

Bí o bá kéré ju ọdún 18 lọ, Màjẹ̀ṣín ni ẹ́. Màjẹ̀ṣín gbọ́dọ̀ ní òbí kan tàbí alágbàtọ́ láti jọ bọ́wọ̀lu ìwé. Èyí túmọ̀sí pé ẹ máa jọ bu ọwọ́ lùú ni. O gbọ́dọ̀ fi ẹ̀rí lélẹ̀ pé òbí tàbí alágbàtọ́ rẹ ni wọ́n. Àpẹẹrẹ ẹ̀rí ni:

- Ojúlówó ìwé ọjọ́ ìbí tàbí èyí tí a bu ọwọ́ lù tí ó ní orúkọ àwọn òbí rẹ tàbí
- Ìwé ilé-ẹjọ́ tí ó ṣe àfihàn òbí nípa òfin.

Bí o bá ti ní ọkọ tàbí ìyàwó tí ó jẹ́ ọdún 18 tàbí jùbẹ́ẹ̀ lọ wọ́n lè bá ẹ ṣe àjọbọwọ́lù. O gbọ́dọ̀ fi ẹ̀rí lélẹ̀ pé ó ti ní ọkọ tàbí ìyàwó.

Bí ìwọ kò bá ní òbí, alagbàtó, ọkọ tàbí ìyàwó, àgbàlágbà tí ó bá ṣe é gbọ́kàn lé bá ẹ ṣe àjọbọwọ́lù bí o bá kéré ju ọdún 18 lọ. Àpẹẹrẹ ni olùgbanisíṣẹ́ àgbàlágbà.  Ní irú àkókò yìí, o lè fi ẹ̀rí ìwé ikú òbí rẹ lélẹ̀ tàbí ìwé òmìnira. Ìwé òmìnira ń tọ́ka síi pé ilé-ẹjọ́ ti fi ìdí rẹ̀ mulẹ̀ pé màjẹ̀ṣín kan kò sí lábẹ́ àbójútó àwọn òbí.

## F. Alájùmọ̀ bọwọ́lú ìfagiléìwé ìrìnnà àwọn màjẹ̀ṣín

Alájọbọwọ́lù lè fagilé iwe-aṣẹ̀ tí màjẹ̀ṣín gbé jáde nípa fífi àkọsílẹ̀ ṣọ̀wọ́ fún Olùdári MVA. Ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ máa wà lábẹ́ ìfagilé títí di ìgbà tí o máa di ọdún 18, àyàfi bí alájọbọwọ́lù bá bu ọwọ́ lu  Ìforúkọsílẹ̀ tùntùn fun ọ. Wọ́n gbọ́dọ̀ peregede nínú àwọn àbùdá tí a ṣàlàyé lókè.

## G. Ìwé ìrìnnà awakọ̀ ti Òkè- Òkun

Bí o bá ní Ìwé ìrìnnà awakọ̀ láti Orílè-èdè miràn, o gbọ́dọ̀ parí ti ìsàlẹ̀ yìí láìkùnà kí o lè gba Ìwé ìrìnnà awakọ̀ ti Maryland:

- Àyẹ̀wò ojú.
- Ìdánwò lórí òye.
- Ìdánwò lórí òye ìrìnnà.
- Ètò ẹ̀kọ́ awakọ̀ lórí ààbò òpópónà o ní wákàtí mẹ́ta, tí MVA fọwọ́ sí. O lè wá àkọsílẹ̀ eléyìí lórí ìtàkùn MVA.

Bí Ìwé ìrìnnà awakọ̀ láti Òkè- Òkun kò sí ní èdè Òyìnbó, o gbọ́dọ̀ tún:

- Ní Ìwé ìrìnnà awakọ̀ Òkè- Òkun, tàbí
- Tu ìwé ìrìnnà awakọ̀ Òkè- Òkun rẹ sí èdè Òyìnbó.

A gbọ́dọ̀ ṣe ògbùfọ̀ ìwé lórí ìwé(ti ilé-iṣẹ́ ti):

- Ogbùfọ̀ tí MVA fi ọwọ́ sí tàbí ògbufọ̀ ilé-ẹjọ́, TÀBÍ
- Àjọ Ìrìnnà Òfúrufú ti Orílè-èdè rẹ

Àwọn ìwé yĩí gbọ́dọ̀ ní:

- Tí a tẹ̀/Kọ ní orúkọ ògufọ̀, ÀTI
- Nọ́ńbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀, ÀTI
- Abọwọ́lù Ògbufọ̀

## H. Ìpín Dọ́gbadọ́gba fún gbogbo Olùbárà

### Fún àwọn Olùbárà èdè òkè òkun

Àjọ MVA ń pèsè oríṣiríṣi ìwé àti àyẹ̀wò ní àwọn èdè mĩíràn fún àwọn olùbárà tí ó bá nílò rẹ̀.

Bí ó bá nira fún ẹ láti ṣe ìbánisọ̀rọ̀ ní èdè Òyìnbó, ìwọ lè lo ògbùfọ̀ nígbà tí o bá ṣe àbẹ̀wò sí MVA. Pàápàá nígbà tí o bá ń ṣe ìdánwò òye tàbí ìdánwò nípa ìrìn-àjò. Bí a bá pèsè ìdánwò nípa òye nínú èdè tí ò ń sọ, o gbọ́dọ̀ gbà á ní ó kéré tán ìgba 5 kí o tó lè lo ògbùfọ̀. O lè wo àkọsílẹ̀ àwọn ògbùfọ̀ tí a fọwọ́sí lórí ìtàkùn wa.

**ÀKÍYÈSÍ:** MVA kò gba owó láti lo Ògbùfọ̀. Àmọ́ ṣá, o ní láti san owó iṣẹ́ àwọn Ògbùfọ̀ fún wọn.

Bi o bá ní ògbùfọ̀ yálà sísọ ati/ tàbi onitùnmo nígbà tí o bá kàn sí MVA, wọ́n gbọ́dọ̀ fi iwé ìdánimọ̀ aláwòrán hàn (yálà ìwé ìdánimọ̀ awakọ̀ ti ìpínlẹ̀ tàbí ìwé ìdánimọ̀) kí wọ́n tó lè farahàn ní ojúkorojú. Àwọn òṣìṣẹ́ MVA máa fi ìdí rẹ̀ mulẹ̀ bóyá Ogbùfọ̀ náà wà lára àwọn tí a fi ọwọ́ sí.

**ÀKÍYÈSÍ:** Àwọn Ògbùfọ̀ tí wọ́n ń ṣisẹ́ fún òye/ ìmọ̀ọ́ṣe lè má lè ṣe iṣẹ́ mĩíràn fún Olùbárà tí a ń yẹ wò. Bí àpẹrẹ, wọn kò lè jẹ́rĩí lórí ibùgbé, kò le darí ilé-ìwé ìwakọ̀, tàbí ṣe àgbéjáde ètò ìyáni tàbí ìfifúnni àjọsọ.

### Fún Àwọn Olùbárà Aláàbọ̀ ara

MVA máa ń pèsè iléègbé fún àwọn Olùbárà Aláàbọ̀ ara tí wọ́n ń ṣe ìdánwò lórí òye tàbí ètò ìrinnà.  Lára wọn ni:

- Àfikún àsìkò fún ìdánwò ṣíṣe.
- Àtìlẹhyìn fún èdè àfọwọ́júwe (American Sign Language ati Atúmọ̀ Odi tí ó dáńtọ́)
- Àyẹ̀wò Ọ̀rọ̀
- Àwọn Olùka fọ̀nrán.
- Yẹtí ohùn
- Aṣèrànwọ́ Ojú.

MVA máa ń pèsè iléègbé lórí ìwúlò ẹni. Jọ̀wọ́ kàn sí aṣojú olùbánisọ̀rọ̀ lórí: feedback.mva.maryland.gov

### Káàdì Aṣàfihàn Ìdàgbàsókè Àìlera

Bí o bá ní Ìdàgbàsókè Àìlera, O lè yàn láti mú Káàdì Aṣàfihàn Ìdàgbàsókè Àìlera dání pẹ̀lú ìwé ìrìnnà awakọ̀. Aláwọ̀ búlúù ni káàdì náà, kò tóbi ju ìwé ìrìnnà awakọ̀ lọ. Ó tún ní àyè láti ṣe àkọsílẹ̀ àìlera rẹ, ọ̀nà tí ó dára jù láti bá ẹ sọ̀rọ̀, àti àwọn àlàyé mĩíràn tí o lè fẹ́ ṣe àjọpín rẹ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró.

Láti gbé Káàdì Aṣàfihàn Ìdàgbàsókè Àìlera kĩí ṣe ọ̀ranyàn – ìwọ ni o máa ṣe ìpinnu bóyá wà á niló ọ̀kan. Ìwọ, tàbí òbí rẹ, tàbí alágbàtọ́ rẹ̀ lè ní káàdì kan nípa kíkàn sí ibi tábìlì àlàyé nínú èyíkéyĩí ojúkò MVA.  MVA kò ní bèrè lọ́wọ́ rẹ láti pèsè àlàyé tàbí àwọn ìwé nípa àìlera rẹ láti gba káàdì yĩí.

# ÌPÍN 3: ÌPÌNLẸ̀ṢẸ WÍWAKỌ̀

Kí o tó wakọ̀:

- Ìwọ àti ọkọ̀ rẹ gbọ́dọ̀ wà ní ipò tí ó dára láti rìnnà.
- O gbọ́dọ̀ ní ìwé àyè tàbí ìwé ìrìnnà awakọ̀ , àti Káàdì àkọsílẹ̀ lórí ọkọ̀.
- O gbọ́dọ̀ ṣe àtúnṣe ìjòkó àti jìgì àyẹ̀gbẹ̀ ọkọ̀ rẹ, àti
- O gbọ́dọ̀ ri dájú pé ìwọ àti gbogbo èrò inú ọkọ̀ ń lo ìgbádí ọkọ̀ wọn.

## A. Wa Ọkọ̀ pẹ̀lú Ìdáàbòbò

Òfin ìpìnlẹ̀ wíwakọ̀ ni pé, ní gbogbo ìgbà, awakọ̀ gbọ́dọ̀ máa darí ọkọ̀ kí ó máà sí ìjàǹbá. Nígbà tí o bá ń wa ọkọ̀, ojúṣe rẹ ni láti dárí rẹ̀ kí ó máà sí ewu. Èyí máa dín ewu kù fún ìwọ, àwọn èrò ọkọ̀ rẹ àti àwọn mìíràn tí ó ń lo ọ̀nà náà.

### Ìwádìí Ìríran/Ìpolongo Awakọ̀

O gbọ́dọ̀ máa ṣe ìpinnu lóòrèkóòrè láti jẹ́ awakọ̀ láìséwu. Láti ṣe èyí, o gbọ́dọ̀ mọ ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àyíká ọkọ̀ rẹ ní gbogbo ìgbà. Nípa wíwo àyíká rẹ ní gbogbo ìgbà máa ràn ẹ́ lọ́wọ́ láti rí àwọn ewu tí ó lè mú kí o díwọ̀ eré kù tàbí pààrọ̀ ìlà. Lára èyí ni wiwoiwájú, àwọn ẹ̀gbẹ́ àti ẹ̀yìn ọkọ̀ rẹ

Nípa ṣíṣe ìwádìí sílẹ̀ àti ṣíṣetán láti pàárọ̀ eré sísá rẹ tàbí pípàárọ̀ àwọn ìlà, o lè wakọ̀ pẹ̀lú ààbò síi wàá sì ní àsìkò láti dá àwọn ewu mọ̀. Eleyìí ni à ń pè ní wíwa ọkọ̀ pẹ̀lú ìdáàbòbò.

### Kíkápá Ewu

Wíwakọ̀ jẹ́ iṣẹ́ tí ó ní ewu.  Wo àwọn ìgbésẹ̀ ìsàlẹ̀ yìí láti kápá ewu kí o sì jẹ́ awakọ̀ aláìléwu àti èyí tí ó ṣe  gbara lé:

- Ṣe àtúnṣe eré sísá rẹ,ìjòkó àti ojú ọ̀nà láti.
- Jára sí ipò ọ̀nà.
- Wà nínú ìdarí ọkọ̀ rẹ.
- Ṣe àfikún sí àsìkò tí o ní láti dáhùn sí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àyíká rẹ.
- Jẹ́ kí àwọn awakọ̀ mìíràn mọ ohun tí o fẹ́ ṣe nípa lílo àwọn atóka ìyípo, abbl.
- Jẹ́ kí àlàfo tí ó dára wà láàárín ọkọ̀ rẹ  àti àwọn ẹlòmìíràn tí wọ́n ń lo ọ̀nà yìí.
- Ìwọ má ṣe ròpé àwọn awakọ̀ ìyókù máa ṣe ohun tí ó yẹ kí wọ́n ṣe.
- Máa wà ní ìṣọ́ra ní gbogbo ìgbà.

## B. Apá Ọ̀tún

Òfin apá ọ̀tún máa ń mú kí gbogbo àwọn tí ó wà ní ojú ọ̀nà wà ní àìléwu. Òfin yi sọ àkókò tí o lè yọ̀nda apá ọ̀tún fún àwọn ẹlòmíràn. Yíyọ̀nda apá ọ̀tún túmọ̀ sí láti gbà kí àwọn awakọ̀ mìíràn, oníkẹ̀kẹ́ tàbí ẹlẹ́sẹ̀ láti kọ́ja rẹ tàbí láti sọdá ọ̀nà ní iwájú rẹ. Èyí túmọ̀sí kí o jẹ́ kí wọ́n kọ́kọ́ lọ.

Bí oó tilẹ̀ jẹ́ pé òfin yìí ṣe àlàyé ẹni tí ó yẹ kí ó kọ́kọ́ lọ ní oríṣiríṣi ipò, máà ṣe rò pé ìwọ ni o ní ẹ̀tọ́ yìí nígbà kankan (ẹ̀tọ́ láti kọ́kọ́ lọ ). O gbọ́dọ̀ máa wo ipò àti gbogbo ohun tí ó wà ní àyíká ní gbogbo ìgbà.

O gbọ́dọ̀ yọ̀nda ẹ̀tọ́ yìí fún:

- Awakọ̀ tí ó wà níbẹ̀ tàbí tí ó kọ́kọ́ dé ibi oríta náà.
- Awakọ̀ tí ó wà ní apá ọ̀tún rẹ bí ẹ̀yin méjèèjì bá dé oríta ní ìgbà kan náà.
- Awakọ̀ tí ó wà ní apá ọ̀tún rẹ ní oríta mẹ́rin níbi tí àmì ìdádúró wà.
- Ẹlẹ́sẹ̀, oníkẹ̀kẹ́ àti àwọn awakọ̀ mìíràn tí wọ́n wà níí ibi oríta yìí.

- Awakọ̀ tí ó ti kọ́kọ́ wà ní ojú ọ̀nà nibí o ti dúró nií ibi oríta mẹ́ta.
- Àwọn awakọ̀ mĩ́ràn , bí ìwọ bá ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dé ibi oríta yĩ́ nií ibi tí àmì kan ti kọjú sí ẹ.
- Awakọ̀ tí ó wà ní ilà adojúkọ̀, nígbà tí ìwọ bá fẹ́ yà ní ẹ̀gbẹ́ òsì. ilà adojúkọ̀ni abala títì nií ibi tí àwọn ọkọ̀ ti ó nlọ̀ sí ọ̀nà mĩ́ràn kọjú sí.
- Àwọn awakọ̀ tí ó wà ní ojú ọ̀nà tí ìwọ ṣẹ̀ṣẹ̀ ń wọ̀ láti ọ̀nà mĩ́ràn tabi ọ̀nà àdàni.
- Awọn awakọ̀ tí wọ́n ti kọ́kọ́ wà lórí títí márosẹ̀, bí ìwọ bá wà nií ìyànà tàbí o ṣẹ̀ṣẹ̀ fẹ́ gbéra.

## C. Nínì Òye Sísáré Ọkọ̀

Àwọn àmì ojú òpópónà máa ń sọ ìwọ̀n tí o gbọ́dọ̀ sáré mọ. Àwọn ìwọ̀n eré sísá tí wọ́n lẹ̀ yĩ́ ni ìwọ̀n tí ó pọ̀ jù tí o gbọ́dọ̀ sá nínú òfin lójú ọ̀nà bí ohun gbogbo bá wà bí ó ti yẹ kí ó rí (ní dáradára ) Ìwọ kò gbọ́dọ̀ sáré ju ìwọ̀n eré sísá yĩ́. Ojúṣe rẹ láti máa sáré ní ìwọ̀n tí kò mú ewu dání.

Ohun tí ó dára jù ni láti wakọ̀ ní ìwọ̀n tí àwọn ọkọ̀ ìyókù ń rìn, títí dé ibi ìwọ̀n tí ó pọ̀ jù.  Nií ìgbà tí ènìyàn bá ń sáré ní ìwọ̀n tí ó kéré ju àwọn ìyókù, ó máa ń fi àyè sílẹ̀ fún àwọn ọkọ̀ mĩ́ràn láti kọjá ẹni. Èyí lè mú kí ìkọlura wáyé.

### Sísáré

Sísáré kọjá ìwọ̀n gbèndéke jẹ́ ọkan lára ìdí ti ìjànbá ọkọ̀ fi máa ń wáyé. Sísáré àsájù kò pa àkókò mọ́ àtipé oó máa ń yọrí sí ìpinnu tí ó máa ń fi ẹ̀mí àwọn ènìyàn sínú ewu. Sísáré kọjá ìwọ̀n nií ewu ńlá àti ipa búburú nítorí pé:

- Ó máa ń dí agbára rẹ kù láti lè yà àti láti lè wakọ̀ ní ibi ìdíwọ̀ tí ó le lójú ọ̀nà.
- Ó má agba àsìkò pípẹ́ láti mú ọkọ̀ rẹ dúró.
- Ó ń dí àǹfàní rẹ kù láti dá ewu mọ̀ àti láti lè gbé ìgbésẹ̀ lórí ohun tí kò dára tàbí àkókò tí ó mú ewu dání.
- Ó ń fi àyè sílẹ̀ fún jàǹbá ìkọlura ọkọ̀ nítorí àwọn ọkọ̀ mĩ́ràn, oníkẹ̀kẹ́ tàbí ẹlẹsẹ̀ lè má lè mọ bí ó ti ń ṣe ẹ́ láti ọdọ̀ wọn.
- Ó ń mú kí agbara àti ipa ìkọlura ọkọ̀ kí ó pọ̀ si, èyí tí ó lè yọrí sí ipálárá ńlá tàbí ikú.

### Eré Sísá fún Oríṣiríṣi Àsìkò

O gbọ́dọ̀ ṣe ìdámọ̀ àti àtúnṣe sí eré sísá rẹ ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀. Òfin Ìrìnnà Maryland gbà kí o sáré ní ìwọ̀nba kí o sì ṣe àkíyèsí ewu tí ó wà lọ́nà tàbí èyí tí ó lè wáyé. Eré sísá rẹ lè kéré ju ìwọn tí a fihàn, látàrí bí ọ̀nà náà ṣe rí ṣùgbọ́n ohun ti ó tako òfin ni láti sáré kọjá ìwọn eré sísá tí fihàn.

O gbọ́dọ̀ dí eré sísá rẹ kù nínú àwọn àyè wọ̀nyí kí o lè wà ní àìléwu:

- Ìyànà tàbí òkè – níbi tí ó ti ṣòro láti rí iwájú.
- Ọ̀nà yíyọ́.
- Àwọn ọ̀nà tí àwọn ẹlẹ́sẹ̀ tàbí ẹranko lè wà.
- Ilé ìtajà, ilé ìgbọ́kọ̀sí tàbí àwọn ibi ilé èrò.
- Súnkẹrẹ fàkẹrẹ.
- Ibi Afárá tín-rín àti Ọ̀gbun.
- Ojúkò ìwé.
- Àwọn ilé-ìwé, ibi ìṣeré, àti àdúgbò.
- Ojú irin tí ó sọ́da. Ìgbà yĩ́ ni ojú irin reluwé àti òpópónà fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́.

## D. Títẹ̀lé Títakété sí Ara-ẹni

Ní gbogbo ìgbà ni kí ọkọ̀ rẹ ta kété sí éyi ti ó wa ni iwájú rẹ. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìkọlura ọkọ̀ ní ó máa ń wáyé nítorí àwọn ọkọ̀ súnmọ́ ara wọn jù. MVA dá àbá kí ìtakété àárín ọkọ̀ jẹ́ ìwọn ìṣẹ́jú aaya

3 sí 4 ní ìgbà tí ohun gbogbo wà bí ó ti yẹ. Èyí tí  ó sie pé ó máa agba ìṣẹ́jú ààyá 3 sí 4 láti dé ibi tí ọkọ̀ iwájú rẹ wà. Ibi ìtọ́kasí jẹ́ ohun kan tí ó wà níwájú bí afárá, ibi ìdádúró, àmì tàbí ìjánu eré. Yan ibi ìtọ́kasí kan lati mọ̀ bóyá o wà ní àìléwu. Bí ọkọ̀ iwájú rẹ bá ti kọ́ja ohun iwájú rẹ, bẹ̀rẹ̀ láti kà 1 ẹgbẹ̀rún kan, 2 ẹgbẹ̀rún kan, 3 ẹgbẹ̀rún kan abbl. Bí o bá ti dé 3 ẹgbẹ̀rún tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ kí ó tó dé ohun náà, o wà ní ó kéré tán ìṣẹ́jú ààyá 3 tàbí jù bẹ́ẹ̀ sí ọkọ̀ iwájú rẹ àtipé ò ń wakọ̀ ní àìléwu.

Nígbà tí o bá ń tẹ̀lé ọkọ̀ tí ó ń dúró lóòrèkóòrè (ọkọ̀ akérò, ọkọ̀ ọlọ́jà), o gbọ́dọ̀ fi kún ìtakété sí ara ọkọ̀ rẹ àti ọkọ̀ iwájú rẹ sí ìṣẹ́jú ààyá mẹ́rin tàbí márùn-ún, tàbí jù bẹ́ẹ̀ bí ó bá nílò rẹ̀.

## E. Dídúró Títakété sí Ara-ẹni

Iye àsìkò tó gbà láti dá ọkọ̀ rẹ dúró ṣe pàtàkí láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún yíyan eré sísá àìléwu. Ìdúró ìtakétésára ẹni rẹ máa dá lórí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ohun, lára wọn ni:

- Oye àsìkò tí ó gbà ẹ́ láti ri pé ìsòro wà.
- Ẹ̀yà àti ipò ojú ọ̀nà náà.
- Ipò tí táyà ọkọ̀ rẹ wà.
- Ipò ìjánu ọkọ̀ rẹ.

## F. Wíwakọ̀ Lórí Ìlà

O gbọ́dọ̀ wa ọkọ̀ rẹ lórí ìlà kan. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ pààrọ̀ ìlà títí di ìgbà tí o máa ri pé kò sí ewu nínú pípààrọ̀ bẹ́ẹ̀. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ sáré kiri ìlà tàbí kí o pààrọ̀ ìlà níí oríta.



**Ojúṣe rẹ ni láti darí ọkọ̀ rẹ ki ó má bàá ní ìjànbá.**

Níí ti bí ó ti yẹ kí ó rí , o yẹ kí o gbé ọkọ̀ rẹ sí apá ọ̀tún òpópónà, àyàfi:

- Ò ń kọjá ọkọ̀ mìíràn tí ẹ jọ ń lọ ní ọ̀nà kan náà,
- Àmì òpópónà kan tàbí ìtọ́ni kan wà tí ó ń sọ pé ó dára láti ṣe bẹ́ẹ̀, tàbí
- Ohun kan wà ní ọ̀nà tí ó mú kí ó ṣe pàtàkì fún ẹ láti pààrọ̀ ààyè láìsí ewu.

## G. Yíyípadà

Nígbà tí ìwọ bá ńyípadà, o gbọ́dọ̀:

- Wá àmì àti atọ́na tí ó ńibi tí o ti lè yípadà.
- Ṣe ètò yíyípadà rẹ kí o tó dé ibi ìyípadà rẹ
- Tan àmì ìyípadà rẹ kí o tó de ibi ìyípadà rẹ kí àwọn awakọ̀ mìíràn lè mọ ohun tí o fẹ́ ṣe.
- Wo iwájú, ẹ̀yìn àti ẹ̀gbẹ́ méjèjì láti ri dájú pé kò sí ewu nínú yíyípadà rẹ.
- Ṣe àtúnṣe eré sísá rẹ fún ìyípadà yìí.

## H. Àyípadà-U

Àyípadà-U lè burú gidi àti pé kò sí ibi tí òfin ti fi àyè gbà á. Bí ó bá jẹ́ pé dandan ni pé o gbọ́dọ̀ ṣe àyípadà-U, kọ́kọ́ wo àyíká láti mọ̀ bóyá wọ́n fi àyè gba àyípadà-U níbẹ̀. Bí wọ́n bá gbà, tan àmì òsì ọkọ̀ rẹ kí o sì dúró fún ọkọ̀ tí ó ń bọ̀ sí ọ̀nà ọ̀dọ̀ rẹ. Nígbà tí ọ̀nà bá ti mọ́, yípadà sí ọwọ́ ìta tàbí sí ìlà apá ọ̀tún ní òpópónà tí ó kọ́gun sí ẹ.

## I. Kíkọjá

Nígbà tí a bá fi àyè gbà ẹ́ láti kọ́já ọkọ̀ mìíràn, o gbọ́dọ̀:

- Ro oye àkókò àti àyè tí o máa nílò lati kọ́já àtipé kí o sì ri dájú pé o kójá láìdí ọkọ̀ Kankan lọ́wọ́
- Lo àmì àyípadà rẹ kí o tó yípadà kí àwọn awakọ̀ mìíràn lè mọ ohun tí o fẹ́ ṣe.

- Fi àyè púpọ̀ sílẹ̀ kí o sì kọ́já àwọn ọkọ̀ mìíràn pẹ̀lú àyè tí kò léwu nínú.
- Rí iná méjèèjì ọkọ̀ tí o kọjá pelu jigi àwo-ẹ̀yin re kí o tó padà sí ojú ìlà tí o ti jáde.

Ní ti bí ó ti yẹ kí ó rí, ẹ̀gbẹ́ òsì ọkọ̀ mìíràn ni ó yẹ kí o gbà kọjá. Àmọ́ ṣá, kò burú bí o bá gbà ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún ọkọ̀ mìíràn kọjá bí kò bà sí ewu nínú rẹ̀, kí o dúró sí ojú ọ̀nà àti:

- Ọkọ̀ mìíràn fẹ́ yípadà ní ẹ̀gbẹ́ òsì.
- O wà ní ọ̀nà tí wọ́n ko dí iwájú rẹ̀ níbí tí ìlà méjì tàbí jùbẹ́ẹ̀ lọ kọjú sí ibìkan náà. Ọ̀nà tí wọn kò dí iwájú rẹ̀ túmọ̀sí pé kò sí igi, àwọn àmì tàbí àwọn ohun mìíràn lójú ọ̀nà.
- O wà ní ojú ọ̀nà tí a kò dí iwájú rẹ̀ ní ojú pẹ̀lú ìlà méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ níbẹ̀.

Nígbà tí ọkọ̀ mìíràn bá fẹ́ kọjá rẹ, o gbọ́dọ̀ fi àyè gbàà àtipé o kò gbọ́dọ̀ fi kún eré sísá rẹ.

O lè máà kọjá:

- Nígbà tí o bá wà níbi àyè tí a kò gbọ́dọ̀ kọjá.
- Nígbà tí ìlà yẹ́lò ńlá ojú ọ̀nà wà ní ẹ̀gbẹ́ ọ̀dọ̀ rẹ.
- Nígbà tí ìlà yẹ́lò ńlá pé méjì.
- Nígbà tí kíkọjá bá máa dí àlàáfíà àwọn ọkọ̀ mìíràn lọ́wọ́.
- Nígbà tí o bá fẹ́ dé orí òkè kan tàbí ibi ìyànà tí o sì fẹ́ kò lè rí iwájú dáradára.
- Nígbà tí nǹkankan dí ìríran rẹ lọ́wọ́ bí o ti dé ìwọn ẹsẹ̀ 100 sí orí afárá, ọ̀nà tí ó gbé sókè tàbí kòtò.
- Nígbà tí o bá ń kọjá tàbí láàárín ìwọn ẹsẹ̀ 100 níbí ikòrítà tàbi ibi tí ọ̀nà ojú-irin ti sọdá.
- Ní èjìká ojú ọ̀nà yálà sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún tàbí sí ẹ̀gbẹ́ òsì.

## J. Àwọn Òfin Ìgúnlẹ̀ Gbogboògbò

Ojúṣe rẹ ni láti ri dájú pé ọkọ̀ kìíṣe ohun burúkú nígbà tí o bá wà á gúnlẹ̀. Èyí túmọ̀sí pé kò fa ewu Kankan fún ẹnìkankan. O gbọ́dọ̀ ní gbogbo ìgbà:

- Wa ọkọ̀ rẹ gúnlẹ̀ ní ibi tí ó hàn gbangba pé nítorí ìgúnlẹ̀ ọkọ̀ ni a ṣe pèsè rẹ̀.
- Nígbà tí o bá ń wa ọkọ̀ rẹ gúnlẹ̀ sí ojú ọ̀nà, jẹ́ kí ọkọ̀ rẹ jìnnà sí ibí ìdíwọ́ ìrìnnà. Bí ibi ìdídúró kan bá wà, wa ọkọ̀ rẹ gúnlẹ̀ sún mọ́ ibẹ̀.
- Ṣe àtò ìjánu ọkọ̀ rẹ nígbà tí o bá wa ọkọ̀ rẹ gúnlẹ̀



- Bí ọkọ̀ rẹ bá jẹ́ mánúà, fi sí jíà nígbà tí o bá wà á gúnlẹ̀ tàbí fi sí 'gúnlẹ̀' bí ó bá ọtọmátíìkì.
- Wo àyègbè rẹ ati lílóbíbọ̀ ọkọ̀ kí o tó ṣí ilẹ̀kùn rẹ. Yará ti ilẹ̀kùn ní kété tí o bá jáde.
- Mú kọ́kọ́rọ́ ọkọ̀ rẹ dání pẹ̀lú rẹ. Ìwà tí ó dára ni láti ti ilẹ̀kùn ọkọ̀ rẹ nígbà tí o bá jáde nínú rẹ.



**Ní àwọn agbègbè tí o bá ti rí 'dúró sí ọ̀tún', wa ọkọ̀ rẹ lọ sí ìlà tàbí àwọn ìlà apá ọ̀tún, àyàfi tí o bá ń kọjá ọkọ̀.**

# ÌPÍN 4: ÀWỌN AMÌ, ATỌ́KA ÀTI ÀLÀ PÈPÉ

Gbogbo èniyàn ni ó gbọ́dọ̀ tẹ̀lé òfin ìdárí ètò ìrìnnà òfin. Ìdárí ètò ìrìnna ni awọn àmì, atọ́ka àti àlà pèpé (àwọn ìlà ojú ọ̀nà) tí ó ń dárí, kìlọ̀ tàbí tukọ̀ ètò ìrìnnà. Kíkùnà láti tẹ̀lé òfin ìdárí ètò ìrìnnà ni kókó ohun tí ó ń fa ìjànbá lójú pópó .

Ìgbà kan ṣoṣo tí ìwọ kò nílò láti tẹ̀lé òfin ìdárí ètò ìrìnnà ni àsìkò tí èyíkéyìí nínú àwọn wọ̀nyí bá sọ fún ẹ kí o ṣe ohun tí ó yàtọ̀:

- Ọlọ́pàá tàbí àwọn òṣìṣẹ́ elétò pàjáwìrì mìíràn.
- Adarí ìfònà ilé-ìwé tí ó wọṣọ tí ó ń darí ètò ìrìnnà nítòsí ilé-ìwé.


Àwọn òfin ètò ìrìnnà tí o gbọ́dọ̀ tẹ̀lé.

Nígbà tí atọ́nà ètò ìrìnnà kò bá ṣiṣẹ́:

- O gbọ́dọ̀ dúró ni ibi tí wọ́n fàlà sí tí ó hàn kedere. Ìlà Ìdánidúró ni ìlà funfun fífẹ̀ tí a kùn sí àárín títì ti ó ń tọ́ka ibi tí o ti gbọ́dọ̀ dúró tí o to de ibi ọ̀nà ti pàdé.
- Tí kò bá sí ibi tí wọ́n fàlà sí tí ó hàn kedere, o gbọ́dọ̀ dúró kí o tó dé ibi ìlà àárín títì.
- Tí kò bá sí ibi tí wọ́n fàlà sí tí ó hàn kedere tàbí ìlà àárín títi, o gbọ́dọ̀ dúró kí o tó dé ibi ọ̀nà ti pàde.
- O gbọ́dọ̀ dúró fún àwọn ọkọ̀ àti àwọn ẹlẹ́sẹ̀ ní ibi ọ̀nà ti pàde, kí o sì dúró títí di ìgbà tí kò sí ewu láti tẹ̀síwájú sínú ibi tí ọ̀nà ti pàdé.

## A. Atọ́ka ètò ìrìnnà

### *Atọ́nà ọkọ̀*




**1. Atọ́nà pupa tí ó dúró jẹ́**

Dúró pátápátá ní ibi ìlà ìdánidúró. Tí kò bá sí ibi`là ìdánidúro, dúró kí o tó dé ìlà àárín títi, atí kí o tó dé ibi ọ̀nà ti o pàde. Dúró síbẹ̀ níwọ̀ngbà tí atónà náà bá ṣì yọ pupa.

Àyàfi bí àmì kan bá dá títan pupa dúró, lẹ́yìn ti o bá dúró pátápátá, o lè:


- Yà sí ọ̀tún, tàbí
- Yà sí òsì láti ọ̀nà àdúgbò olóòpópónà kan sí ọ̀nà àdúgbò olóòpópónà mìíràn.

Nígbà tí ó bá ń tan pupa, o gbọ́dọ̀ fi àyè sílẹ̀ fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀ àti àwọn elétò ìrìnnà mìíràn.




**2. Atọ́nà Yẹ́lò tí ó Dúró jẹ́**

Èyí túmọ̀sí pé atọ́nà náà fẹ́ yí padà láti aláwọ̀ sí pupa. Ó ń fún ẹ ní àǹfàní láti dúró ní àìléwu. Ó tún ń fi àǹfàní fún ọkọ̀ tí ó wà láàárín ibi tí ọ̀nà ti pàdé láti kọjá rẹ̀ kí atọ́nà náà tó yí sí pupa. Bí o bá ti súnmọ́ ibi tí ọ̀nà ti pàdé jù láti dúró láìsí ewu, fi sùúrù là ibi tí ọ̀nà ti pàdé  náà já.



**3. Atọ́nà Aláwọ̀-ewé tí ó Dúró jẹ́**


Tẹ̀síwájú pẹ̀lú ìṣọra lẹ́yìn tí o bá ti kọ́kọ́ ṣe àyẹ̀wò tí o sì ri pé kò sí ọkọ̀ mìíràn ní ibi tí ọ̀nà ti pàdé náà. Ẹyí túmọ̀sí pé o gbọ́dọ̀ ṣọra kí o sì fi ara balẹ̀. Nígbà tí kò bá sí ewu láti tẹ̀síwájú, o lè wọ ibi tí ọ̀nà ti pàdé láti lọ tààrà tàbí yípadà àyàfi bí àmì atọ́nà kan tako ìyípadà náà. O gbọ́dọ̀ fi àyè gba ẹlẹ́sẹ̀ tàbí ọkọ̀ mìíràn tí ó ti wà ní ibi tí ọ̀nà ti pàdé.



**4. Árò Atọ́nà Pupa tí ó Dúró je**


Bí o bá fẹ́ lọ sí ọ̀nà ibi tí árò kọjú sí, dúró pátápátá kí o tó dé ibi ìlà ìdádúró, ibi ìlà ààrín títì tàbí ibi tí ọ̀nà ti pàdé. Dúró síbẹ̀ níwọ̀ngbà tí árò atónà náà bá ṣì yọ pupa.

**5. Árò Atọ́nà Yẹ́lò tí ó Dúró jẹ́**




Ẹyí túmọ̀sí pé àyè láti lọ sí apá ibi árò ń parí. Kí o tẹ̀ẹ jẹ́jẹ́ kí o sì tẹ̀síwájú pẹ̀lú sùúrù.

**6. Árò Atọ́nà Aláwọ̀-ewé tí ó Dúró jẹ́**




Tẹ̀síwájú pẹ̀lú sùúrù lọ sí ibi tí árò kọjú sí. Rántí pe o gbọ́dọ̀ fi àyè gba ẹlẹ́sẹ̀ tàbí ọkọ̀ mìíràn tí ó ti wà ní ibi tí ọ̀nà ti pàdé.

**7. Atọ́nà Pupa tí ó ń Ṣẹ́jú**




Dúró pátápátá ní ibi ìlà ìdánidúró. Tí kò bá sí ibi`là ìdánidúro, dúró kí o tó dé ìlà ààrín títi, atí kí o tó dé ibi ọ̀nà ti o pàde. Fi àyè gba gbogbo àwọn ètò ìrìnnà mìíràn àti ẹlẹ́sẹ̀. O lè tẹ̀síwájú nígbà tí àmì iná pupa tó ń mì bá dúró tí ọ̀nà sí.

Bí atọ́nà Pupa tí ó ń ṣẹ́jú bá wà ní ibi ọ̀nà ti ojú-irin ti kọjá, o gbọ́dọ̀ dúró pátápátá, bí ìwọ kò tilẹ̀ rí ọkọ̀ ojú irin kan tí ó ń bọ̀. Tẹ̀síwájú nígbà tí ọ̀nà bá mọ́.



**8. Atọ́nà Yẹ́lò tí ó ń Ṣẹ́jú Atọ́nà Yẹ́lò tí ó ń Ṣẹ́jú**

Kí o tẹ̀ẹ jẹ́jẹ́ kí o sì tẹ̀síwájú pẹ̀lú sùúrù.




**9. Árò Atọ́nà Pupa tí ó ń Ṣẹ́jú**

Dúró pátápátá kí o tó dé ibi ìlà ìdánidúró, ìlà ojú títì tàbi ibi tí ọna ti pàdé. Fi àyè gba gbogbo àwọn ètò ìrìnnà mìíràn àti ẹlẹ́sẹ̀. Tẹ̀síwájú sí ọ̀nà árò náà bí ọ̀nà náà bá mọ́.


**10. Àwọn Atọ́nà Lílò Ìlà**







Ní àwọn ọ̀nà kan, ètò ìrìnnà lè lọ ní ọ̀nà kan ní ààrín àwọn wákàtí okán, àti ọ̀nà kéjì ní wákàtí mìíràn. Ẹyí dá lórí bi ètò ìrìnnà ṣe pọ̀ sí ní àkókò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ láààrín ọjọ́. Àwọn wọ̀nyín ni à ń pè ní àwọn ìlà tí a lè yípadà. Àwọn Atọ́nà Lílò Ìlà máa ń sọ ibi tí ó yẹ kí o yà sí. A lè fi àwọn àmì, àtọ́nà àti ìlà fífà sààmì sí àwọn ìlà àti ibi tí wọ́n dojúkọ.



Ìwọ kò gbọ́dọ̀ wa ọkọ̀ ní abẹ́ atọ́nà ìlà 'X' pupa.




O lè wa ọkọ̀ nínú ìlà abẹ́ árò atọ́ni aláwọ̀-ewé.

Atọ́nà "X" yẹ́lò tí ó dúró jẹ́ túmọ̀sí pé kí o jáde nínú ìlà ní kíákíá.

Atọ́nà "X" yẹ́lò tí o ń ṣẹ́jú tàbí árò ìyípadà ọlọ́nà méjì túmọ̀sí pé o lè lo ọ̀nà náà láti yà sí apá òsì. Ó ṣeéṣe kí o máa ṣe àjọpín ìlà náà pẹ̀lú àwọn ọkọ̀ tó ó fẹ́ yà sí apá òsì láti òdìkéjì.






## *Atọ́ka Rírìnsọdá*

Atọ́ka Rírìnsọdá máa ń dá ohun ìrìnnà dúró kí àwọn ẹlẹ́sẹ̀ lè sọdá. Àwọn ẹlẹ́sẹ̀ lè lo atọ́nà yĩĩ nípa títẹ ara òpó ní ẹ̀gbẹ́ ọ̀nà. Ó máa sọ fún awakọ̀ láti dúró àti fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀ láti sọdá. Àwọn ti ìsàlẹ̀ yĩĩ ni àwọn ẹlẹ́sẹ̀ àti awakọ̀ máa rí.

### Àwọn ẹlẹ́se:

| Wo Eléyĩĩ | Ṣe Eléyĩĩ |
|---|---|
|  | Dúró. Tẹ bọ́tìn láti kọjá. |
|  | Dúró! |
|  | Tẹ̀síwájú láti dúró. |
|  | Wo ẹ̀gbẹ́ méjèèjì. Bẹ̀rẹ̀ sí ń sọdá nígbà tí ọkọ̀ bá ti dúró. |
|  | Má tĩì bẹ̀rẹ̀. Parí sísọdá bí o bá ti bẹ̀rẹ̀. |
|  | Dúró. Ọkọ̀ ti bẹ̀rẹ̀ sí ń lọ. |

### Àwọn Awakọ̀:

| Wo Eléyĩĩ | Ṣe Eléyĩĩ |
|---|---|
|  | Lọ. |
|  | Yẹ́lò tí ó ń ṣẹ́jú. Tẹ̀ẹ́ jẹ́jẹ́. |
|  | Yẹ́lò tó ki. Múra láti dúró. |
|  | Pupa tó ki. Dúro! |
|  | Pupa tí ó ń ṣẹ́jú. Dúró. Tẹ̀síwájú pẹ̀lú sùúrù. |
|  | Tẹ̀síwájú pẹ̀lú sùúrù. |

# B. Àwọn Amì Ètò Ìrìnnà

## *Àwọn Àwọ̀*

Àwọn àmì ètò ìrìnnà ń lo àwọn àmì àti ọ̀rọ̀ láti ṣàlàyé. Ó yẹ kí o lè ṣe ìdámọ̀ àwọn àmì ètò ìrìnnà nípa ìrísí wọn àti àwọ̀, àti àwọn ọ̀rọ̀, nọ́ńbà, tàbí àmì tí ó wà lára wọn. Ògidì àwọ̀ àmì ètò ìrìnnà kan lè sọ fún ẹ ní kíákíá irú àlàyé tí ó ní.

**Pupa -** Dúró, fàyè gbà á, má ṣe wọlé, tàbí ọ̀nà èbùrú.

**Yẹ́lò -** Ìkìlọ̀ gbogboògbò lórí ohun tí ò ń retí níwájú.

**Funfun -** Gbèdéke eré sísá, yà sí ọ̀tún, àti àwọn àmì mìíràn.

**Aláwọ̀ Ọsàn -** ìkìlọ̀ lórí agbègbè iṣẹ́ tàbí àtúnṣe iṣẹ́.

**Aláwọ̀ Ewé -** Èbúté, àlàfo àti àwọn àpèjúwe ọ̀nà.

**Aláwọ̀ Búlúù -** Àwọn àmì fún iṣẹ́ bíi oúnjẹ, gáàsì àti ibi ìsimi.

**Aláwọ̀ Búráǹ -** Ibi ìgbafẹ́ àti ibi àṣà tí a ní ìfẹ́ sí.

**Fúlọ́rísẹ́ǹtì Yẹ́lò- Aláwọ̀ Ewé -** Àwọn àmì Ilé-ìwé, ẹlẹ́sẹ̀, àti kẹ̀kẹ́.

**Fúlọ́rísẹ́ǹtì Píǹkì -** Ìṣẹ̀lẹ̀ ètò pàjáwìrì ètò ìrìnnà.

**Dúdú -** Àwọn ọ̀nà àmì Olójú kan àti àwọn àmì tí ó ń yí àtẹ̀ránṣẹ́ padà.

**Octagon: Dúro**

Octagon náà (onígun mẹ́jọ) máa ń túmọ̀sí dúró. O gbọ́dọ̀ dúró pátápátá.

**Triangle: Yíìdì**

Tẹ̀ẹ́ jẹ́jẹ́, àtipé bí ó bá ṣe pàtàkì dúró láti fi àyè fún àwọn ọkọ̀ àti àwọn ẹlẹ́sẹ̀.

**Dáyámọ́ǹdì: Ìkìlọ̀**

Àwọn àmì wọ̀nyí ń kìlọ̀ fún ẹ lórí àwọn ohun ọ̀tọ̀ àti ewu tí ó wà níwájú. O lè nílò láti tẹ̀ẹ́ jẹ́jẹ́, ní ìdí èyí múra sílẹ̀ láti ṣe ohun tí ó yẹ.

**Pẹ́náǹtì: Ko si Kíkọjá**

Sàmì sí ibi kò sí àyè láti kọjá. Má ṣe kọjá ọkọ̀ mìíràn.

**Rectangle: Ìlànà tàbí Ìtóni**

Àwọn ìlà dídúró máa ń sábà ṣàlàyé tàbí sọ àwọn òfin ìrìnnà fún ẹ. Àwọn ìlà sísùn máa ń sábà ṣàpèjúwe tàbí ṣàlàyé.

**Pentagon: Agbègbè Ilé-ìwé tàbí Sísọdá Ilé-ìwé**

Pentagon náà (onígun márùn-ún) máa ń kìlọ̀ fún ẹ lórí agbègbè ilé-ìwé àtipé kí ó sàmì si Sísọdá Ilé-ìwé níbi tí àwọn ọmọ ilé-ìwé ti ń sọdá ọ̀nà.

**Róbótó: Ìkìlọ̀ ònà Ojú-irin**

Ó máa ń kìlọ̀ pé ọ̀nà ojú irin wà níwájú.

**Àgbélébú Wíwọ̀: Òpópónà – Sísọdá Ọkọ̀ Ojú irin**

Máa ń tọ́ka ibi tí ọ̀nà ojú-irin ti sọdá.

**Trapezoid**

Ibi ìgbafẹ́ àti ohun àṣà tí ó wu ni àti ọ̀nà sí inú igbó ìjọba.

## Àwọn Àmì Ìdarí

Àwọn àmì yìí dá lórí òfin ìrìnnà. O gbọ́dọ̀ pa wọ́n mọ́.




1. **Àmì onígun-8, Lẹ́tà funfun lórí Pupa**

   Àmì ìdádúró náà ni àmì onígun-8 tí o rí ní ojú ọ̀nà. Nígbà tí o bá dé ibi àmì ìdánídúró:

   - O gbọ́dọ̀ dúró pátápátá ní ibi ìlà ìdánidúró.
   - Tí kò bá sí ila ìdánídúro, o gbọ́dọ̀ dúró kí o tó dé ibi ìlà ààrín títì.
   - Tí kò bá sí ibi`là ìdánidúro tabi ibi ìlà ààrín títi, dúró kí o tó dé ibi tí ọ̀nà ti pàdé.

   O gbọ́dọ̀ dúró fún àwọn ọkọ̀ àti àwọn ẹlẹ́sẹ̀ ní ibi ti ọ̀nà ti pàde, kí o sì dúró títí di ìgbà tí kò sí ewu láti tẹ̀síwájú sínú ibi tí ọ̀nà ti pàdé.




2. **Àmì onígun-3, Lẹ́tà funfun lórí Pupa**

   Àmì yíìdì nìkan ni àmì tí ó rí báyìí. Tẹ́ẹ́ jẹ́jẹ́ bí o ti ń dé ibi àmì yíìdì. Wo ọ̀tún kí o sì wo òsì. Fi àyè sílẹ̀ fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀, kẹ̀kẹ́ àti ọkọ̀. Nígbà tí o bá ti fi àyè sílẹ̀ fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀, kẹ̀kẹ́ àti ọkọ̀, o lè tẹ̀síwájú nígbà tí o bá lè ṣe èyí láìsí ewu.




3. **Àmì Rectangular (Onígun 4), Dúdú lórí Funfun**

   Àwọn àmì wọ̀nyí ń tukọ̀ ètò ìrìnnà. Àmì yìí ń sọ fún ẹ eré sísá tí ó pọ̀jù ni apá ọ̀nà náà ní ibi tí wọ́n lẹ̀ẹ́ mọ́.



Kò sí yíyà sí ọ̀tún



Kò sí yíyà sí Òsì



Kò sí Àyípadà-U




Kò sí Àyípada




Yíyà sí Òsì nìkan




Ìwọ kò Gbọ́dọ̀ Wọlé



Kò sí ìwà gúnlẹ̀




Kò sí yíyà sí Pupa




Ìwọ kò Gbọ́dọ̀ Koja



Dúró sí ọ̀tún ààrín gbùgùn




Yíyà sí Òsì yíìdì lórí Aláwọ̀ Ewé




Ọ̀nà Ọ̀kadà




Ọ̀nà Èbùrú




Ìfi-pamọ̀ fún àwọn Àkàndá ènìyàn láti wà gúnlẹ̀




Ọ̀nà Méjì sí Òsì

Àwọn ọkọ̀ tí ó rin ìrìn-àjò nínú ìrìn ọ̀nà méjèèjì lè lo ààrín láti yà sí òsì




Ọ̀pọ́pọ́nà ọlọ́nàkan lè lọ ní ọ̀nà árò nìkan




Àwọn Ọkọ̀ Eléro Púpọ̀

O lè lo ojú ìlà yìí, ìyẹn nígbà tí o bá ní oye èrò tí wọ́n tọ́ka nínú àmì yìí

## Àwọn Àmì Ìkìlọ̀

Àwọn àmì yìí ń sọ fún awakọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń bọ̀ níwájú.


Dúró Níwájú


Yíìdì Níwájú


Atọ́nà Níwájú


Yíyà sí ọ̀tún tó mọ́


Àwọn Ẹlẹ́sẹ̀ ń sọdá


Róbótó Ìrìnnà (tí wọ́n tún ń pè ní oríta ńlá)



Eré Sísá tí ó Pọ̀jù



Ọ̀nà àbájáde fún Eré Sísá tí ó pọ̀jù



Ibùdó Ko si Kíkọjá


Àwọn ọ́nà Méjì Papọ̀


Ọ̀nà Pín Níwájú


Ọ̀nà Tó Pín Níwájú pari


Ọ̀nà Yà


Ṣáàpù Yà


Ọ̀nà Yà



Ọ̀nà ẹ̀gbẹ́ wọlé níwájú



Ìgbẹ̀yìn Àwọn Ọ̀nà Papọ̀ Níwájú


Ibi tí Ọ̀nà ti Papọ̀


Ibi tí Ọ̀nà ti Papọ̀ "T" Níwájú


Ọ̀nà Ojú-Irin kí Ọ̀nà "T" to Papọ̀


Òkè Pẹ́rẹ́sẹ́


Ó Yọ̀ Nígbà tí ó Tutu


Ọ̀nà Parí



Ọkọ̀ Àjàgbé ń sọdá



Ọkọ̀ Ojú-Irin ń sọda


Ẹlẹ́sẹ̀ àti Kẹ̀kẹ́ ń sọdá


Àgbọ̀nrín tàbí ẹranko ìgbẹ́ míràn ń ré kọjá


Àṣíyá wà Níwájú



Iṣẹ́ Ọ̀nà wà Níwájú



Ọ̀nà Àbùjá



Àwọn Ọmọ Ilé-ìwé ń sọjá Níwáju


Ọkọ̀ Ilé-ìwé Dúró Níwájú



Bẹrẹ Agbegbe Iṣẹ



Pari Agbegbe Ojú ìṣe



Agbegbe Iṣẹ Nṣiṣẹ Nigbati Imọlẹ nkọ-mọna (Awọn ijiya pọ si)

### Ọ̀nà Orí-Òkè tí wọ́n ń lò

Ìwọ̀n máa rí àwọn àmì yìí níwájú ọ̀nà. Wọ́n ṣe àlàyé lórí àwọn èbúté, itosọ̀nà àti bí wọ́n ṣe ń lo àwọn ọ̀nà náà.




### Àwọn Àmì Atọ́ka Ọ̀nà

Wọ́n nọ́ńbà àwọn ọ̀nà kan. Wọ́n ń pè wọ́n ní Àwọn Atọ́ka Ọ̀nà. Àwọn àmì yìí máa ń ṣe ìdámọ̀ fún nọ́ńbà àwọn ọ̀nà kan àti irúfẹ́ ọ̀nà náà.



Ìpínlẹ̀ sí Ìpínlẹ̀



Ọ̀nà U.S.



Ọ̀nà Ìpínlẹ̀

### Àlàyé Iṣẹ́ àti Àwọn Àmì Atọ́ka

Àwọn àmì yìí máa ń tọ́ka irú òwò àti iṣẹ́ tí o lè rí tí o bá gba ibìkan jáde.




Gúnlẹ̀ kí o sì gùn-ún



Atọ́ka Èbúté



Àwọn àmì Iṣẹ́ Gbògbòògbò



Gbígba ilé | Ilé ìwòsàn | Gáàsì | Oúnjẹ | Ibùdókò Òfúrufú | Ibùdókò Ojú Irin

### Àwọn Àmì Atọ́ka Máìlì


Àwọn wọ̀nyí wà ní gbogbo Máìlì ní ojú ọ̀nà Ìpínlẹ̀ sí ìpínlẹ̀. Wọ́n ń tọ́ka àlàyé ibi tí o lè lò nígbà tí o bá nílò ẹ̀nìkan láti wá ẹ. Fún àpẹrẹ, ọkọ̀ awọ̀kọ̀ tàbí òṣìṣẹ́ pàjáwìrí.



# C. Àwọn Àlà pèpé


## *Àwọn Oríṣi Sísàmì sí Ìlà*

Àwọn Àlà pèpé jẹ́ ìlà lójú ọ̀nà. Wọ́n ń pèsè àlàyé tí ó ṣe pàtàkì àti àlàyé láìretí kí o gbójú kúrò lójú ọ̀nà. Ó yẹ kí o dá gbogbo àlà pèpé yìí mọ̀ kí o sì ní òye itúmọ̀ wọn. Àwọn ìlà kan lè tóbi púpọ̀ ní àwọn ibìkan àti/tàbí tí wọ́n ní àwò-ojíìjí tí wọ́n lè mọ láti pè àkíyèsí rẹ kí o sì lè rí àwọn ìlà náà.




### Àgékù Ẹyọ Kan Ṣoṣo - Funfun

Ìlà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ibi tí ètò ìrìnnà ti kọjú sí ibìkan, àtipé písọdá láti ìlà kan sí ìkéjì ni a fi àyè gbà. Tí wọ́n ń lò lójú ọ̀nà pẹ̀lú ìlà méjì.




### Àgékù Ẹyọ Kan Ṣoṣo - Yẹ́lò

Ìlà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ibi tí oko ti n rìn ní òjìkéjì ara wọn àti kíkọjá pẹ̀lú sùúrù ni àyè wà fún ní ọ̀nà méjéèjì. Tí wọ́n ń lò ní ààrín ìlà 2, ọ̀nà onílà 2.




### Ẹyọ Kan Ṣoṣo - Funfun

Sísàmì sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún ọ̀nà. Àti ìlà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ibi tí gbogbo ọkọ̀ ń lọ ní ọ̀nà kan ṣoṣo, ṣùgbọ́n kò sí àyè fún pípàrọ̀ ìlà.




### Ẹyọ Kan Ṣoṣo - Yẹ́lò

Sísàmì sí ẹ̀gbẹ́ osi, lójú pópónà tí a pín, òpópónà ọlọ́nà kan. Òpópónà tí a pín sí mẹ́rin, tí kò sí ilẹ̀ tàbí ìdíwọ́ mìíràn lááárín ìrìn-àjò òpópónà ọlọ́nà kan.





### Àgékù (ẹ̀gbẹ́ si ẹ̀gbẹ́) Ọlọ́nà Méjì - Yẹ́lò

Sísàmì sí ẹ̀gbẹ́ ìlà àyípadà – ìlà níbi tí ìrìn-àjò ti kọjú sí ọ̀nà kan nígbà mìíràn àti ní ọ̀nà mìíràn nígbà mìíràn. O lè wọlé kí o sì jáde látàrí ohun tí àmì àtọ́nà tí a fi àyè gbà'.




### Àgékù (ẹ̀gbẹ́ sí ẹ̀gbẹ́) Ọlọ́nà Méjì - Funfun

Ìlà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ níbi tí ètò ìrìnnà ti ń lọ ní ọ̀nà kan àtipé ìwọ kò lè pààrọ̀ ìlà. A tún lè lò ó láti pa àlà ààrín ìlà àti ìlà HOV. A tún lè lò ó ṣíwájú ìdíwó ti o lè gbà kọjá ní eyiòwú ọ̀nà méjèèjì.



### Àgékù (ẹ̀gbẹ́ sí ẹ̀gbẹ́) Ọlọ́nà Méjì - Yẹ́lò

Ìlà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní ibi tí oko ti n rìn ní òdìkéjì ara wọn àtipè kò sí àyè kíkọjá pẹ̀lú sùúrù fún ikankan ninu ọ̀nà méjéèjì. O lè yà sí ẹ̀gbẹ́ òsì forí ìlà yẹ́lò ọlọ́nà méjì. Bí àpẹrẹ, nígbà tí o bá ń yà sí òpópónà.




### Líle àti Àgékù - Yẹ́lò

Tí à ń lò ní ọ̀nà olóòpópónà méjì níbi tí àyè ti wà láti kọ́ja ní ọ̀nà kan ṣoṣo. Kíkọjá pẹ̀lú Ìṣọ́rá ni:

- Tí a gbà láyè fún ìrìnnà ní ibi àgékù ìlà.
- Tí a ko gbà láyè fún ìrìnnà ní ibi ọ̀na lilè.

A tún lè lò ó láti sàmì sí ìlà méjì ẹlẹ́gbẹ́ òsì – ìlà líle wà ní ẹ̀gbé ìta nígbà tí ìlà gígé wà ní ìnu.



### Onílà kan – Yẹ́lò tàbí Funfun

Àwọn Ìlà lọ títí dé oríta. Àwọn Awakọ̀ ibi tí ọ̀nà ti pàdé gbọ́dọ̀ dúró sí inu ìlà.

## *Àwọn Àlà pèpé miiran*

Àwọn Àlà pèpé miiran ṣe pàtàkì sí wíwa àwàyè. Ó ṣe pàtàkì láti dá wọn mọ̀ àtí láti ní òyè wọn. Lára wọn ni:

### Ìlà Ìdánidúró



Funfun, ìlà líle, tí ó sọ ibi tí ọkọ̀ ti gbọ́dọ̀ dúró fún àmì DÚRÓ tàbí atọ́nà ìrìnnà pupa.

### Ilà Yĩìdì




Triangle titò kékèké káàkiri ìlà náà tí o ṣe àfihàn ibi tí ọkọ ti gbọ́dọ̀ fi àyè fún àwọn ọkọ̀ mĩíràn tàbí ẹlẹ́sẹ̀.

### Fífi Ọ̀rọ̀ àti Àmì Sàmì

Ìsàmì tí ó ń sọ fún ẹ:

- Bí a ti ń lo ìlà.
- Nípa díndín ìlà kù (bí àpẹrẹ, ọ̀nà náà ń yí padà láti méjì sí ẹyọkan).



- Ọ̀nà tí ó yẹ kí ìrìn-àjò gbà.
- Ìsàmì tí à ń lò pẹ̀lú árò tàbí àtẹ̀ránṣẹ́ ọ̀rọ̀ mĩíràn láti ṣe àfihàn bí o ṣe máa rìn nínú ònà náà.






- Sísàmì sí ILÉ-ÌWÉ àti RxR láti kìlọ̀ fún ẹ pé ò ń súnmọ́ agbègbè ilé-ìwé àti ọ̀nà ọkọ̀ ojú irin.





## *Àlà Pèpé Ẹlẹ́sẹ̀ àti Kẹ̀kẹ́*

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ọ̀nà Maryland tí Kẹ̀kẹ́ pín pẹ̀lú ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ kò ní àmì ìrìnnà ní pàtó tàbí àlà pèpé. Àwọn ònà kan wà tí wọ́n ní àjọpín ìlà (Wo àwòrán). Inú ìlú ńlá ni wọ́n sábà wà. Àwọn Ìsàmì sí yĩ:

- Sọ fún àwọn awakọ̀ pé oní kẹ̀kẹ́ lè wà ní ọ̀nà,
- Sọ fún oníkẹ̀kẹ́ nípa ibi tí ó yẹ kí wọ́n rìn, ati
- Láti tako kẹ̀kẹ́-alúpúpú wíwa ní ibi tí kò tọ́.

Àwọn ọ̀nà ní àmì pèpé tí ó ṣàfihàn ìlà tí ó wà fún kẹ̀kẹ́. Ìlà funfun líle tàbí gígé pààlà sáàárín ọ̀nà kẹ̀kẹ́ àti ọ̀nà ọkọ̀. O lè rí ilà kẹ̀kẹ́-alúpúpú tí wọ́n fi àmì ọ̀kada sàmì sí tàbí pẹ̀lú àmì kẹ̀kẹ́ àti árò.








Níbi tí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìgúnlẹ̀ ti ṣe ìtẹ́wọ́gbà, àwọn ìlà tí ó jọra lè pààlà sí àáárín ìlà kẹ̀kẹ́ àti ìlà ìgúnlẹ̀.

Funfun ni ìlà àwọn ẹlẹ́sẹ̀, ìlà gígún tí ó ṣe àfìhàn ibi tí àwọn ẹlẹ́sẹ̀ ti ń sọdá. Ìlà áárín títì lè ní àfikún ìlà láàárín funfun, ìlà gígún, tàbí fi rọ pò wọn.









Gẹgẹ bí ọrọ àjọ àláàbójútó ẹṣọ ìrìnnà òpópópónà, ìjàǹbá ojú ọnà pẹlú ìwọn máìlì 65 láàárín wákàtí ( mph) tàbí jù bẹẹ lọ ni:

- Jù ilọpóméjì lọ lè fa ikú ju ìjàǹbá lọ lójú ọnà pẹlú eré sísá 45 tàbí 50 mph.
- Ó fẹrẹ é tó ilọpó-márùn lè fa ikú ju ìjàǹbá lọ lójú ọnà pẹlú eré sísá 40 mph tàbí kéré jù bẹẹ lọ.

Jẹ ONÍSÙÚRÙ AWAKỌ ń rọ àwọn awakọ láti tẹlé òfin eré sísá. Bí o bá nílò eré sísá, dìrọ mọ gbígbà geemu fídío.

Lílo ìgbàdí ọkọ ni ọnà kan ṣoṣo láti díwó ikú àti ipalárá ńlá nínu ìjàǹbá ọkọ. Jẹ ONIMURÀ AWAKỌ kí o sì lo ìgbàdí ọkọ rẹ - gbogbo ìrìn-àjò, gbogbo wíwakọ, àga ìwájú tàbí àga ẹyìń. Bí ìdá 90 àwọn awakọ àti èrò ọkọ ní ó máa ń lo ìgbàdí ọkọ, àmọ àfojúsùn wa ni ìdá 100 ní ọdọọdún, ọgọọgọrùn-ún àwọn awakọ tí kò lo ìgbàdí ọkọ ní wọn ń ní ipalárá ńlá tàbí sọ ẹmí wọn nù lójú ọnà. Ọpọlọpọ ikú wọnyẹn ni wọn bá ti gbé forí bí àwọn yẹn bá di ìgbàdí wọn mọra ní àkókò ìjàǹbá náà. Ìṣẹjú ààyá mẹta ni ó gbà láti dira ṣùgbọn ó lè mú ìyàtọ ayérayé jáde.

**Fún àlàyé síwájú si, kàn sí:**
**ZeroDeathsMD.gov.**

# ÌPÍN 5: ÀWỌN ÀKÓKÒ ÌWAKỌ̀ ÀTI ÌGBÀ

## A. Wíwakọ̀ nínú Ìríran tí ó dínkù

Ìríran ni agbára rẹ láti rí gbogbo nǹkan tí ó wà ní agbègbè rẹ ní ojú ọ̀nà bí àwọn ọkọ̀ mìíràn, ẹlẹ́sẹ̀, àmì, atọ́nà ojú ọ̀nà, àti àlà pèpé. Àdínkù tàbí Ìrínran kékeré túmọ̀sí pé yió nira láti rí àwọn ohun wọ̀nyí. Oríṣiríṣi nǹkan ni ó lè fà àdínkù ìríran, àmọ́ èyí tí ó wọ́pọ̀ jù ni òkùnkùn, ìkúùkù, òjò àti yínyín.

Wíwakọ̀ nígbà tí ìríran dínkù jẹ́ ohun tí ó nira ju “bí ó ti yẹ” lọ ó sì gbà ìfarabalẹ̀ àtí ìmúrasílẹ̀ tí ó pọ̀. Nígbà tí o bá ń wakọ̀ nínú àdínkù ìríran, rántí:

- Lo àwọn ìlà etí ọ̀nà tàbí ti apá ọ̀tún ọ̀nà náà gẹ́gẹ́ bí atọ́nà.
- Àlà pèpé yẹ́lọ̀ kò gbọ́dọ̀ wà ní ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún rẹ láéláé . Wọ́n gbọ́dọ̀ wà ní apá òsì níí gbogbo ìgbà. Wọ́n máa ń fi yẹ́lọ̀ pín ìrìnnà tí wọ́n ń lọ sí ibi ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ méjì. Ó máa ń Sísàmì sí ẹ̀gbẹ́ òsì ọ̀nà.
- Àlà Pèpé máa ń Sísàmì sí ẹ̀gbẹ́ òsì ọ̀nà. Wọ́n tún ń pín òpópónà tí ó kọjú sí ọ̀nà kan.


### Igbà tí o le lo iná ìwájú rẹ

Láti mọ̀ ìgbà àti bí wọ́n ṣe ń lo iná iwájú rẹ ṣe pàtàkì sí wíwa àwàyè rẹ. Lo àwọn iná iwájú rẹ láti ran ẹ lọ́wọ̀ nìgbà tí ìríran kéré. Lílo iná iwájú rẹ tún máa ń ran ọkọ̀ tí ó ń bọ̀ níwájú rẹ láti rí ẹ.



**Rántí: Kòtò àti Afárá tí ó kún fún omi màá n dìpọ̀ ṣiwajá ojú ọ̀nà. Àtipé títì ọlódà lè tún ní yìnyín ní alẹ̀ tàbí kí ó ní àdìpọ̀ yìnyín látàrí èyí tí ó yọ̀ ní ọ̀sán.**

Àwọn òfin gbòógì fún lílo iná iwájú nìwọ̀nyí:




- Nígbà tí o bá ń wakọ̀, o gbọ́dọ̀ tan iná iwájú rẹ nígbàkúgbà tí kò bá sí iná láti rí bí ìwọn ẹsẹ̀ 1,000 síwájú oko re,
- Ní alẹ́, ìkúùkù, àti ojú-ọjọ́ oní ìjì ṣe pàtàkì láti lo àwọn iná iwájú.
- Òfin Maryland ń retí kí o tan iná iwájú rẹ nígbà ti o bá ń lo wáìpà rẹ nígbà tí ojú-ọjọ́ kò dára tó. Ojú-ọjọ́ tí kò dára tó jẹ́ ojú-ọjọ́ tí ó kù díẹ̀ káàtó tí ó lè fa àkókò ewu.

### Iná iwájú kékeré àti iná iwájú alátànmọ́lẹ̀

Lo Iná iwájú kékeré nígbà tí:

- O bá ń wakọ̀ ní abẹ́ àkóso bí ó ti máa ń rí, bíi wíwakọ̀ ní alẹ́ lójú ọ̀nà tí ó nínà ìgboro.
- Wíwakọ̀ nínú ìkúùkù, òjò, yínyín abbl.
- Wíwọnú ibi kòtò tàbí ibi iṣẹ́. (Òfin yìí kò retí èyí ní gbogbo ìgbà, ṣùgbọ́n ó mú kí ó rọrùn fún àwọn awakọ̀ mìíràn àti àwọn òṣìṣẹ́ láti rí ẹ.)

Lo Iná iwájú alátànmọ́lẹ̀ lójú ọ̀nà tí kò ní iná ìgboro kí o lè rí àwọn ọkọ̀ mìíràn àti àwọn ènìyàn mìíràn. O gbọ́dọ̀:

- Yí padà sí iná iwájú kékeré ó kéré tán bi ìwọn ẹsẹ̀ 500 sí ọkọ̀ tí ó n bọ wà níwájú rẹ.
- Yí padà sí iná iwájú kékeré ó nígbà tí o bá ń tẹ̀lé ọkọ̀ tí kò jìnnà jù ìwọn ẹsẹ̀ 300 sí ẹ.

### B. Wíwakọ̀ ní Alẹ́

Wíwakọ̀ ní Alẹ́ ní ewu ó sì lè ju wíwakọ̀ ní ọ̀sán lọ. O nira láti mọ bí àwọn ọkọ̀ ṣe jìnnà sí àti bí wọ́n ṣe ń sáré sí. Ibi tí iná iwájú ọkọ̀ rẹ bá dé náà ni o máa rí mọ. Ewu pọ̀ ní alẹ́ náà nítori pé ìwọ ko lè ríran dáradára. Èyí mú kí ó nira láti mọ ibi tí ò ń lọ àti ohun tí àwọn mìíràn ń ṣe.

Àwọn ìmọ̀ràn láti tẹ̀lé nìyí nígbà tí o bá ń wakọ̀ lálẹ́:

- Ri dájú pé o rí iná iwájú rẹ kí o sì tẹ̀lé ìmọ̀ràn lórí àsìkò tí ó yẹ kí o lo iná iwájú alátànmọ́lẹ̀.
- Má ṣe tanná sí ojú ohun ìrìnnà tí ó ń bọ̀ níwájú rẹ. Èyí máa mú kí ó nira fún ẹ láti ríran. Dípò bẹ́ẹ̀, wo ọ̀nà tí ó wà níwájú rẹ, tàbí díẹ̀ sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀nà tí ò ń rìn (o lè wo apá ọ̀tún ìlà tàbí ẹ̀gbẹ́ títì).
- Mú kí àyè tí ó wà láàárín ìwọ àti ọkọ̀ tí ó wà níwájú rẹ gbòrò si. Èyí máa mú kí a dẹ́kun ìkọlura bí ọkọ̀ tí ó wà níwájú rẹ bá dúró kiakia.

### C. Wíwakọ̀ nínú Ìkúùkù

Àwọn àbùdá kan wà tí ó so pọ̀ mọ́ wíwakọ̀ nínú ìkúùkù tí ó fi yẹ kí o wà ní ìṣora. Àwọn tìsàlẹ̀ yìí ni àlàkalẹ̀ àti ohun tí à ń retí nígbà tí o bá ń wakọ̀ nínú ìkúùkù:

- Díwó eré sísá rẹ kù.
- Nígbà tí o bá rí iná ọkọ̀ mìíran níwájú, tún díwó eré sísá rẹ si. Ó gbọ́dọ̀ múra sílẹ̀ láti dúró kíakíá.
- Bí ìkúùkù náà bá ki dé bi pè ìwọ kò lè wakọ̀ láìséwu, ya kúrò pátápáta ní ojú ọ̀nà sí bí tí ó dára, kí o sì tan iná pàjáwìrì rẹ sílẹ̀.
- Lo iná iwájú kékeré rẹ nìkan. Kí o tún lo iná ìkúùkù bí o bá ní wọn.

### D. Wíwakọ̀ nínú Ojú-Ọjọ́ tí ó kù díẹ̀ káàtó

Ọ̀nà tí ó tutù lè máa yọ̀, kí ó má gba ọkọ̀ dúró àtípé ó tún mú kí ewu ìkọlura kí ó pọ̀ si. Ìfẹsẹ̀rinlẹ̀ ní ìbáṣepọ̀ láàárín táyà ọkọ̀ rẹ àti ojú ọ̀nà  ti ó mú kí ó ṣe é ṣe fú n ọkọ̀ rẹ láti ṣiṣé, dúro, kí ó sì yípadà. Nígbà tí o bá ní Ìfẹsẹ̀rinlẹ̀ tí ó dára, o lè dári ọkọ̀ rẹ dáradára.

Ewu máa ń pọ̀ si nígbà tí yìnyín bá bo ojú ọ̀nà. Nígbà tí o bá wakọ̀ nínú ojú ọjọ́ tí ó kù díẹ̀ káàtó, o gbọ́dọ̀ fi ara balẹ̀ kí o sì ṣetán gidi.

Nígbà tí o bá wakọ̀ nínú ojú ọjọ́ tí ó kù díẹ̀ káàtó, ó ṣe pàtàkì láti ronú ṣíwájú kí o sì gbé ìgbésẹ̀ láti wà ní àìléwu – kìí ṣe kí o kàn lórí ohun tí àwọn awakọ̀ mìíràn ṣe nìkan. Èyí máa mú kí o yàgò fún ìkọlura. Lára àwọn ohun tí o lè ṣe láti wà ní àìléwu nígbà tí o bá wakọ̀ nínú ojú ọjọ́ tí ó kù díẹ̀ káàtó nìwọ̀nyí:

- Fi àyè púpọ̀ sílẹ̀ – àyè ti o nílò láàárín ìwọ àti ọkọ̀ tí ó wà níwájú rẹ pọ̀ nígbà tí oná tutù ju ìgbà tíona gbẹ lọ. O tilẹ̀ tún nílò àyè sí nígbà tí ìkúùkù tàbí yìnyín bá gba ojú ònà.
- Dín eré sísá rẹ kù kí o lè ní àkókò láti gbé ìgbésẹ̀.
- Ri dájú pé àwọn táyà wà ní ipò tí ó dára látàrí ohun tí ilé-iṣẹ́ tí ó ṣe táyà náà wí àti alàkalẹ̀ ọkọ̀ rẹ.
- Yàgò fún títẹ ìjánu rẹ ní òjijì nítorí pé ó lè yọrí sí jíjá rẹ̀. Bí ìjánu rẹ kò bá ní ohun àbójútó ìjánu ọkọ̀, pan dáradára kí ó má bà á já.
- Yàgò fún mímí ọrùn ọkọ̀ rẹ tàbí yíyí eré sísá ní òjijì.
- Ri dájú pé wáípà rẹ ń ṣiṣẹ́ dáradára.
- Lo iná ìwájú rẹ.

## Wíwakọ̀ nínú Ìkúùkù àti Yìnyín

Kò sí ohun tí ó ń jẹ́ “kò sí ewu eré sísá pátápátá” nínú ìkúùkù àti yìnyín. Ní àsìkò wíntà, gbogbo ọ̀nà lè yàtọ̀ látàrí oorùn, ibòji, iye iyọ̀ tí ó wà ní ojú ọ̀nà, àti àwọn ohun mìíràn. Wò ṣíwájú fún ibùdó ewu. Ó lè le tàbí nira láti rí ìlà orí yìnyín lórílórí ọ̀da (asphalt) orí títì. Èyí ni à ń pè ní yìnyín dúdú nígbà mìíràn. Yìnyín àti àṣùpọ̀ yìnyín ni ó ń fa eléyìí. Ó le` fa ìkolura bí ìwọ kò bá mọ̀ nípa ewu yìí.

Àwọn ọkọ̀ ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin lè tún yọ̀ lórí yìnyín yií. Ó ṣe é ṣe kí ọkọ̀ ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin rẹ rọ̀ ẹ́ lórùn láti dári àmọ́ wíwa irú ọkọ̀ bẹ́ẹ̀ lórí yìnyín léwu bẹ́ẹ̀ni a kò lè tọ́ka rẹ. O gbọ́dọ̀ wà ní ìṣóra ní gbogbo ìgbà.

Àwọn ìmọ̀ràn nígbà tí a bá ń wakọ̀ lórí yìnyín àti ìkúùkù nìwọ̀nyí.

- Tẹ̀ ẹ́ wálẹ̀; kò sí ohun tí ó lè mú kí o wakọ̀ láìléwu lórí yìnyín tabi ọ̀nà ti yìnyín bó bí o bá wà á bí o ti máa ń wàá.
- Jẹ́ kí iná àti fèrèsé rẹ kí ó mọ́. Nínú gbogbo yìnyín àti ìkúùkù kúrò lára ọkọ̀ rẹ kí ó tó wakọ̀.
- Bẹ̀rẹ̀ nípa rírìn jẹ́jẹ́ kí o sì rọra yẹ ìjánu rẹ wọ̀ kí o lè mọ bí ó ti ń ṣiṣẹ́ sí.
- Bẹ̀rẹ̀ nípa rírìn jẹ́jẹ́ kí o tó dé ibi tí ọ̀nà ti papọ̀ tàbí yípadà.
- Jẹ́ kí àgbá ilé epo rẹ àti ike ìfọwájú rẹ kí ó kún.
- Lo ẹ̀wọn, táyà ìkúùkù, tàbí táyà rédíà lórí bi tí ó yẹ lórí ọ̀nà pàjáwìrì nígbà tí a bá fọ ohùn pàjáwìrì.

## Ìpèsè Ohun Èlò Pàjáwìrí:

Kí o kọ́ àwọn ohun èlò pàjáwìrì nínú ọkọ̀ rẹ tí ó ní:

- Abẹ̀bẹ̀
- Iná kékeré àti bátìrì
- Ohun ìtọ́jú ṣíwájú ilé-ìwòsàn
- Aṣọ ìbora
- Kitty litter tàbí iyẹ̀pẹ̀ (fún ìfẹsẹ̀rinlẹ̀ lórí yìnyín tàbí ìkúùkù)
- Ṣọ́bìrì kékeré àti Ìkólẹ̀

### E. Sikidi

Àrìnmọ́lẹ̀ láàárín táyà rẹ àti ojú-ọ̀nà kìí sábà á rí bákan náà. Bí àpẹrẹ, iyẹ̀pẹ̀, egúrù, ilẹ̀ tí kò tẹ́jú, epo fifán orí ilẹ̀, gbígbòòrò si nínú eré sísá, omí ní ojú ọ̀nà máa ń mú àlẹ̀mọ́ra kí ó kéré.  Àyè wipé sikidi tàbí yíyọ̀ lè gbòòrò si nígbàtí àlẹ̀mọ́lẹ̀ bá kéré.

Bí ọkọ̀ bá bẹ̀rẹ̀ sí ń tọ, ó ṣe pàtàkì lati mọ ohun tí ó yẹ láti mu padà bọ̀ sípò ní kíákíá. Lára àwọn òfin tí ó ṣe kókó ni:

- Yàǹda agbára ọkọ rẹ (awẹ́ gáàsì), awẹ́ ìjanu, èyíkéyìí ti o bá ń lò, láti mú kí ọkọ̀ padà sípò.
- Darí si ibi tí o ti ń tọ.
- Wo ibi tí o fẹ́ kí ọkọ̀ rẹ lọ.
- Tẹ awẹ́ ìjánu rẹ nígbà tí o báá tún ń yọ́ mọ - nígbà tí táyà rẹ bá tún lẹ̀ mọ́ ojú ọ̀nà.
- Máa tẹ agbára ọkọ̀ rẹ díẹ̀díè (títẹ gáàsì) lè ṣe ìrànlọ́wọ́ nígbà tí ẹ̀yin ọkọ̀ rẹ bá kọṣẹ́.

### F. Agbára Inú Omi

Omi tí ó wà lójú ọ̀nà lè fa wàhálà fún àwọn awakọ̀. Bí eré sísá ọkọ̀ rẹ tí ń pọ̀ si bẹ́ẹ̀ni omi ojú ọ̀nà ń pọ̀ si, o lè padà máa rìn niǹu omi. Nígbà tí eléyìí bá ṣẹlẹ̀, táyà rẹ máa yọ kúrò lára ọ̀nà. Eléyií ni à ń pè ni “Agbára Omi”. Agbára omi lè gba àwọn ìjọba kan tàbí gbogbo agbára ọkọ̀ rẹ lọ́wọ́ rẹ. Láti dẹ́kun Agbára omi, jẹ́ kí táyà rẹ wà ní ipò tí ó dára kí o sì dín eré sísá rẹ kù lorí ilè tútù. Bí o bá ti ń sọ agbára ìdarí nù:

- Gbé ẹsẹ̀ rẹ kúrò lórí gáàsì.
- Mạ ṣe tẹ ìjánu ọkọ̀ rẹ.

- Jẹ́ kí ọkọ̀ rẹ máa lọ tààrà.
- Tẹ̀ẹ́ jẹ́jẹ́ títí tí wà a fi gba agbára rẹ padà.

## G. Ọ̀nà-Ojú irin Òpópónà tí ó ń sọdá







Rántí, ọkọ̀ ojú-irin kò le yára dúró. Nítorínà, o nílò ìsọ́ra púpọ̀ tí o bá ń súnmọ́ ìsọdá ojú- irin tí o sì kọjá lórí rẹ̀.

Nígbà tí o bá ń súnmọ́ ìsọdà ojú-irin:

- Kíyèsi àwọn ọkọ̀ míràn tí wọ́n fẹ́ dúró níbi ìsọdá ojú-irin. Look foBọ́ọ̀sì, Bọ́ọ̀sì ilé-ìwé, àti ọkọ̀ àjàgbé tí ó gbé àwọn ohun tó léwu gbudọ̀ dúró ńiwájú gbogbo ìsọdá ojú-irin.
- Má a wò fún ọkọ̀ ojú-irin nígbà gbogbo. Ọkọ̀ ojú-irin le wá láti apá méjèèjì, wọ́n sì le wà nítòsí tí wọ́n sì ń yára rìn ju bí ó ṣe hàn lọ.
- Tí ibodè bá ti wọ́lẹ̀ tàbí tí àwọn iná ìkìlọ̀ ń tàn bi mọ̀nàmọ́ná, ó tún mọ̀ sí pé ojú ọ̀nà náà wà ní tìítìí fún ìgbà díẹ̀. Má ṣe lọ kí o sì dúró títí ibodè náà yóò gbé sókè tí àwọn iná ìkìlọ̀ sì ti dáwọ́ dúró.



- Lẹ́hìn tí ọkọ̀ ojú irin bá ti kọjá, wo ọ̀nà méjèèjì kí o tó bẹ̀rẹ̀ sí rìn lójú ọ̀nà ojú irin. Ri dájú pé ọ̀nà ojú irin náà ṣófo kí o tó sọdá. Ó seé ṣe kí ọkọ̀ ojú-irin míràn ma bọ̀ lórí ọ̀nà míràn.
- Má ṣe bẹ̀rẹ̀ sí ní sọdá lórí ọ̀nà ojú-irin bí kò ṣe pé o lè ré kọjá pátápátá kí ọkọ̀ ojú-irin tó súmọ́. Ri dájú pé àyè wà fún ọkọ̀ rẹ ní ọ̀nà kejì ti ojú-irin kí o tó sọdá.
- Tí o bá ní pàjáwìrì lórí tàbí nítòsí ibi ìsọdá ojú-irin, jáde kúrò nínú ọ̀kọ̀ náà kí o sì rìn jìnà sí ọ̀nà ojú irin. Ròyìn àwọn pàjáwìrì tàbí ìṣòro ààbò ní ibi ìsọdá ojú-irin nípa lílo àwọn àlàyé tí ó wà ní àmì ètò ìkìlọ̀ pàjáwìrì aláwọ̀aró àti funfun.




## H. Àbò Ibùdó Iṣẹ́

Agbègbè iṣẹ́ jẹ́ agbègbè kan ní pàtó ní òpópónà tàbí òpópónà márosẹ̀ níbi tí iṣẹ́ mímọ, ìtọ́jú tàbi amáyédẹrùn ti n lọ lọ́wọ́, Tí a sábà máa ń fi àmi àti irinṣẹ́ ìṣàkóso ọkọ̀ tọ́ka sí. Agbègbè yìí le ṣe ìdíwọ́ sí ìrìn àjò ọkọ̀, àti àwọn òṣìṣẹ́, ọkọ̀ àti irinṣẹ́ tí ó wà ní àyíká. Agbègbè iṣẹ́ le wà fún ìgbà díẹ̀ tàbí fún ìgbà pípẹ́, tí o sì ṣeé ṣe kí wọ́n ti apá kan òpópónà pa, Àwọn ọ̀nà míràn, àti àwọn àyípadà míràn sí ìlànà ìrìn àjò ọkọ̀ tó jẹ́ déédé.

Agbègbè iṣẹ́ le wà ní ojú kan, bi ìgbàtí wọ́n bá ń fẹ ojú afárá, tàbí kí o ma sọ̀kalẹ̀ ní ojú ọ̀nà díẹ̀ díẹ̀, gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àtẹ̀jáde ìlà lórí pópó . Agbègbè iṣẹ́ le túmọ̀ sí àwọn ipò àìretí, bi:

- Ìlànà ìrìn àjò ọkọ̀ tuntun.
- Àwọn irinṣẹ́ ìṣàkóso ọkọ̀ tó wà fún ìgbà díẹ̀ (àmi, kónù, àgbá, àmì ìfihàn, tàbí àtẹ̀jáde ìlà lórí pópó)
- Àwọn ọ̀nà tí ó há
- Ìyípadà àwọn ọ̀nà pópó
- Ìpàdé àwọn ọ̀nà àti ẹ̀gbẹ̀ pópó.
- Ìsàlẹ̀ ojú pópó / ojú-pópó tí kò dàn
- Ìdínkù ìjìnnà ìrísí ojú
- Ọ̀nà mìí tí a yàn
- Ẹ̀rọ iṣẹ́ àti ọkọ̀ ikọ́lé tó ń rìn díẹ̀díẹ̀ tí ń padà sínú ìrìnàjò ọkọ̀ ni pópó.

Àwọ̀ ọsàn ni àwọ̀ fún agbègbè iṣẹ́. Tí o bá rí àwọn àmì ní àwọ̀ ọsàn nígbà tí ò ń wa ọkọ̀, ṣe àfiyèsí kí o sì gbáradì fún àwọn ipò ìwakọ̀ àìretí tí ó wà níwájú. Nígbà tí ò ń wa ọkọ̀ ní agbègbè iṣẹ́, Sọ́ra fún àwọn irinṣẹ́ ìṣàkóso ìrìn àjò ọkọ̀ ti ìgbà díẹ̀ bi àmi, kónù, àgbá, àmì ìfihàn, tàbí àtẹ̀jáde ìlà lórí pópó. Wọ́n yí ó tọ́ ọ sọ́nà láti la agbègbè iṣẹ́ kọ já láìléwu.


A ṣe àgbékalẹ̀ agbègbè iṣẹ́ pẹ̀lú ààbò rẹ lọ́kàn. Tẹ̀lé àwọn òfin ààbò wọ̀nyí nígbà tí ò ń wakọ̀ ní agbègbè iṣẹ́:

- Máa ṣọ́ra- jẹ́ kí ààbò jẹ́ ìjẹlọ́kàn rẹ àkọ́kọ́.
- Ìmọ́lẹ̀ tó ń tàn bi mọ̀nàmọ́ná nínú àgbègbè iṣẹ́ túmọ̀ sí pé àwọn òṣìṣẹ́ wà níbẹ̀. Ṣe àfiyèsí- ṣe ìgbọràn sí àwọn àmì agbègbè iṣẹ́, rìn díẹ̀díẹ̀ ki o si máa ṣọ́ra fún àwọn òṣìṣẹ́.
- Ṣọ́ra fún eré sísá rẹ – ṣe ìgbọràn sí òdiwọ̀n eré tí a gbékalẹ̀ ki o sì mọ̀ pé àwọn kámẹ́rà ìyára le wà níbẹ̀. Ìjìyà owó fún ìwakọ̀ pẹ̀lú ìyára le ga ní àgbègbè iṣẹ́ ó sì tún le ga si tí àwọn òṣìṣẹ́ bá wà níbẹ̀. Ìmọ́lẹ̀ aláwọ̀ aró tí ó ń tàn bi mọ̀nàmọ́ná túmọ̀ sí pé kámẹ́rà ìyára ń ṣiṣẹ́.
- O lè rí Ìmọ́lẹ̀ aláwọ̀ ewé tí ó ń tàn bi mọ̀nàmọ́ná lórí ọkọ̀ ìtọ́jú òpópónà tàbí ẹ̀rọ iṣẹ́ nínú àti níwájú àgbègbè iṣẹ́
- Retí ohun àìretí – ipò àgbègbè iṣẹ́ maa ń yípadà nígbogbo ìgbà nítorínà múra láti fèsì, pẹ̀lú pípa ọkọ̀ tán patapata bí ìrìn àjò ọkọ̀ níwájú rẹ bá dúró.
- Dín àwọn ìdàrú kù- yàgò fún lílo Fónù alágbèéká, yíyí ibùdó rédíò, jíjẹun, àti àwọn ìdàrú mîì.
- Bọ̀wọ̀ fún ẹlòmíràn- Darapọ̀ mọ́ ìrìn àjò pẹ̀lú ìṣọ́ra, má ṣe tẹ̀ lé ọkọ̀ tó wà níwájú gan-an, kí o sì má ṣe yí ọ̀nà padà àyàfi pé ó jẹ́ dandan.
- Ṣe ìgbọràn sí ìtọ́nà ẹni tí ó ń fi fúláàgì hàn.

| Ìmọ́lẹ̀ ní agbègbè iṣẹ́ | |
|---|---|
| Ìmọ́lẹ̀ ofeefee osan/ ofeefee tí ń tan | Agbègbè iṣẹ́ tí wọ́n lò/ àwọn òṣìṣẹ́ wà níbí |
| Iná mọ̀nàmọ́ná aláwọ̀ aró | kámẹ́rà ìyára ń ṣiṣẹ́. |
| Iná mọ̀nàmọ́ná aláwọ̀ ewé | Ọkọ̀ ìtọ́jú òpópónà |

## I. Àsúnjọ Súnkẹrẹ-Fàkẹrẹ Ọkọ̀ (Oríta )

Àwọn ọ̀nà tí ó wọ oríta máa ń ní àmì yíìdì. Nígbà tí o bá dé oríta, o gbọ́dọ̀ tẹ̀lé òfin ìrìnnà tí ó wà nílẹ̀ ní gbogbo ìgbà. Máa ṣọ́ra nígbà tí o bá fẹ́ dé oríta gẹ́gẹ́ bi ti àwọn ìyànà mîìràn. Bí o ti ń dé oríta:




- Di eré sísá rẹ ku.
- Dúró sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún ọ̀nà náà.
- Máa kíyèsí àwọn ẹlẹ́sẹ̀ kí o sì fi àyè sílẹ̀ fún wọn lati sọdá.
- Rọra rìn dé ibi ojú yíìdì náà kí o sì dúró fún àyè lójú ọ̀nà. Máa kíyèsí ọkọ̀ tí ó fẹ́ jáde nínú oríta náà. Ìwọ kò nílò láti dúrò lójú ọ̀nà náà bí kò bá sí ọkọ̀ níbi orita náà.

Bí oríta náà bá ní ju ìlà kan, dúró sí orí ìlà rẹ. Nígbà tí o bá ń gbìyàjú láti jáde, tan iná àyípadà ọ̀tún rẹ kí o sì jáde lórí ìlà lẹ́yìn tí o bá jáde tán kí ó tó kọjú sí ibi tí o fẹ́ lọ.

## J. Wíwakọ̀ ìpínlẹ̀-dé-ìpínlẹ̀ àti àwọn ọ̀nà aláàyè díẹ̀


“Awọn ọ̀nà aláàyè díẹ̀” ni àwọn ọ̀nà ńlá tí kò sí ibi tí ọ̀nà ti pádé tàbí iná ìgboro. Ìwọ̀nba ni ibi tí o lè gbà wọlé tàbí jáde nínú ọ̀nà náà. “Ìpínlẹ̀ sí Ìpínlẹ̀” je irufe awọn ọ̀nà aláàyè díẹ tí ó lọ láti ìpínlẹ̀ kan dé èkéjì.

## Fún àwọn Ọkọ̀ tí ó ń wọlé



Ìpínlẹ̀ sí Ìpínle àti àwon ọ̀nà aláàyè díẹ̀ mĩìràn ni wọ́n máa ń sábà gbà wọlé láti ẹnu ibìkan àti òpópónà. Ẹnu kòtò ni o má agbà wọlé sí ọ̀nà márosẹ̀. o maa lo òpópónà eléré láti tún eré sísá rẹ ṣe láti fi àyè gba àwọn tí ó ti ń bọ̀ lójú ọ̀nà Ìpínlẹ̀ sí Ìpínle̊. Nigba ti o ba n wo òpópónà Ìpínlẹ̀ sí Ìpínlè tàbi àwon ọ̀nà aláàyè díẹ̀ mĩìràn, ìwọ kò gbọ́dọ̀ fo ibi ìlà kĩìki tí ó pín ibi àbáwọlé àti òpópónà náà sí méjì. Ti o ba n wakọ ní ilọra si gbedeke èrè-sisa lọ ni opopona, o gbọdọ wakọ ni ọna apa ọtùn nigbakugba ti o ṣee ṣe.

## Fún Jíjáde Ọkọ̀



Yà sí ìlà ọ̀tún kí o tó dé ibi tí o ti fẹ́ yà jade. Bẹ̀rẹ̀ sí ń tẹ̀ ẹ̀ agbàrà jẹ́jẹ́ tí o bá ti wọ títì irosẹ̀. Títì irosẹ naa ni o maa gbe e lo si ona abajade àtipé á sì fún ẹ ní àsìkò láti bẹ̀rẹ̀ jẹ́jẹ́ títí wàá fi dé eré sísá tí kò léwu. Tẹ̀síwájú pẹ̀lú sùúrù lọ sí ibi eré sísá tí a fihàn ti a léde láti jáde kúrò lórí ìlà. Bí o bá jáde ní ibi tí kò yẹ, tẹ̀síwájú títí tí ìwọ á fi kọjá ẹnu ìjáde náà. Lẹ́yìn náà. Wá àyè láti tún wọlé sí ojú ọ̀nà. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ dúró tàbí padà sẹ́yìn ní ibì Kankan lójú òpópónà náà.

## Dídúró

Ko si aye fun e lati duro lori ila nibi ti oko ti n lo lati Ìpínlẹ̀ sí Ìpínlẹ̀ tàbí òpópónà mĩìràn. O lè dúró ní ibi èjìká àmọ́ ìyẹn nígbà tí ọkọ̀ rẹ bá yọnu (kọ ṣiṣẹ́ mọ́) tàbí o ní ohun pàjáwìrì mĩìràn. Bí o bá ma dúró níbi èjìká náà, tan iná pàjáwìrì rẹ láti kìlọ̀ fún àwọn awakọ̀ mĩìràn kí o sì dúró sínú ọkọ̀ rẹ bí o bá lè ṣe bẹ́ẹ̀. Ohun tí o léwu gidi ni láti dúró tàbí rìn kọ́já lójú ọ̀nà Ìpínlẹ̀ sí Ìpínlẹ̀ tàbí àwọn òpópónà mĩìràn nítorí àwọn ọkọ̀ ń sáré gidi.


## K. Ètò Ìsìnkú

Nígbà tí o bá ń wakọ̀ níbi Ètò Ìsìnkú, o gbọ́dọ̀ tan iná iwájú rẹ kí o sì máa ṣáná pàjáwìrì rẹ kí àwọn ọkọ̀ ìyókù lè fún ẹ ní àyè láti kọjá.

O lè gba ibi iná pupa jáde bí ìwọ bá wà lára àwọn onísìnkú kí o sì tan iná rẹ sílẹ̀.

Bí wọ́n tilẹ̀ ní àmì aláwọ̀ ewé, àwọn ọkọ̀ ìyókù gbọ́dọ̀ fún àwọn ọkọ̀ onísìnkú náà láàyé. Wọ́n gbọ́dọ̀ fi àyè sílẹ̀ títí di ìgbà tí gbogbo ọkọ̀ tí ó tò léra náà máa fi lọ, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, wọ́n kàn lè tẹ̀síwájú láì yàsí ọdọ̀ àwọn olóòkú.

## L. Ọkọ̀ tí ó n rìn jẹ́jẹ́



O lè ṣe àláàbápàdé àwọn ọkọ̀ tí ó ń rìn jẹ́jẹ́ lójú ọ̀nà. Lára àwọn wọ̀nyí ni kẹ̀ké, ọkọ̀ àfẹ̀ṣinfà, àti àwọn ọkọ̀ oko. Ọ̀pọ̀ nínú wọn lè ní àmì ìrorarìn lára wọn (fihàn) ní ẹ̀yìn ọkọ̀ wọn láti kìlọ̀ fún ẹ pé, awọn kàn ń rìn ìwọ̀n máìlì 25 tàbí kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ láàárín wákàtí.

Àwọn ìtóni nìyí láti rìn pèlú àwọn ọkọ̀ tí ó rọra ń rìn:

- Máa ṣàkíyèsí níngbogbo ìgbà nípa ọkọ̀ tí ó lè máa rìn ìrìn-àjò ní ìrìn jẹ́jẹ́.
- Yí eré sísá ọkọ̀ rẹ àti àyè rẹ bí ó bá ṣeé ṣe.
- Ìgbà tí kò bá sí ewu nìkan ni kí o kọjá Ọkọ̀ tí ó n rìn jẹ́jẹ́.

Bí o bá tilẹ̀ fẹ́ tẹ̀lé Ọkọ̀ tí ó n rìn jẹ́jẹ́ títí tí ìwọ á fi rí àyè láìséwu láti kọjá rẹ̀, lo iná pàjáwìrì rẹ láti kìlò fún àwọn tí ó ń bọ̀ lẹ́yìn rẹ.

# ÌPÍN 6: ÌWÀ ỌKỌ̀ WÍWÀ BÚBURÚ

## A. Ògógóró, Oògùn Olóró àti Ọkọ̀ Wíwà

Mímutí wakọ̀ tàbí oògùn Olóró jẹ́ ewu ńlá fún ẹ̀mí gbogbo ènìyàn. Ògógóró àti Oògùn Olóró máa ń ní ipá lórí agbára rẹ láti wakọ̀. Èyí túmòsí pé wọ́n mú kí ó nira tàbí kí ó má ṣeéṣe fún ẹ láti wakọ̀ ní àìléwu.

Blood alcohol concentration (BAC) ni ìdíwọ̀n iye ògógóró tí ó wà nínú ẹ̀jẹ̀ rẹ. Maryland gbàgbọ́ pé irú ẹni tí ó bá ní ìwọn ògógóró .08 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ ni ó ń wàkọ̀ lábẹ́ àkóso ògógóró.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Maryland fi ìwọn .08 ṣe ìdíwọ̀n ọlọ́tí, kò sí ìwọ̀n ọtí tí kò lè ní ipa lórí wíwa ọkọ̀ láìléwu ènìyàn. Irísí àti ìrònú ìdájọ́ rẹ lè wà ní abé otí bí ìwọn BAC rẹ bá tilẹ̀ kéré gidi àtípé èyí sì lè yọrí sí kí á fi ẹ̀sù ọdáràn kàn ẹ́. Bí àpẹẹrẹ, ìríran rẹ, agbára rẹ láti ṣe àwọn ìgbésẹ̀ kan, àti akókó ìfèsì sí rẹ lè wà lábẹ́ ewu bí o tilẹ̀ mu ìgò ọtí kan àtipe èyí sì lè mú kí ewu ìkọlura kí ó pọ̀ si.

Ó nira gidi láti mọ ìwọn BAC tìrẹ tàbí bí ògógóró ti ní ipa lórí wíwakọ̀ rẹ. Ìwọ kò lè sọ látàrí iye ìgò ọtí tí o mu nítorí oríṣiriṣi àwọn ohun ni ó lè ní ipa lórí bí ara rẹ ti ń gba ògógóró wọlé. Lára wọn ni bí o ti wúwo sí, sísanra rẹ, ìgbà tí o jẹun kẹ́yìn àti ìwọn oúnjẹ tí ó jẹ nígbà náà. Bí ó ti rẹ̀ ẹ́ sí, ìrònú rẹ, àtipe oògùn lè ní ipa lórí bí ògógóró ṣe ńipa lórí agbára rẹ láti wakọ̀.

### Lábẹ́ 21 – Kò sí Àyè fún Ògógóró

Bí ìwọ kò bá tíì tó ọmọ ọdún 21, ó jẹ́ ohun tí ó tako òfin fún ẹ láti mu ọtí olóògógóró kankan. Bí àwọn agbófinró bá mú ẹ tí o sì ti ń mutí, à ó gbẹ́sẹ̀ lórí ìwé ìrìnnà awakò rẹ tabi fagile. Bí irú rẹ̀ bá ṣẹlẹ̀, wọn kò ní gbà ẹ́ láàyè láti wakọ̀. Ní àfikún, a lè fi ẹ̀sùn kàn ẹ́ lórí rírú òfin tí ó de mímu ògógóró lórí ìwé ìrìnnà awakò rẹ.

### Ṣí Ìdérí Ìgò Ògógóró

Ohun tí ó tako òfin ni láti wakọ̀ pẹ̀lú ìgò ìgógóró tí a ti ṣí ìdérí rẹ̀ ní ayé ìjòkó èrò ọkọ̀. Ìgò ṣíṣí ni agolo, ìgò, tàbí irúfẹ́ agolo mìíràn tàbí pálí. Pálí ògógóró mẹ́fà tí a ti ṣí, ti kò ní nǹkan nínú, tàbí láìsí ìgò/agolo ni a lè pè ní Ìgò ṣíṣí.


Lára àyè èrò ọkọ̀ ni:

- Àyè awakọ̀ àti àwọn èrò ọkọ̀.
- Ibikíbi tí awakọ̀ tàbí ẹ̀rò ọkọ̀ lè nọ́wọ́ sí láti ibi tí wọ́n jòkó sí.

### Controlled Dangerous Substances (CDS) – Ayédèrú àti Oògùn Kíkọ

Ayédèrú Oògùn, awon Oògùn Kíko, àti tábà oníkẹ́mìkà lè ni ipa ribiribi lórí agbára rẹ láti wakọ̀ ní àìléwu. Wọ́n lè ní ipa lórí ìgbàràdi rẹ, ìfarabalẹ̀ rẹ, àmúmọ́ra rẹ, àti àkókò ìfèsì. Gbogbo oògùn ni ó lè mú kí ó nira láti ṣe ìdájọ́ ìjìnàréré àti ìfèsì sí atọ́nà àti ìró lójú ọ̀nà. Wọ́n máa gbẹ́sẹ̀ lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ tàbí kí wọ́n fagile látàrí pé ò ń wakọ̀ labẹ ìdarí ohun èlò buburú.

Ó ṣe pàtàkì láti fi ara balẹ̀ dáradára lórí ìkìlọ̀ tí a kọ sára oògùn tí a kọ fún ẹ tàbí oògùn tí o rà ní ilé oògùn. Wá ìkìlọ̀ tí o sọ fún ẹ pé ìwọ kò gbọ́dọ̀ wakọ̀ tàbí kí o lo ohun ẹ̀rọ tí ó nípan nígbà tí o bá ń lo oògùn náà. Bí o bá wa ọkọ̀ lẹ́yìn tí o ti lo oògùn tí ó sọ fún ẹ kí o máa ṣe bẹ́ẹ̀, tí ó sì le ní ṕa lórí agbára rẹ láti wakọ̀ láìléwu, a lè fi ẹ̀sùn ọdáràn kàn ẹ́.



**Bí o bá pinnu láti mutí, pinnu láti máà wakọ̀.**

### Wíwakọ̀ Pẹ̀lú àwọn Ọmọdé

Bí wọ́n bá fi ẹ̀sùn imùọ́ti pàrà kàn ẹ́ tàbí wíwakọ̀ tòun toògùn olóró pẹ̀lú ọmọdé nínú ọkọ̀ rẹ, adájọ́ lè sọ owó ìtọ́ràn rẹ di ìlọ́po méjì tàbí ẹ̀wọ̀n rẹ.

## B. Wíwakọ̀ Pẹ̀lú ara Kíkan àti Ìbínú ni Ojú-Ọ̀nà

Lára àpẹẹrẹ wíwakọ̀ pẹ̀lú ara kíkan ni: sísáré, kíkọ̀dísọ́nà, títàpá sí atọ́nà ìirinà àti ohun èlò, pípàrò ìlà ní ọ̀nà tí ó léwu, àìfiyèsílẹ̀ fún ẹlòmĩràn, sísọdá lọ́nà àìtọ́ tàbí àìbofinmu.  Ònà tí ó kún, ìdíwọ́ aláìròtẹ́lẹ̀, sísáré, iṣẹ́ ojú ọ̀nà, àti ara rírẹ̀ lè mú kí ènìyàn wakọ̀ pẹ̀lú ara kíkan.

O gbọ́dọ̀ ní ìbọ̀wọ̀ kí o sì fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú gbogbo àwọn tí wọ́n ń lo ojú ọ̀nà. O gbọ́dọ̀ tẹ̀lé gbogbo òfin láti mú kí gbogbo ènìyàn wà láìléwu àti láti dènà ìkọlura. Àwọn àṣírí látí mú àdíkù bá àyè láti mú ẹ kópa nínú wíwakọ̀ pẹ̀lú ara kíkan ni:

- Fi àkókò díẹ̀ sílẹ̀ láti rìn ìrìn àjò.
- Ṣe sùúrù.
- Máa ṣọ́ra.
- Kọjú sí ìwà wíwakọ̀ rẹ.
- Máa júwe èrò rẹ ní gbogbo ìgbà. Jẹ́ kí àwọn awakọ̀ mĩràn mọ ohun tí o fẹ́ ṣe nípa lílo àwọn atóka ìyípo, abbl.
- Tẹ̀lé gbogbo òfin ìrìnnà awọn, àmì, atọ́ka àti àlà pèpé
- Yọ̀nda aye.
- Yàgò fún dídíje pẹ̀lú àwọn awakọ̀ mĩràn.

## C. Ìdíwọ́ nínú Ìwakọ̀

Fífarabalẹ̀ ṣe pàtàkì ó sì nípa láti wakọ̀ láìléwu. O gbọ́dọ̀ mọ ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ lójú ọ̀nà àti àwọn ọkọ̀ tí ó yí ẹ ká. Wà ní ìmúrasílẹ̀ àtipé ìwọ á sì lè yẹra fún ìkọlura. Gbogbo ìgbà ni kí o máa wo ibi tí àwọn ọkọ̀ ìyókù wa, ní iwájú, ní ẹ̀yìn àti èyí tí ó kágun sí ẹ.

"Ìdíwọ́ nínú Ìwakọ̀" ni Ìgbà tí o bá gbé ojú rẹ, àwọn ọwọ́ rẹ, pàápàá ọkàn rẹ kúrò nínú ọkọ̀ tí ò ń wà. Ìdíwọ́ nínú Ìwakọ̀ ń fa ewu tí ó pọ̀ ju ohun tí wọ́n máa ń fi sùn fún ọlọ́pàá tàbí ohun mĩràn lọ. Eyikéyi ìdíwọ́ ni ó lè mú kí o pàdánù rírí tàbí gbígbọ́ ohun tí ó lè mú kí o yẹra fún ìkọlura.

Oríṣiríṣi ohun tí ó tan mọ́ Ìdíwọ́ kí ìdíwọ́. Lára àwọn àpẹẹrẹ ni:

- Jíjẹ àti mímu.
- Yíyí asọ̀rọ̀mágbèsì tàbí ohun orin mĩràn.
- Ṣíṣe àtúnṣe tàbí ṣíṣe GPS.
- Bíbá ọmọdé tàbí ohun ọ̀sìn ṣeré.
- Ohun tí ó ń ṣeré nínú ọkọ̀.
- Sísọ̀rọ̀ àti títẹ àtẹ̀ránṣẹ́ lórí fóònù.
- Mímu sìga.
- Títọ́jú ṣe.
- Fífárungbọ̀n.
- Kíkàwé.
- Bíbá àwọn mĩràn jíròrò nínú ọkọ̀.



**Ofin gbogbogboògbò tí ó dára jù ni pé ṣe sí àwọn awakọ̀ ìyókù àti gbogbo àwọn tí ó ń lo ojú ọ̀nà bí o ti fẹ́ kí a ṣe sí ẹ.**

## Fóònù

Ohun tí o rú ófin ni láti lo ẹ̀rọ ilẹ́wọ́, tí ó fi mọ́ títẹ àtẹ̀ránṣẹ́ nígbà tí a bá ń wakọ̀. Eyí túmọ̀sí pé ìwọ kò lè lo fóònù rẹ bí o tilẹ̀ mu dání. O lè lo fóònù rẹ láti pè bí ìwọ kò bá fi sọ́wọ́ (aláìbọ́wọ́ ṣe). Bí o bá ṣe èyí, ìwọ̀nba ni kí o ṣe èyí mọ kí o sì ṣe àwọn wọ̀nyí láti wà ní àìléwu:

- Lo fóònù rẹ ní àsìkò pàjáwìrí nìkan; bí ó bá ṣeè ṣé, jẹ́ kí èrò ọkọ̀ kan ṣe eléyìí fún ẹ.
- Bí ó bá pan danadan láti pè ìpè náà, yà kúrò ní ojú ọ̀nà, kí o sì dúró kí o tó pe ìpè náà.
- Jẹ́ kí voicemail rẹ máa dáhùn gbogbo ìpè tí ó bá ń wọlé.
- Jẹ́ kí ìbánisọ̀rọ̀ lórí fóònù rẹ kéré gidi.

Bí o bá kéré ju ọdún 18 lọ, o lè má lè lo fóònù nígbà tí o bá ń wakọ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ aláìbọ́wọ́ ṣe. Àyàfì kan tí ó wà níbẹ̀ ni pé o lè lò ó láti fi pe 911 ìpè pàjáwìrì.

## D. Títòògbé Lori Ọkọ̀ Wíwà

Àìsùn dáradára lè tún fa ewu nínú ẹkọ̀ wíwà. Oorun máa ń mú ìfàsẹ́yìn bá ìfèsì sí ohun kan, mú kí òye wálẹ̀, ó sì kewọ́ ìdájọ́, gẹ́gẹ́ bí oògùn àti ògógóró. Èyí lè mú kí àyè láti kópa nínú ìkọlura pọ̀ si.

Àwọn awakọ̀ mìíràn lè tètè sùn ju àwọn mìíràn lọ (títòògbé). Lára àpẹẹrẹ ni àwọn tí ó máa ń wakọ̀ fún ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìgbà lójúmọ́, àwọn tí wọ́n ní ìṣoro oorun, àti àwọ tí wọ́n ń lo àwọn oògùn kan.

Ó ṣe pàtàkì láti mọ àwọn àmì pé ò ń tòògbé kí o sì gbé ìgbésẹ̀ kí o má bàá ní ìkọlura. Àwọn ti ìsàlẹ̀ yìí ni “àmì ewu tí ó wọ́pọ̀” àti òfin tí ó dára láti dojúkọ títòògbé lori Ọkọ̀ wíwà.

### Àwọn àmì ewu fún àwọn awakọ̀ tí ó ń tòògbé

Àwọn wọ̀nyí lè túmọ̀sí pé ò ń tòògbé àtipé kí o gbé ìgbésẹ̀ láti wà ní àìléwu:

- Ojú rẹ dì tàbí kúrò ní nǹkan tí ó ń wò.
- Ó nira fun ẹ láti gbé orí rẹ sókè.
- Ò ń yán ní gbogbo ìgbà.
- Ò ń ní àwọn èrò tí kò papọ̀ tí kò sì jọra.
- Ìwọ kò rántí ìgbà tí o kọjá ibi mélòó kan sẹ́yìn.
- O gbàgbé ibi tí ó yẹ kí o gbà jáde.
- Gbogbo ìgbà ni ò ń wakọ̀ kọjá ìlà rẹ.
- Gbogbo ìgbà ni ò ń pààrọ̀ eré sísá rẹ.



**Bí ó bá rẹ̀ ẹ́ tàbí oorun ń kùn ẹ́ nígbà tí ò ń wakọ̀, ohun tí ó dára jù ni pé kí o simi tàbí pààrọ̀ awakọ̀. Rírẹ̀ máa ń mú kí ọkàn rẹ rẹ̀wẹ̀sì ó sì ń jẹ́ kí ìjígìrì rẹ wọlẹ̀, ó sì ń mú ọkọ̀ wíwà léwu.**







Ìdá kan nínú mẹta àwọn ìkọlura tí ó le ni màá n wáyé láti ọwọ Ìdíwọ nínú Ìwakọ. Lílo fóònù jẹ́ ọkan lára ohun tí ó ń fa Ìdíwọ nínú Ìwakọ. Àmọ́, lára àwọn ohun búburú tí ó ń gba àkókò rẹ kúrò nínú ọkọ wíwà ni oúnjẹ jíjẹ, títú ojúṣe, bíbá àwọn ọmọdé ṣeré, àti pípààrọ asọrọmágbèsì. Jẹ awakọ tí ó farabalẹ tí ó ń yẹra fún ohun tí ó ń gba àkókò tí ó sì kọjú mọ ohun tí ó wà ní ọwọ rẹ-wíwakọ.

Ní ọdọọdún, ẹgbẹgbẹrún àwọn ènìyàn wọn ń fi òfin gbé ní ojú ọnà Maryland lórí mimu ọtí wakọ tàbí oògùn olóró wakọ. Ògógóró àti oògùn olóró máa ń nípa lórí agbára rẹ láti wakọ àti bí o ti máa ń ṣe tẹlẹ, àti agbára rẹ láti wakọ rárá.
Kí o tó jáde, jẹ awakọ TÍ Ó Ń SẸTÒ kí o sì ṣètò láti wálé ní àìséwu, kí o sì ṣètò awakọ onírẹlè. Bí wọn bá fi òfin mú ẹ fún rírú òfin wíwakọ ní ipa ti ó nípa tí ó fi mọ owó ìtánràn ńlá, fífẹwọn jura, àti ẹgbẹgbẹrún dọlà lórí ilé ẹjọ. Èyí tí ó burú jù ni pé, rírú òfin wíwakọ yìí lè yọrí sí egbò ńlá tàbí ikú, gbogbo rẹ ni a sì lè yẹra fún nipa ṣíṣe ìpinnu tí ó dára.

**Fún àlàyé síwájú si, kàn sí:**
**ZeroDeathsMD.gov**

# ÌPÍN 7: ṢÍṢE ÀJỌPÍN ÀNÀ

### A. Ojú-Ọ̀nà títọ́ fún Ẹlẹ́sẹ̀

Àwọn ẹlẹ́sẹ̀ ní ẹ̀tọ́ sí ọ̀nà ṣùgbọ́n wọ́n gbọ́dọ̀n tẹ̀lé ìdarí atọ́nà ìrìnnà. Nígbà tí kò bá sí atọ́nà ìrìnnà, o gbọ́dọ̀ dúró fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀ ní ìyànà bí tí wọ́n fàlà sí tàbí níbi tí wọn kò fàlà sí.

Awakọ̀ gbọ́dọ̀ fi ojú sílẹ̀ pàápàá fún àwọn elẹ́sẹ̀ tí wọ́n dití, fójú, tàbí tí ẹsẹ̀ wọn kò pé. Wọ́n lè ní ìṣoro rírí, gbígbọ́, àtipé wọ́n lè nílò àkókò si láti sọdá.

#### Sísọdá níbi tí Ọ̀nà ti sọdá

Ibi tí ọ̀nà ti sọdá ni ibi tí awọn ẹlẹ́sẹ̀ ti lè sọdá ọ̀nà àtipé àwọn awakọ̀ gbọ́dọ̀ dúró fún wọn láti kọjá.   Wọ́n fàlà ìsodá mìíràn sórí àlà pèpé, ṣùgbọ́n ti àwọn  mìíràn kò rí bẹ́ẹ̀. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ibi tí ọ̀nà ti pàdé ni ó ní ọ̀nà ìsọdá bí wọn kò tilẹ̀ fàlà si.

Àwọn òfin tí ó ṣe gbòógì:

- Nígbà tí atọ́nà ìrìnnà bá wà, àwọn awakò àti ẹlẹ́sẹ̀ gbọ́dọ̀ tẹ̀lé.
- Ìwọ kò gbọ́dọ̀ kọjá ọkọ̀ Kankan tí a dá dúro níbi tí ọ̀nà ti sọdá.
- Ó gbọ́dọ̀ fàyè fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀ nígbà tí atọ́nà iná eléwé bá tàn.
- Ó gbọ́dọ̀ fàyè fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀ nígbà tí aye ba wa fun  atọ́nà iná pupá bá tàn.



**Ránti pé bí ìwọ kò bá lè rí dígí ọkọ̀ àjàgbé, awakọ̀ rẹ̀ kò lè rí ẹ!**

### B. Àwọn Ọkọ̀ Pàjáwìrì

Àwọn ọkọ̀ pàjáwìrì, gẹ́gẹ́ bí ọkọ̀ àwọn ọlọ́pàá, ámbúlánsì, ẹrọ̀ panápaná ní àǹfàní láti kọjá nígbà tí wọ́n bá ń tẹ sìrín, tí wọ́n sì ń ṣẹ́jú iná iwájú wọn.  Lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ tí o bá rí tàbí gbọ́ ìró ọkọ̀ pàjáwìrì ti ó ń bọ̀ tí ó sì ń lo atọ́nà rẹ̀, o gbọ́dọ̀:

- Yà sí etí ẹ̀gbẹ́ ọ̀nà típẹ́típẹ́.
- Yà kúrò ní ibi tí ọ̀nà ọ̀nà ti pàdé, ati
- Dúró jẹ́ títí tí ọkọ̀ pàjáwìrì náà máa fi kọjá.

Tí o bá ń lọ sí ọ̀nà ibi tí ọkọ̀ pàjáwìrì náà ń lọ tí ó sì ń lo atọ́nà rẹ̀, ìwọ kò lè kọjá rẹ̀ títí tí ó máa fi dúró tàbí ìgbà tí ọlọ́pàá kan bá sọ pé kí o lọ.

Bí o bá ń sún mọ́ ọkọ̀ pàjáwìrì, ọkọ̀ afakọ̀ tàbí ọkọ̀ oníṣẹ́ mìíràn tí a dá dúró, o gbọ́dọ̀ tẹ̀sí ọ̀nà tí kò tẹ̀lé èyí tí dá dúró. Bí ó bá ṣeéṣe láti lọ, o gbọ́dọ̀ tẹ̀ ẹ́ jẹ́jẹ́ títí dé eré sísá ti kò ní ewu kí o sì múra láti dúró bí ó bá ṣe é ṣe.

### C. Àwọn Ọkọ̀ Ńlá àti Àwọn Ọkọ̀ Akérò

Kíyèsí ọkọ̀ àgbàgbé tí ó ń yipadà. Àwọn ọkọ̀ àjàgbé máa yí padà níbi tí ọ̀nà ti papọ̀ àtipe wọ́n nílò àyè tí ó pọ̀ ju àwọn ọkọ̀ lọ. Nígbà tí ọkọ̀ àjàgbé bá fẹ́ yí padà sí apá ọ̀tún, ó máa kọ́kọ́ yà sí apá òsì kí ó tó yí padà. Ìwọ lè rò pé wọ́n ń pààrọ̀ ìlà tí wọ́n sì ń gbìyànjú láti gba ọ̀tún lọ. Láti kọjá ọkọ̀ àjàgbé kan ní ẹ̀gbẹ́ kan lè léwu. Dúró láti wò bóyá ọkọ̀ àjàgbé náà fẹ́ yí padà ni kí o tó kọjá rẹ̀. Bí ọkọ̀ àjàgbé kan bá dúró tàbí tí ó ń súnmọ́ ibi tí ọ̀nà ti pàdé, máṣe gbìyànjú láti wọlé láti apá ọ̀tún nítorí awakọ̀ àjàgbé náà ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ìyípadà rẹ ni. O lè bá ara rẹ láàárín ọkọ̀ àjàgbé tí ó ń yípadà àti kòtò kan.

Nígbà tí o bá fẹ́ kọjá ọkọ̀ àjàgbé tí ẹ jọ ń lọ ní ọ̀nà kan ṣoṣo náà, kọ́já kíákíá kí ìwọ kí ó lè mọ


ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àyíká rẹ. Lẹ́yìn náà, kí o padà sí orí ilà náà pẹ̀lú ọkọ̀ àjàgbé náà ìyẹn nígbà tí o bá lè rí iná rẹ méjèèjì lára àyègbè rẹ.

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ibi tí ọ̀nà ti padé ni wọ́n kọ wipe ko dúró sí. Bí o bá dúró kọjá ibi tí wọ́n kọ dúró sí, ọkọ̀ rẹ lè ti dúró sí iwájú ọkọ̀ àjàgbé tí ó ń yípadà láti ọ̀nà àdúgbò tí ó kọgun. Má ṣe bọ́ sí iwájú ọkọ̀ àjàgbé. Ìwọn ọkọ̀ àjàgbé tí ó ti kó ẹrù kún lè wọn tó 80,000 pounds àtipé ó máa rín tó ìwọn orí pápá bọ́ọ̀lù àfẹsegbá láti dúró. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ọkọ̀ ni ìwọ̀ wọn jẹ́ 2,000 pounds.

## Ojúkò-Rárá

"Ojúkò ìfọ́jú" mẹ́rin ní ó wà káàkiri ọkọ̀ àjagbé níbi tí "kò ti lè rí" àwọn ọkọ̀ mĩìràn rárá. Èyí túmọ̀sí pé awakọ̀ ọkọ̀ àjàgbé náà kò lè rí ẹ. Àwọn ojúkò ìfójú yĩ ni à ń pè ní "Ojúkò-Rárá"

- **Ojúkò-Rárá Ẹlẹ́gbẹ́:** Àwọn ọkọ̀ àjàgbé àti ọkọ̀ elérò ní ojúkò rárá ní awọn ẹ̀gbẹ́ wọn. Bí ìwọ kò bá lè rí ojú awakọ̀ láti ara dígí ẹ̀gbẹ́ wọn, àwon náà kò lè rí ẹ. Bí ọkọ̀ àjàgbé naà bá pààrọ̀ ìlà, ìwọ lè wa nínú ewu bí ó bá jẹ ibi ìfojú rẹ ni o wà. Ojúkò ìfọ́jú apá ọ̀tún na ẹ̀gbẹ́ ọkọ̀ àjàgbé náà já, ó sì tàn sí ità ní ibi ìlà mẹ́ta.
- **Ojúkò-Rárá Iwájú:** Yàgò fún ṣíṣe ìrù-ìdí (lílẹ̀ tímọ́tímọ́ mọ́ ọkọ̀ tí ó wà níwájú rẹ). Yàtọ̀ sí ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́, ọkọ̀ àjàgbé àti ọkọ̀ elérò ní ibùdó rárá tí ó pọ̀ ní ẹ̀yìn wọn. Awakọ̀ Ọkọ̀ àjàgbé tàbí ọkọ̀ elérò kò lè rí ẹ ní ẹ̀yìn tí o wà. Bí ọkọ̀ àjàgbé tàbí ọkọ̀ elérò bá tẹ̀ ìjánu rẹ̀ díẹ̀ tàbí dúró, ìwọ kò ni ibìkan láti yà sí .
- **Ojúkò-Rárá Iwájú:** Máà ṣe sáré lọ sí iwájú ọkọ̀ àjàgbé tàbí ọkọ̀ elérò ní kété tí o bá ti kọjá rẹ̀. Awakọ̀ Ọkọ̀ àjàgbé àti ọkọ̀ elérò nílò ìlọ́po méjì àsìkò tí ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ nílò láti dúró. Wo iná iwájú méjèèjì ọkọ̀ elérò tàbí ọkọ̀ àjàgbé nínú dígí rẹ kí o tó bọ́ síwájú wọn, àtipé lẹ́yìn rẹ ìwọ kò gbọ́dọ̀ rọra rìn.
- **Àtìlẹ́yìn fún Ibùdó Rárá:** Ìwọ kò gbọ́dọ̀ yà ní ẹ̀yìn ọkọ̀ àjàgbé tí ó n fi ẹ̀yìn rìn. Ọgọọgọ́rún ènìyàn ni wọ́n ń pa tàbí ṣèeṣe lọ́dọọdún nítorí wọn kò kíyèsí ọkọ̀ àjàgbé tí ó ń fi ẹ̀yìn rìn. Àwọn awakọ̀ ọkọ̀ àjàgbé kò ní dígí tí ó ń rí ẹ̀gbẹ́ àtipé wọ́n lè máà rí ẹ nígbà tí o bá ń gba ẹ̀yìn wọn kọjá.




**D. Àwọn Ọkọ̀ Ilé-Ìwé**

### Awakọ̀ gbódọ̀ dúró fún ọkọ̀ àwọn ọmọ ilé-ìwé.

Bí ọkọ̀ ilé-ìwé kan bá ti dúró níwájú pẹlú iná rẹ tí ó ń ṣẹ́jú, bí o tí ń sún mọ́ ọ̀dọ̀ rẹ, o gbọ́dọ̀:

- Dúró ó kéré tán bí ìwọn ẹsẹ̀ 20 sí ẹ̀yìn ọkọ̀ ilé-ìwé náà, bi o bá wà ní ẹ̀yìn rẹ̀.
- Dúró ó kéré tán bí ìwọn ẹsẹ̀ 20 sí iwaju ọkọ̀ ilé-ìwé náà, bi o bá wà ní iwaju rẹ̀.

Ìwọ kò lè bẹ̀rẹ̀ sí ń tẹ̀síwájú àyàfi ìgbà tí ọkọ̀ ilé-ìwé náà bá gbéra tàbí kí ó pa iná rẹ̀ tí ó ń ṣẹ́jú.

Bí o bá wà lójú ọ̀nà ọlọ́pọ̀lọ́pọ̀ ìlà tí a fi nǹkan pín, ìwọ kò gbọ́dọ̀ dúró bí ọkọ̀ ilé-ìwé náà bá wà ní òdìkéjì ìlà.

## E. Ọ̀kadà

Àwọn Ọlọ́kadà ní irú ẹ̀tọ́ kan náà tí àwọn awakọ̀ mìíràn ní ojú ọ̀nà. Àmọ́ Ọlọ́kadà lè ṣèṣe ní ìdá mẹ́fà ju awakọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ lọ nínú ìkọlura. Ọ̀kadà kéré ju ayọ́kẹ́lẹ́ àti ọkọ̀ àjàgbé lọ, ní ìdí èyí ó lè nira láti sọ bí eré sísá wọn tàbí ìjìnnà síra wọn ti tó.

- **Fi àyè sílè fún Ọ̀kadà tí ó ń bọ̀ nígbà tí o bá ń yípadà sí òsi.** Bí ìwọ kò bá fi àyè sílẹ̀ fún ọlọ́kadà, a lè fi òfin mú ẹ pẹ̀lú ìjìyà tí ó nípan àtipé o lè fa ìpalára púpọ̀. Àwọn awakọ̀ ní ó máa ń jẹ̀bi nínú ìdá bí ìlàjì ìkọlura láàárín ayọ́kẹ́lẹ́ àti ọ̀kadà.
- **Wò ní ẹ̀méjì kí o tó pààrò ìlà tàbí kí o tó jádé sí ààrín ọ̀nà.** Wo dígí rẹ kí o sì wo èjìká rẹ bákan náà láti ri dájú pé kò léwu láti pààrò ìlà tàbí kí o tó jádé sí ààrín ọ̀nà. Ọ̀kadà lè farapamọ́ níbi ojúkò ìfọ́jú rẹ tàbí kí o máa tilẹ̀ ri bí o bá rọra wòó nítorí wọ́n kéré púpọ̀.
- **Má ṣe àjọpín ìlà kan ṣoṣo pẹ̀lú Ọ̀kadà.** Àwọn Ọlọ́kadà sábà máa ń yà kiri lójú ọ̀nà láti yàgò fún ewu ojú ọ̀nà bí kòtò tàbí epo lórí ilẹ̀, nítorí afẹ́fẹ́ àti kí àwọn ìyókùn lè rí wọn. Àwọn Ọlọ́kadà ní àǹfàní láti lo gbogbo ìlà ọ̀nà kan.
- **Ìwọ kò gbọ́dọ̀ ṣe “ìrù ẹ̀yìn” (rìn sún mọ́ jù) sí ọlọ́kadà.** Fi àyè bí ó kéré tán ìṣẹ́jú ààyá 3-4 sílẹ̀ láàárín ọkọ̀ rẹ àti ọ̀kadà tí ó wà níwájú rẹ. Àwọn ọ̀kadà lè nílò láti dúrò díẹ̀ fún àwọn ewu ọ̀nà bí òkuta, ọ̀nà tútù tàbí ojú-irin ti ó sọdá tí kò tan mọ́ ọkọ̀ ní ọ̀nà kan náà. Ọlọ́kadà sábà máa ń dí eré sísá wọn kù ní ọ̀nà tí kò gbà kí iná ìjànú wọn tàn. Ní ìdí èyí, máa múra sílẹ̀ kí o sì fi àyè tí ó pọ̀ sílẹ̀ fún ọ̀kadà.
- **Fi àyè púpọ̀ sílẹ̀ láàárín ọkọ̀ rẹ àti ọ̀kadà nígbà tí o bá ń kọjá.** Atẹ́gùn tí ó ń fẹ́ àti òyì ọkọ̀ tí ó ń kọjá lè nípa lórí ọ̀kadà. Nígbà tí o bá kọjá ọlọ́kadà tán, ri dájú pé o lè rí iná ńla iwá ọlọ́kadà na kí ó tó padà sí ojú ilà rẹ. Bí ọ̀kadà kan ba ń kọjá rẹ, o ní láti wà lórí eré sísá rẹ kí o sì fún wọn ní àyè láti kọjá.
- **Máa ṣóra nígbà tí o bá ń wakọ̀ súnmọ́ àkójọ àwọn ọlọ́kadà.** Ọlọ́kadà máa ń kópa nínú ìdije eré tí ó níiṣe pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọlọ́kadà. O nílò ètò ìbánisọrọ̀ tí ó dára àti sùúrù láti wakọ̀ pẹ̀lú àwọn wọ̀nyí. Bí o bá nílò láti pààrọ̀ ìlà tàbí pé o fẹ jáde, tètè tan iná rẹ kí o sì dúró fún àwọn ọlọ́kadà náà láti pa ọ̀nà fún ẹ. Darapọ̀ pẹ̀lú àwọn èrò tàbí ọlọ́kadà wọ̀nyí nígbà tí àyè bá wa fún ẹ nìkan ni tí kò sì sí ewu. Bí ó jẹ́ àjọ kékeré ni, ó lè rọ́rùn láti tẹ̀ ẹ́ wálẹ̀ kí àwọn àjọ náà kọjá kí o tó pààrọ̀ ìlà.

Jọ̀wọ́ ṣe àgbéyẹ̀wò ìwé atọ́nà ọ̀kadà bí o bá fẹ́ ìwé ìrìnnà awakọ̀. O lè ri lórí itàkùn MVA.

## F. Kẹ̀kẹ́

Ọkọ̀ náà ni kẹ̀kẹ́ jẹ́, gẹ́gẹ́ bí òfin Maryland. Àyè wà fún oníkẹ̀kẹ́ láti lo ojú ọ̀nà àtipé wọ́n sì gbọ́dọ̀ tẹ̀lé gbogbo atọ́nà ìrìnnà. Àmọ́ àwọn oníkẹ̀kẹ́ ṣòro láti rí, wọn kò ní ariwo, àtipé wọn kò ní ìdíwó àbò nítòsí wọn gẹ́gẹ́ bí ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́. O gbọ́dọ̀ fi sùúrù wakọ̀ súnmọ́ kẹ̀kẹ́ – nítorí àṣìṣe kékeré lè mú ìpalára ńlá tàbí ikú dání.

## Máa retí Oníkẹ̀kẹ́ lójú Ọ̀nà

Máa retí láti rí àwọn Oníkẹ̀kẹ́:

- Nínú gbogbo oríṣiríṣi ọ̀nà (yàtọ̀ sí òpópónà ìpínlẹ̀ sí ìpilẹ̀ àti afárá àti kòtò ojúkọ̀ etí ìlú).
- Ibi tí ọ̀nà ti pàdé àti oríta.
- Nínú gbogbo ojú-ọjọ́.
- Nígbogbo àkókò ní ọ̀sán àti ní òru.

Oníkẹ̀kẹ́ lè rìn lójú òpópónà ìrìn-àjò (níbi tí àwọn ọkọ̀ ayọ́kẹ́lè wà) fún àbò ara wọn. Wọ́n lè ṣe èyí nítorí pé ọ̀nà náà kéré, tàbí láti yàgò fún ewu ìdíwọ́ tàbi ewu àlà. Ní ojú ọ̀nà tí kò ní èjìká, tàbí nígbà tí a bá wa ọkọ̀ gúnlẹ̀ sí apá ọ̀tún, ibi tí ó sàbà ní àbò fún oníkẹ̀kẹ́ jù ni ààrín ọ̀nà ìrìn-àjò. Ní Maryland, oníkẹ̀kẹ́ lè rìn ní gbogbo ìlà bí ó tilẹ̀ ń rìn nínú eré sísá tí ó kére sí eré ìrìnnà (bí ọ̀nà náà bá kéré jù fún ọkọ̀ ayọ́kẹ́lé láti kọjá kẹ̀kẹ́ náà láìléwu nígbà tí o bá wà lórí ìlà).

Kí o tó ṣí ilẹ̀kùn ọkọ̀, wò bóyá oníkẹ̀kẹ́ kan wà ti o le maa bo lẹ́yìn.

## Apá Ọ̀tún

Oníkẹ̀kẹ́ ní ẹ̀tọ́ láti kọjá nígbà tí ọkọ̀ báa ń yípadà, ní ìdí èyí o gbọ́dọ̀ fi àyè sílẹ̀ fún kẹ̀kẹ́.

Nígbà tí o bá bó sí ojú ọ̀nà tàbí kọjá lójú ònà oníkẹ̀kẹ́ tàbi èjìká rẹ̀, o gbọ́dọ̀ fi àyè sílẹ̀ fún àwọn oníkẹ̀kẹ́ tí ó wà níbè láti kọjá.

Awọn kẹkẹ ni ẹtọ ọna kanna bi awọn ẹlẹsẹ ni ọna ikorita.  Ikuna lati fi ẹtọ ọna fún kẹkẹ ti o wa s’okunfa ìjàmbá gbe awọn itanran ati tàbí akoko ni ẹwọn ati awọn ayọ̀kúrò aaye lori àkọsílẹ̀ iwakọ rẹ.

## Àwọn agun kẹ̀kẹ́ ní òpópónà

A gba kẹ̀kẹ́ láyè ní òpópónà káàkiri ìpínlẹ̀. Fún àwọn agun kẹ̀kẹ́ – Nígbà tí o bá ń gun kẹ̀kẹ́ rẹ ní òpópónà, rántí láti fún àwọn ẹlẹ́sẹ̀ àti àwọn tó ń lò ìrànlọ́wọ́ ẹ̀rọ ìrìn-àjò ní apá ọ̀tún ọ̀nà. Àwọn àṣẹ òfin ti agbègbè le lòdì sí lílo kẹ̀kẹ́ ní òpópónà; jọ̀wọ́ tọ́ka sí kóòdù agbègbè.

## Títẹ̀lé Oníkẹ̀kẹ́

Bí o ti ń dé ọ̀dọ̀ Oníkẹ̀kẹ́, tẹ̀ ẹ́ jẹ́jẹ́. Má ṣe tẹ ìfé ọkọ̀ rẹ. Oníkẹ̀kẹ́ lè gbọ́ ariwo ọkọ̀ tí ó ń bọ̀ àtipé ariwo ńlá lè mú kí ọwọ́ wọn gbọ̀n, èyí sì lè fa jàǹbá.

Oníkẹ̀kẹ́ kò ní iná atọ́nà, ní ìdí èyí wọ́n máa lo ọwọ́ láti júwe èròngbà wọn fún ẹ.

Má ṣe súnmọ́ oníkẹ̀kẹ́ jù. Rántí pé àwọn ihò kékere, ìgò àti àwọn ohun ewu mìíran lè léwu fún oníkẹ̀kẹ́. Kẹ̀kẹ́ lè dúró kí ó sì tún tẹ̀síwájú lááàrín àkókò díẹ̀ ní ìdí èyi oníkẹ̀kẹ́ lẹ̀ máa bì tàbí kí ó pààrọ̀ eré sísá rẹ̀ láti yàgò fún ewu ọ̀nà tí ọlọ́kọ̀ kò lè rí.

## Kọjá pẹ̀lú Sùúrù – fún ọ̀kadà ní ó kéré tán ìwọn bàtà 3

Rọra kọjá kẹ̀kẹ́ gẹ́gẹ́ bí o ti máa kọ́já ọkọ̀ tí ó ń rọra rìn. Máa múra láti tẹ̀ ẹ́ jẹ́jẹ́ kí o sì dúró títí tí ojú ìrìnnà máa fi mọ́. Lẹ́yìn náa fi ó kéré tán ìwọn bàtà 3 sílẹ̀ lááàrín ọkọ̀ àti kẹ̀kẹ́ náà nígbà tí o bá ń kọjá. Fi àyè púpọ̀ sílẹ̀ bí o bá ń kọjá kẹ̀kẹ́ lójú ònà kẹ̀kẹ́ yálà ní èjìká rẹ̀ tàbí lójú ọ̀nà kan náà pẹ̀lú ọkọ̀ rẹ. Ri dájú pé o rí kẹ̀kẹ́ náà láti ara dígí rẹ kí o tó padà sí ilà rẹ.

## Máa ṣóra ní ibi tí Ọ̀nà ti pàdé, orí afára àti òpópónà

Ní gbogbo ìgbà ni kí o má rò ó pé àwọn oníkẹ̀kẹ́ ń lọ tààrà lójú ibi tí ọ̀nà ti pàdé nàà àyàfi bí wọ́n bá ṣe àpẹrẹ pé awọn fẹ́ yà. Fi àyè gba oníkẹ̀kẹ́ gẹ́gẹ́ bí o ti lè fi àyè gbà ọkọ̀ mĩ̀ràn. Àwọn oníkẹ̀kẹ́ sábà máa ń rì ní ẹ̀gbé ọ̀nà tàbí títì, ní ìdí èyi wo ẹ́gbẹ́ méjèèjì kí o tó yà sí ẹ̀gbẹ́ títì tàbí ẹ̀gbẹ́ ònà.

Rántí pé kẹ̀kẹ́ lè wá láti apá ibi tí a kò reti. Oníkẹ̀kẹ́ ti ó ti lóye sábà máa wa kẹ̀kẹ́ kíákíá (bí ìwọn 35 mph) àtipe ó lè ti súnmọ́ ẹ jù bí o ti rò lọ.

- Máà ṣe yà sí apá ọ̀tún láti inú ìlà lẹ́sékẹsẹ̀ ti o bá kọjá oníkẹ̀kẹ́ ní èjìká rẹ̀ tàbí lójú ọ̀nà kẹ̀kẹ́. Ìlà tààrà ni ìlà ti ó tẹ̀síwájú.
- Gbìyànjú láti ri pé kò sí kẹ̀kẹ́ Kankan ní apá ọ̀tún rẹ tàbí ní ojúkò ìfójú rẹ nígbà tí o bá ń yípadà sí apá ọ̀tún.
- Ki o tò bẹ́rẹ̀ sín yi yípadà sí apá ọ̀tún, lọ si apá ọ̀tun dáradára ní ònà kẹ̀kẹ́, èjìká, tàbí ìyànà apá ọ̀tún.
- Nígbà tí o bá ń yípạdà, fi àyè gba kẹ̀kẹ́ gẹ́gẹ́ bí o ti ń fi àyè gba ọkọ̀ mĩ̀ràn tí ó ń ló tààrà. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ yà sí apá òsì lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ níwájú kẹ̀kẹ́.
- Wò ó dáradára bóyá kẹ̀kẹ́ Kankan ń bọ̀ ki o tó gba apá ọ̀tún ọkọ̀ tí ó ń yípadà kọjá.
- Nígbà tí ọ̀nà bá tín-ín-rín nítorí afárá, àwọn ọkọ̀ tí a wà gúnlẹ̀, tàbi ohun ìdíwọ́ mĩ̀ràn ní apá ọ̀tún, máa retí oníkèkẹ́ tí o wà ní èjìká rẹ láti dárapọ̀ mọ́ ọ̀nà ìrìn-àjò náà.

## Wíwakọ̀ ní Alẹ́

Bí ó bá rí ohun kan ní ọ̀nà ní alẹ́, máà ṣe rò pé kò sí ní ojú ọ̀nà. Ó lè jẹ́ kẹ̀kẹ́ lójú ọ̀nà ìrìn-àjò. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, oníkẹ̀kẹ́ lè yàgò fún lílo èjìká títì ní alẹ́ nígbà tí kò bá sí ọkọ̀ nitorí àwọn ẹka igi, kòtò, ìdòtí, àti wípé gbogbo àlà pẽ̀pé ni ó ṣòro lati rí. Iná rẹ lè kìlọ̀ fún oníkẹ̀kẹ́ láti yà sí èjìká títì fún ẹ láti kọjá, àmọ́ ó máa ń gba àkókò ní alẹ́. Nígbà tí o bá ń súnmó kẹ̀kẹ́, lo iná iwájú rẹ kékeré.

## Kìyèsí àwọn Ọmọdé

Nígbà mĩ̀ràn, a kò lè so ohun tí àwọn ọmọdé tí wọ́n wà lórí kẹ̀kẹ́ lè ṣe, nítorí náà máa retí ohun tí kò wọ́pọ̀. Rántí pé wọ́n kéré o sì lè nira láti rí wọn. Ó ṣeeṣe kí àwọn ọmọdé tí wọ́n ń gun kẹ̀kẹ́ kí ó máa fi àmì Kankan sílè kí wọ́n tó yà. Máa ṣọrá fún àwọn oníkẹ̀kẹ́ tí ó fẹ́ wọ́ ojú ọ̀nà láti ọ̀nà ẹ̀gbẹ́ tàbí ibi tí a wa ọkọ̀ gúnlẹ̀ sí. Tẹ̀lé àṣẹ eré sísá ní àgbègbè ilé-ìwé àti agbègbè ibùgbé kí o le láyè láti ri àwọn ọmọdé oníkẹ̀kẹ́, kí o lè wakọ̀ láìléwu.

## G. Mopeds ati Scooters

Àwọn awakò ọkọ̀ mopeds àti ọkọ̀ scooters gbọ́dọ̀ tẹ̀lé gbogbo òfin ìrìnnà. Àwọn awakọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ àti ti àjàgbé gbódọ̀ máa ṣàkíyèsí mopeds àti scooters nítorí ìrísí wọn mú kí wọ́n ṣòro láti rí.

Wọ́n lè wa mopeds àti scooters lórí gbogbo ọ̀nà tí gbèdéke eré sísá rẹ̀ jẹ́ máìlì 50 láàárín wákàtí tàbí kí ó kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ. Wọ́n lè wà:

- Ní ẹ̀gbẹ̀gbẹ́ ara wọn tàbí ní ẹlẹ́nìkan
- Lójú ọ̀nà tàbí ní èjìká rẹ̀.

Àwọn awakò mopeds àti scooters gbọ́dọ̀ wa ọkọ̀ wọn súnmọ́ apá ọ̀tu ojú ònà bí agbára wọn bá ti mọ.

Máa ṣọra ní àyíká moped àti scooter pàápàá ní ibi tí ọ̀nà ti pàdé nígbà tí wọ́n lè máa yí padà tàbí máa ló tààrà. Bákan náà máa ṣọra lójú ọ̀nà tín-ín-rín níbi tí ó lè máa sí àyè làti kọjá.

## H. Níní Òye Ìmọ̀ Ẹ̀rọ Ọkọ̀

"Advanced Driver Assistance Systems" (ADAS) Ìmọ̀ ẹ̀rọ Ọkọ̀ ni àwọn àbùdá ọkọ̀ tí ó máa ń mú kí wíwakò kí ó wà ni àìléwu. Ìmọ̀ ẹ̀rọ ADAS ńràn wá lọ́wọ́ láti pa èmí mọ́ kí a sì dènà ìpalára. Nígbà ti a bá lò wọ́n dáradára, wọ́n ń dẹ́kun 40% ìpalára.

Wọ́n ṣe àgbékalẹ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ̀ ADAS láti ràn ẹ́ lọ́wọ́ lórí iṣẹ́ ọkọ̀ wíwà bi:

- Dídúró sórí ìlà rẹ.
- Mímú àdínkù bá awon ojúkò ìfọ́jú.
- Ìjìnàsíra si àwọn mìíràn láìléwu
- Dídenà Ìpalára.
- Igúnlẹ̀

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ọkọ̀ ni wọ́n ń lọ sẹ́ńsò àti ìyàwòrán láti mọ ewu tí ó lè wà ní ọ̀nà. Àwọn àpẹrẹ irú ìmọ̀ ẹ̀rọ wọ̀nyí ni ijànú ọkọ̀ onipàjàwìrì igbálòdè, Onìrànwọ́ pipa mọ́ ìlà, àti ikilọ̀ ojúkò ìfọ́jú.

**Má ṣe fi gbogbo ara gbọ́kàn lé ADAS láti darí Ọkọ̀ rẹ. Ojúṣe rẹ ni ṣiṣẹ́ àìléwu Ọkọ̀ rẹ ní gbogbo ìgbà!** Ojúṣe rẹ ni láti mọ gbogbo ohun tí ó wà ní àyíká rẹ nípa wíwo ojú ọ̀nà pẹlú dígí àti ìyàwòrán rẹ.

Mọ̀ pé:

- Ìmọ̀ ẹ̀rọ náà ní gbèdéke àti pé ó lè má ṣiṣẹ́ dáradára nínú òjò, ìkúùkù, ọyẹ́, lórí òkè ati àwọn ihò kékèké.
- Ìmọ̀ ẹ̀rọ máa ń ṣiṣẹ́ ní ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ lorí oríṣiríṣi ọkọ̀ - àpótí iwájú rẹ̀ gan lè yàtọ̀.
- Oríṣiríṣi ni orúkọ tí Ìmọ̀ ẹ̀rọ náà ní àtipé àwọn orúkọ yìí kò ṣàlàyé irú iṣẹ́ tí ó ń ṣe.

Ìgbà gbogbo:

- Jẹ́ kí sẹ́ńsọ̀ ọkọ̀ rẹ kí ó wà ní mímọ́ kí ó má sì bàjẹ́.
- Jẹ́ kí okun ìmọ̀ ẹ̀rọ náà kí ó ṣe déédé pèlú àsìkò kí o sì tẹ̀lé ìmọ̀ràn olùpèsè rẹ̀.
- Jẹ́ kí òye ìmọ̀ ẹ̀rọ tí o fẹ̀ lò lórí eyíkéyìí ọkọ̀ kí ó yé ọ kí o sì lò wọ́n láìléwu àti bí ó ti tọ́. Kọ́ báwo nípa ṣíṣe àgbéyèwò ìwé atọ́nà ọkọ̀ rẹ tàbí bíbèrè lọ́wọ́ olùtakọ̀ rẹ.

Ní kòkárí gbogbo rẹ̀, gbogbo ìgbà ni kí o kọjú sí wíwakọ̀ rẹ kí o sì máa darí ọkọ̀ rẹ.



**Jẹ́ kí òye ìmọ̀ ẹ̀rọ tí o fẹ̀ lò lórí eyíkéyìí ọkọ̀ kí ó yé ọ kí o sì lò wọ́n láìléwu àti bí ó ti tọ́.**

# ÌPÍN 8: ÌKỌLURA ÀTI DÍDÚRÓ ỌKỌ̀

## A. Ìkọlura

Nígbàkúgbà tí o bá ni ìkọlura, tan iná pàjáwìrì rẹ tàbí abẹ̀bẹ̀ rẹ láti kìlọ̀ fún àwọn awakọ̀ mìíràn.

### Bí o bá kópa nínú ìkọlura níbi tí ẹnìkan ti ní ìfarapa tí ó fi mọ́ ẹlẹ́sẹ̀ tàbí oníkẹ̀kẹ́, o gbọ́dọ̀ dúró ní ojúkò ìṣẹ̀lẹ̀ yẹn àti:

- Pe 911 lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ láti rí ìrànlọ́wọ́ láti ọ̀dọ̀ ọlọ́pàá, panápaná, àti ànbúlánsì.
- Sọ iye àwọn tí ó kàn, irú ìpalára, àti ojúkò ìkọlura náà.
- Má ṣe gbé àwọn ọkọ̀ náà.

### Bí o bá jẹ̀bi ẹ̀sùn kíkúrò ní ojúkò ìkọlura tí ó yọrí sí ìpalára ńlá, ìwọ máa dojúkọ ìbáwí ńlá:

- Wọ́n máa gbẹ́sẹ̀ lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ (Wọn kò ní gbà ẹ́ láàyè láti wakọ̀).
- O lè lọ sí ọgbà ẹ̀wọ̀n tó bí ọdún 5 àti owó ìtọ́ràn tí ó lè tó $5,000.
- Kíkúrò ní ojúkò ìkọlura níbi tí ẹnìkan ti kú jẹ ìwà ìpànìyàn. O lè lọ sí ọgbà ẹ̀wọ̀n tó bí ọdún 10 àti owó ìtọ́ràn tí ó lè tó $10,000.

### Bí kò bá sí ìpalára àmọ́ tí ọkọ̀ rẹ kò lè rìn:

- Pe 911 lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, ṣe àlàyé ojúkò ìṣẹ̀lẹ̀ náà, ṣàlàyé pé kò sí ìpalará kankan ṣùgbọ́n pé o nílò ìrànlọ́wọ́ àwọn ọlọ́pàá.
- Ṣe sùúrù kí o má sẹ̀ gbìyànjú láti sọdá títì tàbí dá ọkọ̀ dúró. Ri dájú pé o yà kúrò ní ojú ọ̀nà.

### Bí kò bá sí ìpalára àmọ́ tí ọkọ̀ rẹ lè rìn:

- Gbé ọkọ̀ rẹ kúrò ní ojú ọ̀nà kí ó má sì jìnnà sí ibi tí ìṣẹ̀lẹ̀ náà ti ṣẹ̀. Èyí máa mú kí ìwọ àti àwọn ẹlòmìíràn wà ní àìléwu àtipé kò ní fa súnkẹrẹ-fàkẹrẹ.
- Gba àlàyé tí ó kúná lọ́dọ̀ àwọn awakọ̀ tí ó kù tí wọ́n kópa nínú ìkọlura náà. Ṣe àlàyé fún àwọn awakọ̀ ìyókù bákan náà. Lára wọn ni: orúkọ, ibùgbé, fóònù, nọ́ńbà ọkọ̀ àti ìpínlẹ̀ rẹ̀, nọ́ńbà ìwé ìrìnnà awakọ̀, orúkọ ọkọ̀ àti ẹyà rẹ̀, àti àlàyé nípa adójútòfò rẹ̀.
- Bèrè orúkọ, ibùgbé, àti fóònù àwọn óṣojúmi-kòró.
- Rántí ojúkò ìkọlura náà, ọjọ́ àti àkókò, iye ọkọ̀ tí ó kàn, ojú ọjọ́, àti bí ọ̀na ṣe rí. Kọ àlàyé yìí sílẹ̀ bí o bá lè kọ́.
- Rántí irú ìdíbàjẹ́ tí ó bá ọkọ̀ náà. Kọ àlàyé yìí sílẹ̀ kí o sì yàwòrán bí o bá lè ṣẹ́.
- Kọ òtítọ́ bí ìkọlura náà ṣe wáyé.

### Rántí pé o gbọ́dọ̀ pe ọlọ́pàá ní gbogbo ìgbà tí:

- Nígbà tí ẹnìkan bá ní ìpalára.
- Tí ọkọ̀ kan kò lè rìn.
- O jọ bí ẹni pé awakọ̀ kan ti mu ọ̀tí yó.
- Awakọ̀ kan kò ní ìwé ìrìnnà awakò.
- Awakọ̀ kan gbìyànjú láti kúrò ní ojúkò ìṣẹ̀lẹ̀ náà láìfún ẹ ní àlàyé lórí ètò adójútòfò àti àwọn àlàyé tí ó ṣe pàtàkì mìíràn.
- Wọn ti ba nǹkan ìlú kan jẹ́.

### Bí o bá kọlu ọkọ̀ tí wọn kò dásí tàbí ohun ìní mĩìràn tí wọn kò dásí, O gbọ́dọ̀:

- Wa ọkọ̀ rẹ gúnlẹ̀ kí ó súnmọ́ ojútò ìṣẹ̀lẹ̀ náà, láì dá ọkọ̀ dúró púpọ̀ jù bó ṣẹ̀ ye lọ̀
- Gbìyànjú láti wá ẹni tí ó ni ọkọ̀ tàbí ohun ìní náà láti sọ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ fún wọn kí o sì fún wọn ní àlàyé ara rẹ.
- Bí ìwọ kò bá rí ẹni tí ó ni ọkọ̀ tàbí ohun ìní náà, kọ ìwé pélébé kan sílẹ̀ fún wọn lórí ohun tí ó ṣẹlẹ̀ pẹ̀lú àlàyé nípa ara rẹ. Fi ìwé pélébé náà sí ibi tí wọ́n ti lè tètè ri.

Bí o bá fi ọkọ̀ rẹ gbá ohun ọ̀sìn tí o si ṣe ìpalára fun, o gbọ́dọ̀ pe ọlọ́pàá lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Ajá, Ológbò, Ẹṣin, àti màlúù ni àpẹrẹ àwọn ohun ọ̀sìn.

## B. Pàjáwìrí Ẹ̀gbẹ́ Ojú Ọ̀nà

Gbogbo Pàjáwìrí Ẹ̀gbẹ́ Ojú Ọ̀nà ni ó yàtọ̀, ní ìdí èyí kí o ṣe sùúrù kí o sì lo ọpọlọ rẹ, bóyá táyà tí ó jò ni, títọ́jú èrò inú ọkọ̀, tàbí nǹkan mĩìràn.

Nígbà tí Pàjáwìrí Ẹ̀gbẹ́ Ojú Ọ̀nà bá wà:

- Wo ipò náà.
- Lo òye ìdájọ́ tí ó dára láti pinnu bí o ṣe máa fèsì.
- Ṣe àkíyèsí àwọn ọkọ̀ mĩìràn nítorí Pàjáwìrí Ẹ̀gbẹ́ Ojú Ọ̀nà lè yípadà ní ààrín iṣẹ́jú kan.

### Wá ibi tí kò léwu

Ọdọọdún ni àwọn ènìyàn ń rí ìfarapa tàbí rí ikú he ní ẹ̀gbẹ́ ojú ọnà nígbà tí wọ́n bá ń dúró fún ìrànlọ́wọ́ ọkọ̀. Bí ọkọ̀ rẹ bá bàjẹ́, sa ipá rẹ láti gbe lọ sí èjìká ọ̀nà. Bí o bá lè dé ibi kòtò kan tàbí ibi ìgbọ́kọ̀sí, wò ó gẹ́gẹ́ bí ohun tí o lè ṣe bí ó bá tilẹ̀ túmọ̀sí pé kí o fi táyà tí ó ti jò rìn tàbí bíba rĩìmù rẹ̀ jẹ́. Bí o bá ṣe lè jìnà sí òpópónà sí ni àbò rẹ ti máa tó. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ dúró tàbí gúnlẹ̀ ní ibùdó onígun-mẹ́ta tí a kùn níbi tí ọ̀nà ti jáde.

### Bí o bá lè dúró nínú ọkọ̀:

Bí o bá lè dúró nínú ọkọ̀ rẹ, de ara rẹ kí o sì kọjú síwájú. Àwọn ọkọ̀ ní àwọn àbùdá àbò tí ó máa ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àbò rẹ àti ti àwọn èrò inú ọkọ̀ bí ọkọ̀ mĩìràn bá kọlu ọkọ̀ rẹ.

### Bí iwo ko bá lè dúró nínú ọkọ̀:

Bí kò bá mú ọgbọ́n wá tàbí ṣeéṣe láti dúró nínú sínú ọkọ̀ rẹ, kíyèsí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àyíká rẹ kí o sì yan àsìkò tí ó rọrùn fún olúkúlùkù láti jáde. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ dúró sí itòsí ọkọ̀ rẹ. Dípò bẹ́ẹ̀, tètè kúrò ní ojú ọ̀nà. Lọ sí ẹ̀yìn kọ̀rọ̀ kan, òpópónà, tàbí odi oju-irin. Bí ó bá ṣeeṣe, lọ sí òkè. Kọjú sí àwọn ọkọ̀ tí ó ń bọ̀ kí a sì farabalẹ̀ nítorí tí ọkọ̀ bá fẹ̀ yá wọ̀ sí ọ̀dọ rẹ.

## C. Ìdúró Ètò Ìrìnnà

Àwọn agbófinró máa ń kọ ìwé ètò ìrìnnà fún àwọn tí a fi ẹ̀sùn kàn pé wọ́n rú òfin ọkọ̀ ìrìnnà ní Maryland. O gbọ́dọ̀ tẹ̀lé àṣẹ ọlọ́pàá tí wọ́n bá dá ẹ dúró, bí bẹ́ẹ̀kọ́, wọ́n á fi òfin mú ẹ.

### Bí Agbófinró kan bá dá ẹ dúró:

- Yà sí apá kan ojú-ònà kí ó jìnnà bi o bá tí le jiìnnà sí òpópónà. Tan iná ìṣẹ́jú rẹ.
- Pa iná ọkọ̀ rẹ àti ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì.
- Yí fèrèsé ọkọ̀ rẹ sílẹ̀ kí o lè bá ọgá ọlọ́pàá sọ̀rọ̀.
- Jòkó sínú ọkọ̀ rẹ kí o sì lo ìgbàdí rẹ.
- Gbé ọwọ́ rẹ sí ibi tí ó hàn – ọrùn ọkọ̀ ni ibi tí ó dára jùlọ. Ìwọ kò gbọ́dọ̀ gbé ìgbésẹ̀ tí ó máa mú kí ọlọ́pàá náà rò pé ò ń sá pamọ́ tàbí pé o fẹ́ nọwọ́ mu nǹkan.
- Bí ọlọ́pàá náà bá já ìwé fún ẹ, ìwọ kò gbọ́dò bá ọlọ́pàá náà jiyàn lórí rẹ̀. Nígbà tí o bá dé ilé ẹjọ́, ìwọ má a ní àyè láti ṣàlàyé ara rẹ.

## D. Òfin Ìfarahàn

Ní Maryland, o gbọ́dọ̀ farahàn nígbà tí o bá ń súnmọ́ ọkọ̀ kan tí wọ́n dá dúró, tí ó nà dúrú, tàbí tí a wà gúnlẹ̀ tí iná rẹ̀ ń ṣẹ́jụ́. Bí ó bá ṣeéṣe láti farahàn, o gbọ́dọ̀ tẹ̀ ẹ́ jẹ́jẹ́ títí dé eré sísá ti kò ní ewu. Kíyèsí ojú-ọjọ́, ipò ọ̀nà náà, ojú ọ̀nà, àti àwọn ẹlẹ́sẹ̀ nígbà tí o bá pinnu eré sísá tí kò léwu.

Rírú òfin yìí jẹ́ ohun tí ó le pèlú àwọn ìjìyà ìsàlẹ̀ yìí:

- Owó ìtọ́ràn $110 àti pọ́ìǹtì kan lórí ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ. MVA máa ń lo pọ́ìǹtì láti ṣe àkọsílẹ̀ òfin rírú àti ìjìyà tí ó wà fun.
- Owó ìtọ́ràn $150 àti pọ́ìǹtì mẹ́ta bí òfin rírú náà bá yórí sí ìkọlura.
- Owó ìtọ́ràn $750 àti pọ́ìǹtì mẹ́ta bí ikú tàbí ìfarapa púpọ̀ bá wà.

Pọ́ìǹtì máa ń yọrí sí kí a gbẹ́sẹ̀ lé tàbí fagi lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.



## Lati ṣe àjọpín ọnà awakọ

Jẹ awakọ ti o gbà ẹmi là



## Lati wò lẹẹméjì awakọ

Jẹ awakọ ti o gbà ẹmi là

Àbò ẹlẹṣẹ àti oníkẹkẹ ní ipa lórí gbogbo ènìyàn ní Maryland.  Àwọn ìwádìí tí a kò nílò máa ń wáyé nítorí pé àwọn awakọ tàbí ẹlẹṣẹ ti mú òtí yó, wọn kò mọ nípa òfin ọkọ, tàbí wọn kò kíyèsára. Àwọn ọnà gbódọ jẹ ibi tí kò léwu fún gbogbo ènìyàn àtipé ó ṣe pàtàkì kí gbogbo wa ṣe ojúṣe wa.
Lára wọn náà ni oníkẹkẹ, Ọpọlọpọ ènìyàn ni kò mọ pé ọkọ ni a ka kẹkẹ mọ ní ojú ọnà Maryland, gẹgẹ bí ti ayọkẹlé tàbí ọkọ àjàgbé. Èyí túmọsí pé awakọ àti oníkẹkẹ gbọdọ kọ láti ṣe àjọpín ọnà àti láti ṣe ohun tí ó yẹ láti mú kí ara wọn wà ní àìléwu.
Jẹ Awakọ tí ó PÍN ỌNÀ NÁÀ – tẹ ẹ jẹjẹ, ṣe àkíyèsí kí o sì máa gbáradì fún ẹlẹṣẹ àti oníkẹkẹ.

Nígbà tí ìkọlura bá wà tí ó kan ọkọ ayọkẹlẹ tàbí ọkọ àjàgbé àti ọkadà, ní ọpọlọpọ ìgbà, ọlọkadà ni ó máa ń pàdánù. Nítorí pé kò sí àbò fún ọlọkadà bí àwọn èrò inú ayọkẹlẹ àti ọkọ àjàgbé, àwọn ọlọkadà máa ń ní ìpalára ni ìdá 75 nínú àwọn ìkọlura. Àwọn awakò àti àwọn ọlọkadà ní ojúṣe láti ṣe àjọpín ojú ọnà láìléwu.
Nígbà tí ìkọlura tí ó kan awakò àti ọlọkada bá wà, awakọ ni ó ń sábà jẹbi ní ọnà tí ó ju ìdájì lọ. Jẹ awakọ tí ó ń WÒ LẸẸMÉJÌ, ní gbogbo ìgbà ni kí o máa wò lẹẹméjì tàbí jù bẹẹ lọ kí o tó kọjá, pípàárọ ìlà, àti dídára pọ mọ ọkọ ojú pópó.

**Fún àlàyé síwájú si, kàn sí:**
**ZeroDeathsMD.gov**

# ÌPÍN 9: ÀWỌN ÌFÒFINDÈ MÌÍRÀN, ÒFIN RÍRÚ ÀTI ÌJÌYÀ RẸ̀

**A. Ìfòfindè**

Rántí pé àǹfàní ni ọkọ̀ wíwà kìí ṣe ètọ́. MVA ní àṣẹ láti gbé ìfòfinde lé iwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ láti ri dájú pé o wakọ̀ láìléwu. ìfòfinde wiwako ni gbedeke ti a gbe lori anfani re lati wako. Ìfòfinde lè dá lórí irú ìwé ìrìnnà awakọ̀ tí o ní tàbí tí gbé lé ẹ lórí nítorí pé o rú òfin àwọn òfin ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́. Ẹ̀sẹ̀ ńlá ni wíwakọ̀ ayọ́kẹ́lé pẹ̀lú Ìfòfinde lórí gbèdéke. O lè sọ àǹfàní wíwakọ̀ rẹ nù.

Àwọn ìfòfinde wíwakọ̀ yìí dá lórí àwọn oní-ìwé ìrìnnà ìdàgbàsóke lábẹ́ ọdún 18.

## Ìfòfinde Ìgbàdí inú Ọkọ̀

O gbọ́dọ̀ máa lo ìgbàdí inú ọkọ̀ aláàbò ní gbogbo ìgbà bí o bá ní ìwé ìrìnnà onígbà díẹ̀. Gbogbo èrò ọkọ̀ gbọ́dọ̀ lo ìgbàdí àbò tàbí ìgbàdí àbò ọmọdé.

## Ìfòfinde Èrò Ọkọ̀

Bí o bá ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀ tí o sì wà ní abẹ́ ọdún 18, ìwọ kò lè wa ọkọ̀ pẹ̀lú èrò ọkọ̀ láìsí aláàbójútó lábẹ́ ọdun 18 fún ọjọ́ 151 àkọkọ́ àyàfi tí wọ́n bá jẹ́ àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ. O lè wakọ̀ pẹ̀lú àwọn èrò ọkọ̀ lábẹ́ ọdún 18 tí kò tan mọ́ ẹ tí o bá ní adarí awakọ̀ tí ó dáńtọ́ pẹ̀lú rẹ. Àwọn mọ̀lẹ́bí rẹ lè jẹ́ ọkọ̀ tàbí ìyàwó rẹ, ọmọbìnrin rẹ, ọmọkùnrin rẹ, ọmọ-ọkọ rẹ obìnrin, ọmọ-ọkọ rẹ ọkùnrin, alábìnrin rẹ, alakùnrin rẹ, ẹ̀gbọ́nbìnrin, ẹ̀gbọ́nkùnrin, àti mọ̀lẹ́bí rẹ mìíràn tí ó ń gbé ní ilé yín. Wo Ìpín 10.B. fún ẹni tí ó kún ojú òṣùwọ̀n láti jẹ́ adarí awakọ̀.

## Ìfòfinde Àsìkò Alẹ́

Bí o bá ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀, àyè wà fún ẹ láti wakọ̀ láìní adarí awakọ̀ pẹ̀lú rẹ làárin 12:00 òru àti 5:00 àárọ̀, KÌ bí o bà:

- Wíwakọ̀ lọ, bọ̀, tàbí ní àkókò iṣẹ́ rẹ
- Wíwakọ̀ lọ tàbí bọ̀ láti ìṣètò wọ̀fún
- Wíwakọ̀ lọ tàbí bọ̀ láti àlàkalẹ̀ iṣẹ́ ilé ìwé
- Wíwakọ̀ lọ tàbí bọ̀ láti ètò eré ìdárayá tàbí àkókò ẹ̀kọ́ kan tí ó jọ mọ́ tí o ti kópa nínú rẹ̀

## Ìfòfindè Ẹ̀rọ Àìlókùn

Bí ìwọ bá ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀ tàbí àṣẹ ìrìnnà, o lè lo ohun ìbánisọ̀rọ̀ kankan tí kò ní okùn (tí ó fi mọ́ fóònù aláìfọwọ́mú) nígbà tí o bá ńwakọ̀. Àyàfi kan ṣo ṣo ni  nọ́ńbà pàjáwìrì 911.

**B. Àyẹ̀wò Oògùn Olóró tàbí Ọ́ti -- Àfọwọ́si Ẹlẹ́lọ̀ọ́**

Ní Maryland, bí o bá wakọ̀ tàbí tiraka láti wakọ̀ lójú ọ̀nà tàbí nínú ohun ìní ẹnìkan tí gbogbo ènìyàn máa ń lò, o ti gba (fi ọwọ́ si) láti ṣe àyẹ̀wò oogùn olóró tàbí ọ́ti bí agbófinró kan bá bèrè lọ́wọ́ rẹ láti ṣe. Àwọn àyẹ̀wò yìí díwọ̀n iye ọ́ti tàbí tàbi oògùn olóró tí ó wà nínú ara rẹ.

Bí ọlọ́pàá kan bá ní ìdí láti gbàgbọ́ pé ò ń wakọ̀ nígbà tí o wà lábẹ́ àkóso oògùn olóró, ọ́ti tàbí ohun èlò tí à ń darí rẹ̀, wọ́n lè gba fọ́ọ̀mù amòye tí ó ń mọ oògùn olóró nínú ẹ̀jẹ̀ tí ó fi lélẹ̀ níbi àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀. Wọ́n máa gbẹ́sẹ̀ lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ bí ìwọn ògógóró nínú ẹ̀jẹ̀ rẹ bá jẹ́ .08 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. MVA máa tún gbẹ́sẹ̀ lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ bí ògógóró bá ṡi tún wa nínú ara rẹ.

Bí ọlọ́pàá kan bá ṣe àfilélè gbólóhùn tí o ṣe é gbẹ́kẹ̀lé pé o kọ̀ láti ṣe àyẹ̀wò, MVA máa tún gbẹ́sẹ̀ lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.

## C. Gbígba ìwé ìdánimọ̀, ìwé ìrìnnà awakọ̀ ayédèrú tàbí èyí tí a parọ́ sí tàbí Àlàyé Ààyè Olùkẹ́kọ̀o

Bí o bá gbìyànjú láti gba ayédèrú ìwé ìdánimọ̀, ìwé ìrìnnà awakọ̀ tàbí àlàyé ààyè olùkẹ́kọ̀o ayédèrú, wọ́n lè jáwe fún ẹ àti/tàbí kí wọ́n gbé ẹ lọ sí ẹ̀wọ̀n lábẹ́ òfin ìjọba àpapọ̀ àti ìjọba ìpínlẹ̀.

Ohun tí ó tako òfin ni láti parọ́ nípa ọjọ́ orí rẹ láti rà, mú tàbí gba ògógóró. Ní àfikún sí àwọn ìjìyà tí a ṣàlàyé ní òkè yìí, wọ́n tún lè gbẹ́sẹ̀ lé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.

## D. Àwọn ìgbésẹ̀ Adarí

MVA lè gbẹ́sẹ̀ lé, fagi lé tàbí kọ̀ láti fún ẹ ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ bí o bá rú àwọn òfin ọkọ̀. Bí èyí bá wáyé, MVA máa fi ìwé ránṣẹ́ sí ẹ láti fi tó ẹ létí nípa:

- Irú ìgbésẹ̀ tí wọ́n ń múra láti gbé.
- Àwọn ìdí tí wọ́n fi fẹ́ gbé irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀.
- Irú ìgbésẹ̀ tí o lè gbé láti yí ìpinnnu yìí padà tàbí láti da dúró.

Ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìgbà, o lè bèrè fún Ìgbẹ́jọ́ adarí láti ṣàlàyé ìdí tí wọn kò fi lè gbé irú ìgbésẹ̀ adarí bẹ́ẹ̀.

Bí MVA bá gbẹ́sẹ̀ lé, fagi lé tàbí kọ̀ láti fún ẹ ní ìwé ìrìnnà awakọ̀, o gbọ́dọ̀ fún MVA ní ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ. Láìsí ìwé ìrìnnà awakọ̀, wọn kò ní gbà ẹ́ láàyè láti wakọ̀. Àkókò ìrókún-nílé tàbí Ìgbẹ́sẹ̀lé bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà tí ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ bá tẹ MVA lọ́wọ́.

### ìrókún-nílé ìwé ìrìnnà awakọ̀

Bí wọ́n bá ní kí ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ lọ rókún-nílé, ìwọ máa pàdánù láti wakọ̀ fún ìgbà díẹ̀. Ní ìgbà mìíràn, MVA lè pinnu láti pèsè ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbèdéke. ìwé ìrìnnà awakọ̀ onígbèdéke fi àyè gba ènìyàn láti wakọ̀ fún àwọn ìdíkan nìkan bíi lílọ àti bíbọ̀ ní ilé-iṣẹ́ tàbí ilé-ìwé.

### Dídá Àṣẹ Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ pada

Dídá àṣẹ ìwé ìrìnnà awakọ̀ Maryland padà le jù ìrókún-nílé lọ.

Bí wọ́n bá dá àṣẹ ìwé ìrìnnà awakọ̀rẹ padà, o lè má lè wakọ̀ mọ́ títí di ìgbà tí MVA bá pinnu pé o tún lè wakọ̀ láìléwu mọ́. Bí wọ́n bá dá àṣẹ ìwé ìrìnnà awakọ̀rẹ padà, àkókò íretí tí ó kéré jù wà kí o tó lè bèrè kí MVA da padà (ìtúmọ̀ pé kí o gbà á padà). MVA lè kọ ìbéèrè rẹ.

### Fífagilẹ́ Ìwé Ìrìnnà Awakọ̀ pada

Fífagilẹ́ ìwé ìrìnnà awakọ̀ Maryland padà le jù ìrókún-nílé lọ. Ó túmọ̀sí pé a ti fi òpin sí (parí) àfàní wíwakọ̀ rẹ àtipé a kò lè da padà. MVA lè fagilé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ bí wọ́n bá ri pé:

- Kò yẹ kí wọ́n ti fún ẹ ní ìwé ìrìnnà awakọ̀.
- Ìwọ kòpèsè àlàyé tí wọ́n bèrè tàbí tí ó ṣe régí lórí bí o ṣe gbà ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.
- Ìwọ lu jìbìtì nígbà tí o fi orúkọ sílẹ̀ tàbí gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.

Bí ọjọ́ orí rẹ bá kéré jù ọdún 18, òbí tàbí alágbàtọ́ lè bèrè pé MVA fagilé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ (Wo ìpín 2.F.).

## E. Àwọn Ìjìyà

Bí a bá ti gbé ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ kalẹ̀ lórí rẹ tàbí "Àsìkò àbójútó níwájú ilé-ẹjọ́" (PBJ) fún rírú òfin nígbà tí ò ń lo iwé ìrìnnà awakọ̀ onígbà díẹ̀.

- O ní láti parí ètò ìmútẹ̀síwájú awakọ̀, àti/tàbí
- ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ máa wà lábẹ́ ìrọ́kún-nílé tàbí ìfagilé. Nígbà tí ìrọ́kún-nílé tàbí ìfagilé bá parí, gbèdéke iṣẹ́ àti ètò ẹ̀kọ́ máa wà lórí ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.

### Ìjìyà fún Àwọn Ọ̀jẹ̀wẹ́wẹ́

Bí ọjọ́ orí rẹ bá wà lábẹ́ ọdún 18 pẹ̀lú ìwé ìrìnnà awakọ̀, a sì gbé ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ kalẹ̀ lórí rẹ fún rírú òfin tàbí a fún ẹ ní àsìkò àbójútó ṣíwájú ìdájọ́, àwọn ìjìyà kàn ẹ́:

- Ẹ̀ṣẹ̀ ÀKỌ́KỌ́ gbà kí o parí ètò ìmútẹ̀síwájú awakọ̀.
- Ẹ̀ṣẹ̀ ÌKÉJÌ máa yọrí sí ìrọ́kún-nílé ọlọ́jọ́ 30 fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ pẹ̀lú gbèdéke ọlọ́jọ́ 90 tí ó tẹ̀le èyí tí ó fún ẹ ní gbèdéke láti wakọ̀ sí ilé-iṣẹ́ àti ẹnu ètò ẹ̀kọ́ nìkan.
- Ẹ̀ṣẹ̀ ÌKẸ́TA máa yọrí sí ìrọ́kún-nílé ọlọ́jọ́ 180 fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ gbà, kí o wà níbi ètò ìmútẹ̀síwájú awakọ̀ fún awọn ọ̀jẹ̀wẹ́wẹ́ awakọ̀ àti onígbèdéke láti wakọ̀ sí ilé-iṣẹ́ àti ẹnu ètò ẹ̀kọ́ nìkan fún ọjọ́ 180.
- Oní ÌKẸ́RIN tàbí JÙ BẸ́Ẹ̀ LỌ máa yọrí sí fífagilé ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ. O gbọ́dọ̀ yege nínú gbogbo ìdánwò ìwé ìrìnnà kí ó tó lè gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ padà.

### Ìjìyà fún àwọn Àgbàlágbà

Bí ọjọ́ orí rẹ bá jẹ́ ọdún 18 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ pẹ̀lú ìwé ìrìnnà awakọ̀ onigba die, a sì gbé ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ kalẹ̀ lórí rẹ fún rírú òfin tàbí a fún ẹ ní gbèdéke ṣíwájú ìdájọ́, ìjìyà wọnyi kàn ẹ́:

- Ẹ̀ṣẹ̀ ÀKỌ́KỌ́ gbà kí o parí ètò ìmútẹ̀síwájú awakọ̀.
- Ẹ̀ṣẹ̀ ÌKÉJÌ máa yọrí sí ìrọ́kún-nílé ọlọ́jọ́ 30 fún ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.
- Oní ÌKẸ́TA tàbí JÙ BẸ́Ẹ̀ LỌ máa yọrí sí kí o rọ́kún-nílé ọlọ́jọ́ 180 tàbí ìgbàpadà ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ.

Àwọn ìjìyà yìí máa wá GẸ́GẸ́ BÍ ÀFIKÚN sí èyíkéyìí ìjìyà tí ó lè wá nínú ìdájọ́ ilé-ẹjọ́. Bákan náà léyìn ìdájọ́ tàbí gbèdéke Kankan ṣíwájú ìdájọ́ lórí òfin rírú, o máa nílò láti bẹ̀rẹ̀ àkókò àìní-ìdájọ́ olóṣù 18 kí ìwọ tó lè gbà ìwé ìrìnnà awakọ̀ padà.

## F. Lílo ibi Ìwàgúnlẹ̀ Aláàbọ̀-Ara, Ike Ìwé Ìrìnnà, àti Àpèlé



A lè jáwé fún ọ ní ọ̀nà tí ó le, bí ìwọ bá lo ibi Ìwàgúnlẹ̀ Aláàbọ̀-Ara, Ike Ìwé Ìrìnnà Aláàbọ̀-Ara, àti Àpèlé Aláàbọ̀-Ara ní ọ̀nà tí kò bófin mu. A lè já ìwé ìfofin mú fún ẹ fún àwọn òfin rírú wọ̀nyí:

- Wíwakọ̀ gúnlẹ̀ níbi Ìwàgúnlẹ̀ Aláàbọ̀-Ara láìṣe pé o ní Ike Ìwé Ìrìnnà Aláàbọ̀-Ara tàbí Àpèlé tí àwọn MVA tàbí àwọn tí wón kún ojú òṣùwọ̀n gbé jáde fún ike tàbí àpèlé náà lè jẹ́ ti awakọ̀ tàbí ti èrò inú ọkọ̀ náà.
- Wíwakọ̀ gúnlẹ̀ níwájú tàbí dídí iwájú pátákó ní ọ̀nà kànkan (kódà kí o ní ìwé ike ìrìnnà tàbí àpèlé).

- Wíwakọ̀ gúnlẹ̀ nínú èyíkéyìí níbi àyè tí ó kọ̀gun sí ibi Ìwàgúnlẹ̀ Aláàbọ̀-Ara (kódà kí o ní ìwé ike ìrìnnà tàbí àpèlé). ibi Ìwàgúnlẹ̀ jẹ́ ojú àyè níbi tí awọn tí ó wà lórí àga arọ máa ń gbà sọ̀kalẹ̀ nínú ọkọ̀ tàbí wọ ọkọ̀.
- Lílo Àpèlé Aláàbọ̀-Ara nígbà tí ọjọ́ orí rẹ̀ ti lọ.
- Lílo ìwé ìrìnnà Aláàbọ̀-ara tàbí Àpèlé Aláàbọ̀-Ara nígbà tí Aláàbọ̀-Ara náà kò sí níbẹ̀ àti láìsí ìdánimọ̀ tí ó péye.
- Èyíkéyìí jìbìtì tàbí irọ́ nígbà tí a bá sẹ àkọsílẹ̀ láti gba ìwé ìrìnnà Aláàbọ̀-ara tàbí Àpèlé Aláàbọ̀-Ara.

Lọ sí orí ìtàkùn MVA fún àlàyé síwájú si lórí Ìwàgúnlẹ̀ Aláàbọ̀-Ara.



**Njẹ́ o mọ? Ti wọn bá mú ọ fún ẹsun imutì-wakọ, iwọ yoo ni lati fi breathalyzer car lock (odinwọn-èémí fun atipa ọkọ) sori ọkọ rẹ ti yóò ṣe idiwọ fun ọ lati ṣi'na ọkọ ti o ba kẹ̀fin ọti.**

# ÌPÍN 10: ÀWỌN ÀLÀYÉ TÍ Ó ṢE PÀTÀKÌ MÌÍRÀN

## A. Àwọn ìpele Ìlera láti fi ṣọwọ́ sí MVA

Bí o bá ní ìkan tàbí òmírà nínú àwọn ìpò àìsàn tí a tọ́ka sí nísàlẹ̀ yìí, o gbọ́dọ̀ fi tó MVA létí nígbà tí o bá ń bèrè fún tàbí àtúngbéjáde ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ. Bí a bá ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe irú àìsàn bẹ́ẹ̀ lẹ́yìn tí o ti gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ, fi tó MVA létí nígbà tí wọ́n bá ṣe irú àyẹ̀wò bẹ́ẹ̀. Àwọn ẹ̀ka MVA bíi MVA's Driver Wellness àti Safety Division àti/tàbí Medical Advisory Board gbọ́dọ̀ fi ọwọ́ si fún ẹ láti gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ bí o bá ní èyikéyìí nínú àwọn àìsàn tí ó lè ní ipa lórí agbára rẹ láti wakọ̀.

- Ìtọ̀ ṣúgà tí ó ti mú kí ṣúgà ara ki ó kéré gan tí ó nílò ìrànlọ́wọ́ ẹlòmìíràn láàárín oṣù 6 sẹ́yìn.
- Warapá àti Gìrì
- Aragbígbóná tí o ti fa ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìnira láàárín oṣù 6 sẹ́yìn
- Rọ lápá-Rọ lẹ́sẹ̀.
- Àìsàn tí ó mú kí o máa kọ̀ óyi, dídákú tàbí gbígbàgbé ara
- Àìrórun sùn
- Ìtàn egbò inú ọpọlọ (TBI)
- Àìsàn tí ó ń fa ara rirẹ̀, gbígbàn, ọwọ́ ati ẹsẹ̀ kíkú tàìtai tí ó lè ni ipa lórí wíwakọ̀ rẹ.
- Ọwọ́ tàbí ẹsẹ̀ tí kò sí níbẹ̀ tàbí tí wọ́n ti gé tàbí tí ó ti kọṣẹ́ tí ó lè ni ipa lórí wíwakọ̀ rẹ.
- Àìsàn ojú tí ó ń ṣe ìdènà fún ìríran kedere ní ìwọn 20/70 acuity ó kéré tán nojú kan tàbí kòkòrò inú ojú tí ó tó dìgírìì 110.
- Ìṣòro ògógóró.
- Ìṣòro lílo oògùn olóró
- Àrùn ọpọlọ tí ó lè ni ipa lórí wíwakọ̀ rẹ.
- Ìṣòro àìleronú.
- Iyẹ rírа

## B. Adarí Awakọ̀ – Ohun tí wọ́n nílò àti Ojúṣe wọn

Bí o bá ní ìwé àyè ìrìnnà Maryland, ọkọ̀ tí wọ́n dárúkọ tàbí ìpele ọkọ̀ tí wọ́n dárúkọ nìkan ni o lè wà. O gbọ́dọ̀ ní adarí awakọ̀ pẹ̀lú rẹ. Adarí awakọ̀ ni:

- O kéré tán omo ọdún 21.
- Ní báyìí, ó ní ìwé ìrìnnà ó kéré tán ọlọ́dún mẹ́ta ní Maryland tàbí ìpínlẹ̀ mìíràn láti wa irú ìpele ọkọ̀ kan náà tí ò ń wà.
- Jókó sí ẹgbẹ́ rẹ àyàfi bí ó bá jẹ ọ̀kadà.

## C. Olùfiẹ̀ya ara sílẹ̀

Àwọn ènìyàn Maryland lè fún ènìyàn ní ẹ̀bùn ẹ̀mí àti ìlera nípa fífi ẹ̀ya ara wọn àti tisù wọn mìíran sílẹ̀ lẹ́yìn ikú.

- Ẹnikẹ́ni tí ó jẹ́ ọmọ ọdún 18 àti jùbẹ́ẹ̀ lè jẹ́ olùfiẹ̀ya ara sílẹ̀.
- Àwọn màjèṣín ó kérétán ọdún 16 lè fi ẹ̀ya ara sílẹ̀ bí òbí tàbí alágbàtó rẹ̀ bá fi ọwọ́ si (gbà bẹ́ẹ̀) nínú ìwé.

Wo gbólóhùn yìí nínú ìfitónilétí ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ tàbí àtúntẹ̀ rẹ̀:

"Jọ̀wọ́ wò bóyá lẹ́yìn ikú rẹ, o fẹ́ láti ran àwọn ẹlòmìíràn lọ́wọ́ nípa jíjẹ́ olùfiẹ̀ya ara sílẹ̀". Nípa títẹ "Bẹ́ẹ̀ni" o ti fi àṣẹ sí pé kí á gbé gbogbo àlàyé tí ó ṣe  pàtàkì nípa rẹ ránṣẹ́ sí Ẹ̀ka Ètò Ìlèra ti Maryland kí wọ́n sì gbé sí". Bí o bá fara mọ, o lè yàn ki ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ tọ́ka èyí Àlàyé síwájú síi lórí olùfiẹ̀ya ara sílẹ̀ ni a lè rí lórí ìtàkùn MVA.

**D. Fi Orúkọ sílẹ̀ láti dìbò**


Ìwé àbádòfin ìforúkọsílẹ ìdìbò 1993, tí wọ́n sábà ń pè ní "Motor Voter" jẹ́ òfin ìjọba àpapọ̀ . Èyí gbà kí MVA fi àyè gbà àwọn olùbárà rẹ̀ láti fi orúkọ sílẹ̀ fún ìdìbò, tàbí ṣe àtúnṣe àlàyé ìdìbò wọn, nígbà tí wọ́n bà gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ tàbí ìwé káàdì ìdámîmọ̀.

**E. Ohun Ìnílò fún Adójútòfò**

Gbogbo ọkọ̀ tí a bá fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní Maryland gbọ́dọ̀ ní ètò adójútòfò láti ọwọ́ ilé iṣẹ́ tí o fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní Maryland. Bí ìwọ bá ní ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ o gbọ́dọ̀ sètò adójútòfò fún ewu ara rẹ̀ ati ìdíbàjẹ́ ohun ìní gẹ́gẹ́ bí iye tí là kalẹ̀. Wo ìtàkùn MVA fún àlàyé lórí iye rẹ̀.

Ní gbogbo ìgbà ni ó gbọ́dọ̀ mu ìwé ìdánimọ̀ adójútòfò pẹ̀lú rẹ nígbà tí o báa ń wakọ̀. Káàdì yĩí lè jẹ́ ti orí ayélujára. Bí agbófinró kan bá bèrè káàdì adójútòfò rẹ, o gbọ́dọ̀ fi hàn wọ́n. Bí o bá kọ̀, wọ́n lè jáwé fún ọ̀.

**F. Òfin Ìgbàdí Ọkọ̀**



Gẹ́gẹ́ bí òfin ti sọ, awakọ̀ àti gbogbo àwọn èrò inú ọkọ̀ ni ó gbọ́dọ̀ lo ìgbàdí àbò tàbí ìgbàdí ìjòkó ọmọdé.

**G. Ìjòkó Àbò Ọmọdé**

Gbogbo ọmọde lábẹ́ ọdún 8 ni ó gbọ́dọ̀ rìn nínú ìjòkó àbò ọmọdé, àyàfi bí ọmọ náà bá jẹ́ 4'9" tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ọmọdé tí wọ́n kéré ju ọdún 2 gbọ́dọ̀ rìn nínú ìjòkó iwájú-ẹ̀gbẹ́ tí ó wà ní ìbámu pẹ̀lú àlàkalẹ̀ ìjọba àpapọ̀ títí di ìgbà tí wọ́n máa ga tàbí wúwo dé ibi tí olùpèsè rẹ̀ sọ. O gbọ́dọ̀ tẹ̀lé gbogbo àlàyé tí Olùpèsè ìjòkó àbò ọmọ rẹ àti ti ọkọ̀ rẹ sọ.

Lára ìjòkó àbò ọmọdé ni ìjòkó inú ọkọ̀, àga booster àti àwọn ìjòkó àbò ọmọdé mĩíràn tí ìjọba àpapọ̀ fi ọwọ́ sí.

Bí ìwọ kò bá lè ra ìjòkó àbò ọmọdé, o lè kàn sí Kids In Safety Seats (KISS) níbí ẹ̀kà ìlèera ti Maryland lórí 800-370-SEAT. KISS máa ń darí àwọn ètò ní gbogbo agbègbè ìpínlẹ̀ náà láti yá àwọn ènìyàn ní ìjòkó ọkọ̀ tàbí booster ní iye tí kò gá jù pàápàá fún àwọn ìdílé tí kò lè rà wọ́n. Ìjòkó lè má sí ní gbogbo ibi ní gbogbo ìgbà.

**H. Àpò Afẹ́fẹ́**

Àpò Afẹ́fẹ́ jẹ́ ohun àbò tí ó ṣe pàtàkì láti dá ààbò bò ẹ́ nínú íkọlura. Fún àbò tí ó dára jù.

- Lò wọ́n pẹ̀lú ìgbàdí ẹsẹ̀ àti ẹ̀jìká ọkọ̀ rẹ.
- Jòkó sún sẹ́yìn kúrò ní ọrùn rẹ dáradára. Gbìyànjú láti jẹ́ kí àyè tí ó tó ínsìi 10-12 wà láàárín ọrùn ọkọ̀ àti àyà rẹ.
- Àwọn aboyún gbọ́dọ̀ gbé ibi ìtan ìgbàdí náà sí abẹ́ ikùn wọn kí ó wálẹ̀ dáradára dé ibi itan wọn. Kí wọ́n gbé ibi èjìká ìgbàdí náà sórí ikùn wọn yíká.
- Àwọn ọmọdé lórí ìjòkó ẹ̀gbẹ́ iwájú ọkọ̀ kò gbọ́dọ̀ rin ìrìn-àjò lórí ìjòkó iwájú ọkọ̀ pẹ̀lú àpò afẹ́fẹ́ èrò inú ọkọ̀.
- Àwọn ọmọdé lábẹ́ ọdún 13 gbọ́dọ̀ rìn ìrìn àjò pẹ̀lú ìhámọ́ra ẹ̀gbẹ́ ìjòkó lórí àbò ìjòkó ọmọdé tàbí pẹ̀lú ìgbàdí ọkọ̀.

**I. Ìtúsílẹ̀ pẹ̀lú Anti-lock Braking System (ABS)**

Anti-Lock Braking Systems (ABS) máa ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ẹ láti dẹ̀nà títì ọrùn ọkọ̀ kí o lè dárí ọkọ̀ rẹ  Nígbákúgbà tí kọ̀npútà inú ọkọ̀ rẹ bá fura pé ẹsẹ̀ ìkan tàbí òmíràn ń tì, ABS á bẹ̀rẹ̀ sí ń fẹ́ atẹ́gùn sínú ìjánu rẹ ju ti àtẹ̀yìnwá kí wọn kí ó má ṣe tì. Nígbà tí ABS bá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́, o lè gbọ́ ariwo níbi ìjánu ọkọ̀ rẹ, abẹ̀bẹ̀ ìjánu náà á sì gbọ̀n ní abẹ́ ẹsẹ̀ rẹ. Yẹ àlàyé atọ́nà ọlọ́kọ̀ rẹ wò fún àlàyé síwájú sí lórí Anti-lock braking system.

### J. Wíwọ Ìbòrí orin, Yẹtí orin àti àkìbọ etí ṣe èèwọ̀

O lè má lè wakọ̀ pẹ̀lú àkìbọ̀ etí, ìbòrí etí, tàbí yẹtí orin ní etí méjèèjì. Kò sí àyè fún ohun aṣèrànlọ́wọ́ ìgbọ́ran.

### K. Ìgúnlẹ̀ Fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́

A kò nílò Ìgúnlẹ̀ fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ mọ́ nígbà tí o bá ń ṣe ìdánwò ọkọ̀ wíwà rẹ. Àmọ́ ṣá, ìwọ máa kọ́ nípa rẹ̀ nínú ètò ẹ̀kọ́ ọkọ̀ wíwà ti MVA. Òye kan náà tíe ma nílò nínú ìgúnlẹ̀ fẹ̀gbẹ́kẹ̀gbẹ́ ni a tún mẹ́nubà nígbà tí o bá ṣe "àyípadà onípọ̀ìntì méjì" ní àkókò ìdánwò ọkọ̀ wíwà tí o ṣe láti gba ìwé ìrìnnà awakọ̀ rẹ. Lára wọn ni: ìmọ̀ ìríran, ìdájọ́ àyè, ìwúlò dígí àti atọ́nà ìyípadà, ọrùn ọkọ̀, ìjánu ọkọ̀, àti ìdarí gbìigbèra ọkọ̀.

### L. Ìwa Ọkọ̀ gúnlẹ̀ inú ilé, Ìwa ọkọ̀ gúnlẹ̀ Ẹlẹ́yìn, Ìyípadà ọkọ̀ ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́ta


O gbọ́dọ̀ lè ṣe ìwàgúnlẹ̀ sínú ní àṣeyọrí, ìgúnlẹ̀ sínú ààyè, àti ìyípadà onípọ̀ìntì mẹ́ta ní àkókò ìdánwò ọkọ̀ wíwà rẹ. Ìgúnlẹ̀ náà ni a ṣe ní àyè 10' by 20' ní àkókò ìdánwò náà àti ìyípadà náà ní àyè 16' by 20. Àwọn ìgbésẹ̀ yìí ṣe àfihàn bí o ṣe lè ṣe ìdájọ àyè, lo dígí, àti atọ́nà ìyípadà, ọrùn ọkọ̀, ìjánu ọkọ̀, àti kí o sì darí ọkọ̀ rẹ nígbà tí o bá ń sáré. Wọ́n tún ṣe àyẹ̀wò ìríran, àtìlẹ́yìn àti ìmọ̀ ọkọ̀ wíwà ní gbogbògbò.

### M. Àwọn Òfin àti Àṣírí fún Kẹ̀kẹ́ wíwà

Gẹ́gẹ́ bí àwọn awakọ̀, onikẹ̀kẹ́ ní ẹ̀tọ́ àtí ojúṣe láti lo ọ̀nà láìléwu. Ṣe ojúṣe rẹ nípa jíjẹ́ onikẹ̀kẹ́ aláìléwu àti oníbọ̀wọ̀.

**Pa àwọn Òfin Ìrìnnà mọ:** Rìn tààrà àti ní ojú kan ní ọ̀nà tí ó ṣee sọ. Ṣe ètò sílẹ̀ kí o sì fi àyè sílẹ̀ láti borí ewu àti láti darí ìrìnnà àti láti ṣílẹ̀kùn ọkọ̀. Fi àyè gbà àwọn ẹlẹ́sẹ̀, kí o sì pa gbogbo atọ́nà àti àmì ìrìnnà mọ́.

**Rìn pẹ̀lú Òfin Ìrìnnà:** Má a rìn ní apá ọ̀tún ní gbogbo ìgbà. Kíyèsára nígbà tí o bá ń kọjá àwọn ẹlẹ́sẹ̀ àti kẹ̀kẹ́ ní apaá ọ̀tún. Nígbà tí o bá deé ibi tí ọ̀nà ti pàdé, lo ọ̀nà tí ó tọ́ fún ibi tí ò ń lọ (òsì, tààrà , ọ̀tún).




**Tọ́ka gbogbo Àyípadà:** Wo ẹ̀yìn wò kí o tó pààrọ̀ ìlà tàbí yípadà. Lo atọ́nà ìyípadà rẹ láti jẹ́ kí àwọn ìyókù mọ ohun tí o fẹ́ ṣe:

**Yà sí apá òsì láìléwu:**

- Yí padà sí apá òsì bi àwọn awakọ̀ ṣe máa ń ṣe nípa yíyà sí apá òsì òpópónà (ìlà àyípadà òsì ), tàbí
- Sọdá gẹ́gẹ́ bí ẹlẹ́sẹ̀, sísọ̀ kalẹ̀ lórí kẹ̀kẹ́ rẹ, kí o sì rìn kọjá ní ọ̀nà tí ó sọdá.

**Múra sílẹ̀ fún àsìkò ọ̀nà yíyọ̀:** Nígbà tí o bá ń ṣe ìtúkọ̀sílẹ̀ nínú òjò tàbí ìkúùkù, fi àyè díẹ̀ sílẹ̀ láti dúró kí o sì wá àlà pèpé àti àbò ohun ìwúlò, tí ó lè máa yọ̀.

**Hàn kedere - Lo àwọn iná ní alẹ́:** Nígbà tí o bá ń wakọ̀ ní alẹ́, òfin ìpínlẹ̀ Maryland ń retí iná funfun níí iwájú kẹ̀kẹ́ rẹ, àti pupa ní ẹ̀yìn. Wọ́n gbọ́dọ̀ hàn kedere láti ó kéré tán ìwọ̀n bàtà 600 sẹ́yìn. Ní àfikún, wọ́n pé kí o wọ aṣọ tí ó mọ́ ní ọ̀sán àti aṣọ aláwọ̀ bálabàla nígbà tí o bá ń rin ìrìn alẹ́.

### Ìrinṣẹ́ Kẹ̀kẹ́:

Gbogbo àwọn tí ó wà lábẹ́ ọdún 16 nílò akoto. Èyí kan ẹni tí a gbé sẹ́yìn tí kìí ṣe òun ni ó ń wa kẹ̀kẹ́. Bákan náà ni a dá àbá akoto fuún gbogbo ènìyàn káàkiri ọjọ́ orí .

Gẹ́gẹ́ bí òfin, gbogbo kẹ̀kẹ́ gbọ́dọ̀ ní :

- Ìjánu tí ó lè dá kẹ̀kẹ́ náà dúró láààrín ìwọ̀n ẹsẹ̀ 15 nígbà tí ó ń loọ ní ìwọn máìlì 10 láààrín wákàtí lórí ilẹ̀ gbígbẹ, tí ó sì mọ́.
- Iná funfun iwajú tí wọ́n lè rí láààrín ìwọ̀n bàtà 500 sẹ́yìn àti iná ẹ̀yìn pupa tí wọ́n lè rí láààrín ìwọ̀n bàtà 600 sẹ́yìn nígbá tí wọ́n bá wà á lálẹ́ tàbí ní àkókò tí ìmọ́lẹ̀ púpọ̀ kò sí.
- Ìjòkó tí ó ní àbò tí ó lẹ̀ típẹ́típẹ́ mọ́ kẹ̀kẹ́ náà , bí ó bá ń rin ìrìn àjò pẹ̀lú ọmọdé.
- Agolo kẹ̀kẹ́ , àpótí , tàbí àpò nígbà tí o bá ń gbé nǹkan kékeré kí ọwọ́ méjèèjì lè wà ní ọrùn kẹ̀kẹ́.

## N. Àwọn Ọkọ̀ Eléré Kékeré Onínà (Àwọn oríkì)

### Kẹ̀kẹ́ Onínà

- Ènìyàn ni ó máa ń wà wọ́n pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ agbára iná .
- Wọ́n ní ẹsẹ̀ tí ó ṣe ń tẹ̀ .
- Wọ́n ní ẹsẹ̀ méjì tàbí méta.
- Wọ́n ní agbára iná pẹ̀lú ìwọ̀n watts 750 tàbí kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ.

### Oríṣiríṣi Kẹ̀kẹ́ Onínà

**Ìpele 1:** Wọ́n ní agbára tí ó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ nígbà tí oníkẹ̀kẹ́ ń tẹ kẹ̀kẹ́ àtipé ó máa dúró nígbà tí kẹ̀kẹ́ bá dé eré sísá máìlì 20 láààrín wákàtí.

**Ìpele 2:** Wọ́n ní agbára tí ó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ yálà oníkẹ̀kẹ́ ń tẹ kẹ̀kẹ́ tàbí kò tẹ kẹ̀kẹ́ àtipé ó máa dúró nígbà tí kẹ̀kẹ́ bá dé eré sísá máìlì 20 láààrín wákàtí.

**Ìpele 3:** Wọ́n ní agbára tí ó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ nígbà tí oníkẹ̀kẹ́ ń tẹ kẹ̀kẹ́ àtipé ó máa dúró nígbà tí kẹ̀kẹ́ bá dé eré sísá máìlì 28 láààrín wákàtí.

### Scooter iná eléré sísá kékeré

- Wọ́n ṣètò wọn láti gbé olùdarí kẹ̀kẹ́ nìkan.
- Wúwo kéré ju 100 pounds.
- Wọ́n ní ẹsẹ̀ iwájú àti ti ẹ̀yìn ní ọwọ́ kan náà, tàbí ẹsẹ̀ kan níwájú àti ẹsẹ̀ méjì lẹ́yìn.
- Wọ́n ní ọrùn àti ibi tí oníkẹ̀kẹ́ lè gbé ẹsẹ̀ sí .
- Wọ́n ń lo agbára iná àti agbára ènìyàn .
- Lè ṣiṣẹ́ ní eré sísá tí ó tó máìlì 20 láààrín wákàtí.

Àkiyesi: Bí ìwọ bá lo ọkọ̀ onínà eléré kékeré, ṣe àgbéyẹ̀wò bóyá àwọn gbèdéke mìíràn wà.



**Rántí: Ohun tí ó tako òfin ni láti wakọ̀ láìsí ìwé adójútòfò ọkọ̀! Bí ìwọ kò bá ṣe adójútòfò fún gbogbo ọkọ̀, wọ́n máa jáwé fún ẹ tí ó tó $2,500 lórí ọkọ̀ kànọ̀nkan ní ọdọọdún .**

